**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA (NOUN)**

# YOR 471 : YORÙBA WRITTEN DRAMA (ERÉ-ONÍṢE ÀPILẸ̀KỌ YORÙBÁ)

COURSE CODE: YOR 471

COURSE TITLE: Yorùbá Written Drama

**PROFESSOR ỌLÁGÒKÈ ÀLÀMÚ**
Èkìtì State University, Ado-Ekiti
Nigeria

COURSE WRITER: Professor Ọlágòkè Àlàmú

COURSE EDITOR: Professor Dúró Adélékè

**ÌFÁÁRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ**

Nínú kọ́ọ̀sì yìí ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Módù mẹ́ta ni a pín iṣẹ́ yìí sí. Àwọn ohun tí a gbéyẹ̀wò ní abẹ́ módù kínní ni: Ìpinlẹ̀ṣẹ̀ àti ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá; ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá; ìlànà ìtúpalẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá àti àwọn ẹ̀dá-itàn inú eré-oníṣe.

Ní abẹ́ módù kejì ni a ti ṣe àtúpalẹ̀ ìfìwàwẹ̀dá, àgbéyẹ̀wò ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì inú eré-oníṣe, àyẹ̀wò ibùdó-ìtàn àti ìlò-èdè. Nínú módù kẹta ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àti àtúpalẹ̀ àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá márùn-ún. Àwọn eré-oníṣe náà ni *Ẹfúnṣetán Aníwúrà, Olú Ọmọ* àti *Ayé yẹ wọ́n tán* láti ọwọ́ Akínwùmí Ìṣọ̀lá, *Rẹ́rẹ́ Rún* láti ọwọ́ Ọládẹ̀jọ Òkédìjí àti *Ayégún* tí Adéníyì Àkàngbé kọ.

**ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ**

Àfojúsùn kọ́ọ̀sì yìí ni láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ní ìmọ̀ kíkún lórí àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá, oríṣìíríṣìí ọ̀nà tí a lè gbà ṣe àtúpalẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá àti àwọn iṣẹ́ tí òǹkọ̀wé ń fi ìwé rẹ̀ jẹ́.

**OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Ojúṣe akẹ́kọ̀ọ́ ni láti ka àti ṣe àmúlò ìwé yìí fún kọ́ọ̀sì yìí ní ìlànà ìkọ́ni láti ilé. Akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ ka iṣẹ́ yìí fún àmúṣe módù, iṣẹ́ ṣíṣe àti ìdánwò àṣekágbá.

## ÌGBÉLÉWỌ̀N TÍ OLÙKỌ́ YÓÒ MÁÀKÌ

Ìgbéléwọ̀n àtìgbàdégbà máa wáyé nípa ṣíṣe àmúlò ìwé yìí. Máàkì iṣẹ́ àyànṣe yóò jẹ́ ìdá ogójì (40%) àpapọ̀ máàkì. Ìdánwò àṣekágbá sì jẹ́ ìdá ọgọ́ta (60%) àpapọ̀ máàkì. Ó kéré tán akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ ṣe iṣẹ́ àyànṣe mẹ́ta tí olùkọ́ yóò máàkì kí o tó lè ṣe ìdánwò àṣekágbá.

**ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ ÀTI ÒSÙNWỌ̀N**

**ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ**

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn bí máàkì gbígbà yóò ṣe wáyé

| Ìgbéléwọ̀n | Máàkì |
|---|---|
| Iṣẹ́ Ṣíṣe/Àmúṣe módù 1 – 3 | Ogójì (40%) |
| Ìdánwò Àṣekágbá | Ọgọ́ta (60%) |
| Àpapọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

**ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ**

Vice Chancellor's Remark

Foreword

Ìfáárà sí kọ́ọ̀sì yìí

**MÓDÙ KÌN-ÍN-NÍ: ERÉ-ONÍṢE ÀPILẸ̀KỌ YORÙBÁ**

Ìpín Kìn-ín-ní: Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìpín Kejì: Ìpínsísọ̀rí Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá I

Ìpín Kẹta: Ìpínsísọ̀rí Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá II

Ìpín Kẹrin: Ìlànà Ìtúpalẹ̀ Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìpín Karùn-ún: Ẹ̀dá Ìtàn Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

**MÓDÙ KEJÌ: ÌFÌWÀWẸ̀DÁ, ÌSỌ̀RỌ̀ǸGBÈSÌ, IBÙDÓ-ÌTÀN ÀTI ÌLÒ-ÈDÈ NÍNÚ ERÉ-ONÍṢE ÀPILẸ̀KỌ YORÙBÁ**

Ìpín Kìn-ín-ní: Ìfìwàwẹ̀dá Nínú Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìpín Kejì: Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì Nínú Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìpín Kẹta: Ibùdó Ìtàn Nínú Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìpín Kẹrin: Ìlò Èdè Nínú Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìpín Karùn-ún: Ìpàrokò Nínú Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

**MÓDÙ KẸTA: ÀGBÉYẸ̀WÒ ERÉ-ONÍṢE ÀPILẸ̀KỌ YORÙBÁ MÁRÙN-ÚN**

Ìpín Kìn-ín-ní: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* – Akínwumí Ìṣọ̀lá

Ìpín Kejì: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* – Akínwumí Ìṣọ̀lá

Ìpín Kẹta: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún* – Ọládẹ̀jọ Òkédìjí

Ìpín Kẹrin: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayégún* – Adéníyì Àkàngbé

Ìpín Karùn-ún: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* – Akínwumí Ìṣọ̀lá

# MÓDÙ KÌN-ÍN-NÍ

**Ìpín Kìn-ín-ní: Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

4.2 Ìdàgbàsókè Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti ṣàlàyé ohun tí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ jẹmọ́. Lẹ́yìn náà ni a ó ṣàlàyé kíkún nípa ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le:

- ṣàlàyé ohun tí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá jẹ́
- dárúkọ díẹ̀ lára àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

(1) Kí ni eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?

(2) Sọ ìwúlò eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

Kí a tó máa sọ nípa erè-oníṣe àpilẹ̀kọ, ó yẹ kí á mọ ìtumọ̀ eré-oníṣe Yorùbá. Ògúndèjì (2001) fi yé wa pé, eré-oníṣe ni a gbà gẹ́gẹ́ bí àwọn eré tí a fi ṣe àgbékalẹ̀ èèyàn àti ìrírí wọn ní àwùjọ Yorùbá tí a sì tún fi èdè Yorùbá kọ tàbí tí a fi èdè Yorùbá gbé kalẹ̀. Yorùba ni ó sẹ̀dá irúfẹ́ eré yìí, àwọn Yorùbá náà sì ni ó máa ń jẹ́ oǹkàwé tàbi òǹwòran eré náà. Bí a ṣe ni erè-oníṣe apilẹ̀kọ, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni a ní èyí tí ó jẹ́ àpilẹ̀ṣe. Ṣùgbọ́n èyí tí ó jẹ́ àpilẹ̀kọ ní ó kàn wá gbọ̀ngbọ̀n nínú ẹ̀kọ́ yìí, ohun náà ni a ó sì máa gbéyẹ̀wò.

Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá jẹ́ eré tí a ṣe agbékalẹ̀ rẹ̀ sí inú ìwé ní ọ̀nà tí yóó dá àwọn òǹkàwé lárayá, tí yóò sì tún dá wọn lẹ́kọ̀ọ́ pẹ̀lú. Òǹkọ̀wé máa ń fi eré yìí sọ ìtàn. Àwọn òǹkọ̀wé eré-oníṣe máa ń fi eré wọn sọ̀rọ̀ nípa àwọn oríṣìíríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, yálà èyí tí ó ti ṣẹlẹ̀ tàbí èyí tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́, ó sì le jẹ́ èyí tí òǹkọ̀wé wòye pé ó lè ṣẹlẹ̀ ní ọjọ́ iwájú. Èyí ló máa ń jẹ́ ká rí àwọn oníṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí alóre ní ọ̀pọ̀ ìgbà.

Onírúurú kókó ọ̀rọ̀ ni òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ lè fi eré rẹ̀ pàsamọ̀ fún àwùjọ. Kókó náà le è dá lórí ẹ̀sìn, àṣà, ètò ọrọ̀-ajé, ọ̀rọ̀ òṣèlú, ètò ẹ̀kọ́, ìtàn ìwásẹ̀, ìtàn ọjọ́ọjọ́un, ìjà orogún, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ohun èlò pàtàkì tí ó jẹ òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ lógún jù lọ ni àṣà. Àwọn òǹkọ̀wé a máa gùn lé àṣà àwùjọ láti ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà wọn, wọ́n sì máa ń pe àkíyèsí àwùjọ sí àwọn ìyàtọ̀ tó dé bá àwùjọ, wọn a máa ṣe àfihàn àwọn ohun tí ó dára ní àwùjọ pẹ̀lú èyí tó kù káàtó.

Ìlànà tí òǹkọ̀wé gbà ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà rẹ̀ ni ó máa fi hàn gẹ́gẹ́ bíi eré-oníṣe. Nínú eré-oníṣe, ìlànà ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì ni àwọn òǹkọ̀wé máa ń lò láti ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ wọn. A ó kọ orúkọ ẹ̀dá ìtàn tí ó sọ̀rọ̀, a ó sì kọ ọ̀rọ̀ tí ó sọ sí iwájú orúkọ náà, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ náà ni a ó ṣe fún ẹni tí ó fèsì ọ̀rọ̀.

## 4.2 Ìdàgbàsókè Eré Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Onírúurú akitiyan ló ti wáyé lórí ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Ọ̀kan lára àwọn akitiyan ni èyí tí àwọn oníwèé ìròyìn ṣe. Ìwé ìròyìn tí a mọ̀ sí *Elétí Ọfẹ* ni ó gbé eré oníṣe àpilẹ̀kọ kan jáde ní ọjọ́ kẹrìnlélógún oṣù kẹta ọdún 1923. Wọ́n fún àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí ní àkọlé mẹ́ta. Àkọlé àkọ́kọ́ ni wọ́n pè ní "Rẹ́rìnín Díẹ̀", tí àkọlé kejì sì jẹ́

"Pamí ń kú obìnrin" nígbà tí wọ́n pe àkọlé kẹta ní "Ẹni máa kú pàdé ẹni máa pa á." Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ ni Akíntan tí ó jẹ́ olóòtú ìwé ìròyìn *Elétí Ọfẹ* máa ń tẹ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ náà jáde nínú ìwé ìròyìn rẹ̀. Àhunpọ̀ eré-oníṣe tí Akíntan gbé jáde yìí kò gùn rárá bẹ́ẹ̀ ni kò sì lọ́jú pọ̀, iṣẹ́ tí ó fẹ́ rán àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ni ó ṣe pàtàkì sí i, kò mú ọ̀rọ̀ ìfìwàwẹ̀dá ní ọ̀kúnkúndùn.

Ògúnṣínà (1982) fi yé wa pé ìlú Èkó ni ibùdó-ìtàn eré-oníṣe ti Akintan kọ. Nínú ìwòye Ògúnṣínà eré-oníṣe náà pegedé nípa ìlò èdè torí pé àwọn èròjà bí i ìlò èdè òǹkọ̀tàn, àwàdà àti ìpanilẹ́rìnín hàn nínú rẹ̀. Ṣùgbọ́n, torí pé kò sí ìdánilójú pé Akintan sọ eré-oníṣe náà di odidi ìwé, a kò le pe é ní ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ àkọ́kọ́.

Ní ọdún 1958 ni àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ méjì mìíràn tún jáde. Ìkíni ni wọ́n pe àkọlé rẹ̀ ní *Pàsáṇ sìnà*, tí Adébóyè Babalọlá kọ, ìkejì ni èyí tí Ọdúnjọ kọ tí ó sì pe àkọlé rẹ̀ ní *Agbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo*. Àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ méjèèjì yìí ni a rí tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí eré-oníṣe àkọ́kọ́. Lẹ́yìn 1958 tí àwọn ìwé wọ̀nyí ti jáde, a kò gbúròó eré oníṣe àpilẹ̀kọ kankan mọ́ tó fi di ọdún 1964 tí eré-oníṣe *Ká sòótọ́ ká kú* jáde láti ọwọ́ Ọlánipẹ̀kun Ẹ̀san. Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bẹ̀rẹ̀ sí jáde lọ́kan-ò-jọ̀kan láti ọdún 1965. Lára àwọn eré tí ó jáde ni Fálétí *Wọ́n rò pé wèrè ni*, Ọlábímtán *Olúwa ló mẹjọ́ dá* àti Ẹ̀san (1968) *Òrékelẹ́wà*.

Ṣùgbọ́n lọ́wọ́ lọ́wọ́ tí à ń sọ̀rọ̀ yìí onírúurú ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá ni àwọn òǹkọ̀wé ti kọ, tí ó sì wà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ilé ìtàwé.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé òǹkọ̀wé máa ń fi eré-oníṣe àpilẹ̀kọ sọ ìtàn tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ yálà èyí tó ti ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn, èyí tí ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ tàbí èyí tí ó ń bọ̀ wá ṣẹlẹ̀. Àwọn àpẹ́ẹ̀rẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí ó máa ń wà níbẹ̀ ní ẹ̀sìn, ètò òṣèlú, ọrọ̀ ajé àti àwọn ìtàn lóríṣiríṣi. Àṣà àwùjọ ni èròjà pàtàkì tí òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ máa ń ṣàmúlò nínú àpilẹ̀kọ rẹ̀. Ònkọ̀wé a sì máa lo ìlànà ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì fún àgbékalẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ rẹ̀.

A tún fi yé wa pé, E. A. Akintan bẹ̀rẹ̀ sí í gbé eré onítàn jáde nínú ìwé ìròyìn *Elétí Ọfẹ* ní ọdún 1923. Ṣùgbọ́n a kò le è pe eré onítàn Akintan yìí ní àkọ́kọ́ irú rẹ̀ torí pé kò sí

ìdánilójú pé a sọ ọ́ di odidi ìwé. *Pàṣán sìnà* àti *Agbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* tí Adébóyé Babalọlá àti Ọdúnjọ kọ ní ọdún 1958 ni a le pè ní eré-oníṣe àpilẹ̀kọ àkọ́kọ́

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

(1) Ṣàlàyé ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

(2) Ipa wo ni E. A. Akintan kó lórí ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?

(3) Ìwé wo ni ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá àkọ́kọ́?

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Ògúnṣínà, B. (1980). Ipa tí àwọn ìwé ìròyìn kó nínú ìdàgbàsókè lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá. *Yorùbá Gbòde: Ìwé Àtìgbàdégbà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè Yorùbá Ilẹ̀ Nàìjíríà*. No 5.

Ògúndèjì, P. (2001). Eré-oníṣe Yorùbá. *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá- èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Ìjẹ̀bú –Òde. Shebiotimọ Publications (pp 167-188)

**Ìpín Kejì: Ìpínsísọ̀rí Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ 1**

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ìpínsísọ̀rí Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá I
4.2 Ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà nínú lílo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Ní abala yìí ni a ó ti pín eré-oníṣe àpilẹ̀kọ sí àwọn ìsọ̀rí ìsọ̀rí ní ìbámu pẹ̀lú iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe tàbí ohun tí à ń fi wọ́n ṣe. A ò ní gbàgbé láti sọ àwọn ìyàtọ̀ tó wà láàárín àwọn ìsọ̀rí náà. A ó tún gbìyànjú láti tọ́ka sí àwọn àpẹẹrẹ ìwé eré-oníṣe tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le:

- ṣe ìpínsíṣọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá
- sọ àwọn ìyàtọ̀ tó wà láàárín àwọn ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan tí a pín eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá sí.
- tọ́ka sí àwọn ìwé tí ó bá ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan lọ.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

(1) Àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá wo ni o ti bá pàdé?

(2) Irúfẹ́ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ wo ni o lérò pé wọ́n jẹ́?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Ìpínsísọ̀rí Eré Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìpínsíṣọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ, a lè gbé e ka orí òṣùnwọ̀n méjì. Òsùnwọ̀n kìn-ín-ní ni èyí tí í ṣe **lílo ìdanilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n**, nígbà tí **lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi òsùnwọ̀n** sì jẹ́ ìlànà kejì. Àwọn ìsọ̀rí méjèèjì wọ̀nyí ló tún ní ẹ̀ka. Ìsọ̀rí àkọ́kọ́ (ìsọ̀rí lílo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n) tí a mẹ́nu bà yìí ni àwọn onímọ̀ bí i Ìṣọ̀lá (1981), Ọlátúnjí àti Ògúndèjì (1986) àti Adéjùmọ̀ (2001) tún pín sí ọ̀nà márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Torí náà ìṣọ̀rí àkọ́kọ́ yìí ni a ó máa yẹ̀wò nínú ẹ̀kọ́ kejì tí a wà yìí. Àwọn ọ̀nà márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí àwọn onímọ̀ pín ìsọ̀rí àkọ́kọ́ sí ni ìwọ̀nyí:

(i) Eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà

(ii) Eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ṣíṣe àmúlò ìtàn gidi

(iii) Eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀

(iv) Eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìfẹ̀hónúhàn

(v) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa títanijí

## 4.2 Ìsọ̀rí Lílo Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Gẹ́gẹ́ bí Òsùnwọ̀n

Báyìí, a ó bẹ̀rẹ̀ síí ṣe àlàyé àwọn ẹka tí ó wa lábẹ́ ìṣọ̀rí lílo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

### (1) Eré oníṣe-àpilẹ̀kọ adánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà

Àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí yìí jẹ́ èyí tí àwọn ẹ̀dá ìtàn inú rẹ̀ máa ń gba èrè iṣẹ́ ọwọ́ wọn bí ó ṣe yẹ, èyí ni pé bí ẹ̀dá-ìtàn inú èrè bá ṣe jókòó ní yóó bá ara rẹ̀ nínú fọ́tò láìsí ìrẹ́jẹ kankan. Bí wọ́n bá ṣe rere, wọn yóò gba rere. Bí ó bá sì jẹ́ pé ibi ni wọ́n hù ní ìwà, ibi náà ni wọn yóò gbà gẹ́gẹ́ bí èrè iṣẹ́ wọn. Ọ̀nà tààrà ni ìsọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí ń gbà dá àwọn òǹkàwé lẹ́kọ̀ọ́ tí ó sì ń dá wọn lára yá. Àwọn àpẹẹrẹ ìwé eré oníṣe àpilẹ̀kọ tí ó wà ní ìsọ̀rí yìí ni *Pàṣán ṣìnà* láti ọwọ́ Adébóyè Babalọlá, *Agbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* láti ọwọ́ Ọdúnjọ, *Wọ́n rò pé wèrè ni* àti *Ìdàámú páàdì mínkáílù* láti ọwọ́ Adébáyọ̀ Fálétí àti *Àbíkú Solóògùn dèké* tí Olú Owólabí kọ. A tún rí

*Afàgò kẹ́yin àparò* tí Àrìnpé Adéjùmọ̀ kọ, *O ṣèyí tán* láti ọwọ́ Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé gẹ́gẹ́ bí ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ adánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà. Àwọn mìíràn tún ni *Ayédáadé* láti ọwọ́ Àyànó àti *Ayégún* láti ọwọ́ Adéníyì Àkàngbé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**(2) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ṣíṣe àmúlò ìtàn gidi**

Èyí ni àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí àwọn òǹkọ̀wé máa ń gbé ka orí ìtàn kan tí ó ti ṣẹlẹ̀ rí láti jẹ́ kí àwọn òǹkàwé kẹ́kọ̀ọ́ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ àtẹ̀yìnwá. Ìtàn gidi lè jẹ́ èyí tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ààtò ìlú, ètò mọ̀lẹ́bí, ọ̀rọ̀ ọ̀ṣèlú, olórogún àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àpẹẹrẹ àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bẹ́ẹ̀ ni *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ, *Baṣọ̀run Gáà* tí Adébáyọ̀ Fálétí kọ, *Líṣàbí Agbòǹgbò Àkàlà* láti ọwọ́ Olú Owólabí àti *Ògèdèǹgbé Agbógungbórò* tí Olúsẹ̀san Ajéwọlé kọ. Gbogbo àwọn ìwé wọ̀nyí ló jẹ́ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí ó ṣàmúlò ìtàn gidi fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà àti fún ìdánilárayá pẹ̀lú.

**(3) Eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìfẹ̀dásẹ̀fẹ̀**

Eré-oníṣe yìí máa ń ṣàmúlò ìfiniṣẹ̀fẹ̀, yẹ̀yẹ́ tàbí ẹ̀sín gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti bu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà ìbàjẹ́ láwùjọ. Òǹkọ̀wé máa ń gbé àwọn ẹ̀dá ìtàn sí ipò tí a ó ti fi wọ́n ṣe yẹ̀yẹ́ nínú ìṣọ̀rí eré yìí. Lára àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí ó jẹ́ afẹ̀dásẹ̀fẹ̀ ni, *Àṣírí tú* tí Babátúndé Ọlátúnjí kọ, *Aabẹ́ Àbò* láti ọwọ́ Akínwùmí Ìṣọ̀lá, *Alàgbà Jerímáyà* tí Oyètúndé Awóyẹlé kọ àti *Ọlọ́run Lúgọ* láti ọwọ́ Débọ̀ Awẹ́.

**(4) Eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìfẹ̀hónúhàn**

Ìfẹ̀hónúhàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà kan gbòógì tí àwọn ènìyàn ń gbà láti jà fún ẹ̀tọ́ wọn, àwọn òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ máa ń ṣàmúlò ìfẹ̀hónúhàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti ṣe àgbékalẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ wọn láti dá àwùjọ lẹ́kọ̀ọ́ pàápàá jùlọ nípa bí ènìyàn tàbí àwùjọ ṣe le gba ara wọn sílẹ̀ lóko ìmúnisìn. Irú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ báyìí máa ń fún àwọn ènìyàn ní òye lórí ọ̀nà tí wọn yóò gbà láti gba ara wọn lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ láwùjọ. Àpẹẹrẹ àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bẹ́ẹ̀ ni *Iná ràn* tí Adésọlá Ọlátẹ́jú kọ àti *Rẹ́rẹ́ Rún* láti ọwọ́ Ọládẹ̀jọ Òkédìjí.

**(5) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa títanijí**

Ìtanijí ni pípe àkíyèsí tàbí títa ènìyàn lólobó sí ohun kan tí ó ń bọ̀ wá ṣẹlẹ̀ láìpẹ́ tàbí tí ó ti ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́ ṣùgbọ́n tí ènìyàn kò kọbiara sí. Nígbà tí a bá wá ń sọ̀rọ̀ nípa eré oníṣe tó ní í ṣe pẹ̀lú ìtanijí, àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ báwọ̀nyìí ni àwọn eré tó jẹ́ pé wọ́n máa ń tètè pe àkíyèsí ènìyàn sí ohun tí ó ń bọ̀ wá ṣẹlẹ̀ láìpẹ́, yálà búburú tàbí rere, ìṣẹ̀lẹ̀ náà le jẹ́ èyí tí ó jẹ mọ́ ètò òṣèlú, ìjọba ìbílẹ̀, ọ̀rọ̀ nípa ètò ọrọ̀ ajé tàbí ètò ẹ̀kọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Òǹkọ̀wé irúfẹ́ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bẹ́ẹ̀ sì máa ń gbìyànjú láti ṣàwárí àwọn ọ̀nà tí ènìyàn yóò rìn láti ṣẹ́gun ìṣòro, bí ó bá jẹ́ pé ohun tí ó tani lólobó sì jẹ́ nǹkan tí ó léwu. Àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí yìí máa ń sáábà ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìfẹ̀hónúhàn.

**4.2 Ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà nínú lílo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òṣùnwọ̀n**

Ní ìpele yìí, a gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún wa pé, kò sí bí ìwọ̀núbọ̀nú kò ṣe ni wà nínú gbogbo àwọn ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá tí a ṣàlàyé. Lákọ̀ọ́kọ́, gbogbo àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ wọ̀nyí ni ó ń dánilẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n sì ń dánilárayá, èyí ni ìjọra tàbí ìwọ̀núbọ̀nú gbogbogbòò tí ó kárí gbogbo ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Síwájú sí i, eré-oníṣe tí a pè ní adánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tàárà náà ni òǹkọ̀wé lè ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ nípa síṣàmúlò ìtàn gidi, èyí ni pé eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa àmúlò ìtàn gidi le wáyé ní ọ̀nà tàárà tí yóò sì yé àwọn òǹkàwé yékéyéké.

Ẹ̀wẹ̀, a tún le ṣàmúlò ìtàn gidi láti ṣàgbékalẹ̀ eré-oníṣe ìfẹ̀dásẹ̀fẹ̀. Nínú irúfẹ́ eré yìí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀dá ènìyàn kan ni a fi ń ṣe ẹ̀fẹ̀, síbẹ̀ ó le jẹ́ ìtàn gidi. Ìfẹ̀dásẹ̀fẹ̀ yìí sì tún le dánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tàárà tí kò sì ní lọ́jú rárá. Torí náà gbogbo àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ wọ̀nyí ni wọ́n wọnú ara wọn. Fún àpẹẹrẹ, bí a bá wo ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ́ *Ayé yẹ wọ́n tán* àti *Ayégún* a ó ríi pé àwọn ìwé eré-oníṣe méjèèjì yìí ni ó gbé àbùdá ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìfẹ̀dásẹ̀fẹ̀ àti ìtanijí wọ̀. A sì rí àwọn eré-oníṣe bí i *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* àti *Olú Ọmọ* tó jẹ́ pé àbùdá ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìsọ̀tàn ló borí nínú ìgbékalẹ̀ wọn. Ọ̀nà kan pàtó tí a rò pé ó dára jù láti pín eré-oníṣe Yorùbá sí ìsọ̀rí ni fífi àwọn àbùdá tó rinlẹ̀ jù láti ṣe ìpínsísọ̀rí wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti jẹ̀ kí ó di mímọ̀ fún wa pé òsùnwọ̀ méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni awọn onímọ̀ ṣàmúlò fún ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá, ***lílo ìdanilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n, àti lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi ọ̀sùwọ̀n***. A ṣe àgbéyẹ̀wò lílo ìdanilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n, nínú rẹ̀ ni a sì ti rí àwọn ẹka márùn-un ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí ìpínsísọ̀rí ní eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà, eré oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ṣíṣe àmúlò ìtàn gidi, eré-oníṣe adanilẹ́kọ̀ọ́ afẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀, eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ afẹ̀hónúhàn àti eré-oníṣe adánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìtanijí. Ní ìparí ẹ̀kọ́ yìí ni a ti ṣe àlàyé àwọn ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà nínú àwọn ẹ̀ka márùn-un tó wà ní abẹ́ ìṣọ̀rí lílo ìdanilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

(1) Ṣe ìpínsísọ̀rí àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

(2) Ṣàlàyé ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà nínú àwọn ẹ̀ka márùn-un tó wà ní abẹ́ ìṣọ̀rí lílo ìdanilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ògúnṣínà, B. (1980). Ipa tí àwọn ìwé ìròyìn kó nínú ìdàgbàsókè lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá. *Yorùbá Gbòde: Ìwé Àtìgbàdégbà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè Yorùbá Ilẹ̀ Nàìjíríà.* No 5.

**Ìpín Kẹta: Ìpínsísọ̀rí Eré Oníṣe Àpilẹ̀kọ II**

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìpínsísọ̀rí Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá II

4.1.1 Lílo Kókó Ìtàn Gẹ́gẹ́ bí Orísun

4.1.2 Ìwọ́núbọ̀nú tí ó wà nínú lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n

5.0 Ìsọnísọ́kí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àtẹ̀yìnwá ti jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé méjì ni ìsọ̀rí tí àwọn onímọ̀ pín eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá sí. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sàlàyé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìsaáju. Àlàyé kíkún si ti wáyé lórí ìpínsísọ̀rí àkọ́kọ́ tíí ṣe ***lílo ìdanilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n***. Ní ìpele yìí a ó lọ tààrà láti sàlàyé ìpínsísọ̀rí tíí ṣe ***lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi òsùnwọ̀n.*** Níbẹ̀ náà ni a ó ti mẹ́nu ba àwọn ìwọ̀núbọ̀nú tí tó wà láààrín àwọn ẹka tí ó wà nínú ìsọ̀rí kejì yìí. A ó tún gbìyànjú láti tọ́ka sí àwọn àpẹẹrẹ ìwé eré-oníṣe tí ó wà ní abẹ́ ìṣọ̀rí kọ̀ọ̀kan.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le:

- sàlàyé àwọn ẹka tí ó wa ní abẹ́ ìsọ̀rí lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi ọ̀ṣùwọ̀n nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá
- sọ àwọn ìyàtọ̀ àti ìwọ̀núbọ̀ní tó wà láààrín àwọn ẹka abẹ́ ìsọ̀rí náà.
- tọ́ka sí àwọn ìwé tí ó bá àwọn ẹka kọ̀ọ̀kan inú ìsọ̀rí náà mu.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

(1) Ṣàlàyé àwọn ẹka tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí ***lílo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bíi òsùnwọ̀n*** nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàlàyé ní ìpín kejì.

(2) Sọ kókó ìtàn inú ìwé eré-oníṣe kan tí o ti kà rí.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Lílo Kókó Ìtàn Gẹ́gẹ́ bí Òsùnwọ̀n**

Báyìí, a ó bẹ̀rẹ̀ síí ṣe àlàyé àwọn ẹka tí ó wa ní abẹ́ ìsọ̀rí *lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi òsùnwọ̀n* fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

Ní abẹ́ ìpínsísọ̀rí kejì tí í ṣe ìsọ̀rí *lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi òsùnwọ̀n* ni a ti rí àwọn ẹ̀ka wọ̀nyìí:

(i) Eré-oníṣe amẹ́kúnwá/ládojúdé

(ii) Eré-oníṣe amẹ́rìnínwá

(iii) Eré-oníṣe amẹ́kún/mẹ́rìnínwá

**4.1.1 Lílo Kókó Ìtàn Gẹ́gẹ́ bí Orísun**

Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa kókó ìtàn, kókó ìtàn jẹ́ ohun kan tí ó ṣe pàtàkì nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá torí pé, òhun ni láríjà ìdí tí a fi ṣe àgbékalẹ̀ àpilẹ̀kọ náà, àwọn kókó yìí sì ni àpilẹ̀kọ dá lórí, òhun ni ó dúró gẹ́gẹ́ bíi ìsọníṣókí àpilẹ̀kọ tí yóò sì dá òǹkàwé lárayá. A ó túbọ̀ ṣàlàyé ohun tí à ń pè ní kókó ìtàn nínú kọ̀ọ̀sì yìí níwájú.

Ó ṣe é ṣe kí á ṣe àmúlò kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi òṣùwọ̀n nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ. Bí a bá wá ṣàmúlò kókó ìtàn, ọ̀nà mẹ́ta pàtàkì ni a lè pín ìsọ̀rí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá sí:

(i) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kúnwá/ládojúdé

(ii) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́rìnínwá

(iii) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kún/mẹ́rìnínwá

Báyìí, a ó ṣe àlàyé àwọn ẹka tí ó wa lábẹ́ ìsọ̀rí lílo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

**(1) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kúnwá tàbí ládojúdé**

Ẹ̀yí ni irúfẹ́ eré-oníṣe tí òǹkọ̀wé máa ń mọ̀-ọ́n-mọ̀ ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ láti jẹ́ kí òǹkàwé kọ́ ẹ̀kọ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó máa ń dá lérí ohun ìbànújẹ́ kan. Ẹ̀yà eré-oníṣe yìí máa ń jẹ́ èyí tí yalà olú ẹ̀dá-ìtàn tàbí àwọn akópa máa ń kojú ìṣòro tí ó sì jẹ́ pé ìṣòro bẹ́ẹ̀ kìí lójútùú títí eré náa yóò fi wá sí òpin. Orúkọ mìíràn tí wọ́n tún fún ẹ̀yà eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí ni eré-oníṣe ládojúdé torí pé ó máa ń kó àwọn òǹkàwé láyà sókè títí di òpin, ṣùgbọ́n ṣá o, ó máa ń kọ́ òǹkàwé ní ẹ̀kọ́ tó jinlẹ̀.

Àpẹẹrẹ irúfẹ́ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí ni *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Òkédìjí kọ àti *Ọba Kò So* láti ọwọ́ Dúró Ladipọ.

**(2) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́rìnínwá**

Ẹ̀yà eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí jẹ́ èyí tí ó máa ń dẹ́rìn pẹ̀ẹ̀kẹ́ òǹkàwé gẹ́gẹ́ bí orúkọ tí a fi fún un. Nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí, ìṣàmúlò àwàdà máa ń peléke gan-an torí pé àfojúsùn òǹkọ̀wé ni láti fi eré náà dá ẹ̀rín pa àwọn ènìyàn kí ó sì mú inú àwùjọ dùn. Torí náà onírúurú ẹ̀dá-ìtàn ni òǹkọ̀wé máa ń lò, òǹkọ̀wé yóò sì gbé ìwà, ìṣe àti irísí tí ó le panilẹ́rìn-ín bọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn náà lọ́rùn. Ìsọ̀rọ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn, ìwọṣọ, ìṣesí, ìrísí àti ìhùwàsí wọn ni yóò jẹ́ ohun adẹ́rìn-ín pa òǹkàwé láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin eré. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà nínú irú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí, àwọn ohun tí ó le báni nínú jẹ́ le wáyé ṣùgbọ́n kò ní tó nǹkan, àwọn ohun apanilẹ́rìn-ín ni ó peléke jùlọ. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé òǹkọ̀wé le ṣàmúlò ọgbọ́n àtinúdá rẹ̀ láti ṣe àgbékalẹ̀ ohun tí ó burú ní ọ̀nà tí yóò pa òǹkàwé lẹ́rìn-ín. Ní àkótán, ohun ìdùnnú ni ó máa ń jẹ́ olúborí nínú ẹ̀yà eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí. Lára àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí ni a ti rí *Alàgbà Jeremáyà* tí Awóyẹlé kọ àti *Abẹ́ Àbò* láti ọwọ́ Akínwùmí Ìṣọ̀lá.

**(3) Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kún-mẹ́rìnínwá**

Nínú ẹ̀yà eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí a pè ní amẹ́kún-mẹ́rìnínwá, àwọn àbùdá tí ó jẹ mọ́ ẹkún àti ẹ̀rín ni ó máa ń jẹ́ ọgbọọgba. Nígbà tí ìtàn bá dojúdé dé gbèdéke kan, tí ìbànújẹ́ ti ń dorí òǹkàwe kodò, òǹkọ̀wé yóò tún lo ọgban àtinúdá rẹ̀ láti ṣe àmúlò àwọn ohun tí yóó

pa òǹkàwe ní ẹ̀rín, èyí ni yóò dúró gẹ́gẹ́ bí i atura fún òǹkàwe tí inú rẹ̀ yóó sì dùn láti tẹ̀síwàjù nínú kíkà ìwé náà. Ọgbọọgba ni ìbànújẹ́ àti ayọ̀ tí ó máa ń wà nínú àhunpọ̀ ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kún-mẹ́rìnínwá náà.

## 4.4 Ìwọ́núbọ̀nú tí ó wà nínú lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n

Ní abala yìí ni a ó ti ṣàlàyé àwọn ìjọra tí ó wà nínú àwọn ẹka ti ìlànà lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n pín sí. Kò sí bí a ṣe lè pààlà sí àárín àwọn ẹka yìí tí kò ní sí ìwọ́núbọ̀nú nígbà tí a bá ṣàmúlò kókó gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n. Àwọn àbùdá eré-oníṣe mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni wọ́n ní àwọn àbùdá kan tí ó jọra.

Àwọn ìsọ̀rí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni ó ń dánilẹ́kọ̀ọ́ lábẹ́ àkóso bó ti wù kí éré tó. Yálà inú òǹkàwé dùn tàbí ó bàjẹ́ lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìwé náà tán, ó di dandan kí ó rí ẹ̀kọ́ kan kọ́ níbẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn àbùdá eré-oníṣe àpilẹ̀kọ méjèèjì (amẹ́kún àti mẹ́rìnínwá) ni ó ń dánilẹ́kọ̀ọ́. Síwájú síi, bí a bá ṣàkíyèsí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá dáadáa, òǹkọ̀wé máa ń ṣe àmúlò àwàdà àti ọgbọ́n mìíràn láti pa ènìyàn lẹ́rìn-ín tí inú òǹkàwé yóò sì máa dùn tí yóò fi parí ìwé náà ní kíkà. Ṣùgbọ́n kò sí bí sánmọ̀ ṣe lè funfun tó tí a kò ní rí dúdú díẹ̀, bí ó bá tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀rín ni ó peléke nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá tí ó jẹ́ mẹ́rìnínwá, ní ìgbà mìíràn, òǹkọ̀wé lè gbé ìwà ìkà wọ inú ẹ̀dá-ìtàn kan, tí yóò sì máa ṣe ìkà fún àwọn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn ní èyí tí yóò ba òǹkàwé nínú jẹ́, ṣùgbọ́n ṣá o, lẹ́yìn-ò-rẹyìn, àwọn ẹ̀dá-ìtàn tí a ṣe ní ìkà yóò borí ogun, ọ̀rọ̀ gbogbo yóò sì já sí ẹ̀rín. Ẹ̀wẹ̀, bí ó ṣe wà ní lììkì ní ó wà ní gbàǹja, eré oníṣe tí ó jẹ́ amẹ́kúnwa náà le ni ohun apanilẹ́rìn-ín nínú nígbà mìíràn láti le è mú ọkan òǹkàwé balẹ̀ díẹ̀, ṣùgbọ́n ṣá o, àbùdá amẹ́kúnwá yìí ni yóò jẹ́ olúborí

Ní ìparí, èyí túmọ̀ sí pé, a lè bá ẹ̀rín díẹ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kúnwa bẹ́ẹ̀ náà sì ni a lè rí ìbànújẹ́ díẹ̀ nínú èyí tí ó jẹ́ apanilẹ́rìnín.

## 5.0 Ìsọníṣókí

A jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún wa pé ẹka mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó wà ní abẹ́ lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Àwọn náà sì ni; eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kúnwá/ládojúdé, eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́rìnínwá àti eré-oníṣe àpilẹ̀kọ amẹ́kún-mẹ́rìnínwá. Àlàyé sì tún wáyé lórí àwọn ìwọ̀núbọ̀nú tí ó jẹyọ láàárín àwọn ẹ̀ka náà.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

(1) Ṣàlàyé àwọn ẹka tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí *lílo kókó ìtàn gẹ́gẹ́ bíi òsùnwọ̀n* nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

(2) Sọ àwọn ìyàtọ̀ àti ìwọ̀núbọ̀ní tó wà láàárín àwọn ẹka abẹ́ ìsọ̀rí náà.

(3) Tọ́ka sí àwọn ìwé tí ó bá àwọn ẹka kọ̀ọ̀kan inú ìsọ̀rí náà mu.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Umukoro, M. (2002) *Drama and Theatre in Nigerian Schools*. Ibadan: Caltop Publications (Nigeria) Limited.

**Ìpín Kẹrin: Ìlànà Ìtúpalẹ̀ Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìlànà Ìtúpalẹ̀ Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

4.1.1 Kókó-ìtàn

4.1.2 Àhunpọ̀-ìtàn

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Ní abala yìí, a ó ṣàlàyé ohun tí à ń pè ní kókó-ìtàn, àhunpọ̀-ìtàn, ibùdó-ìtàn, ẹ̀dá-ìtàn, àti ìfiwàwẹ̀dá.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- ṣe àlàyé ohun tí à ń pè ní kókó-ìtàn, àhunpọ̀-ìtàn, ibùdó-ìtàn, ẹ̀dá-ìtàn àti ìfiwàwẹ̀dá.
- sọ ìyàtọ̀ tó wà láàárín kókó-ìtàn àti àhunpọ̀-ìtàn.
- ṣàlàyé ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Ṣàlàyé ní ṣókí àwọn ẹ̀ka tí a gbéyẹ̀wò lórí lílo kókó-ìtàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀ṣùwọ̀n ìpínsísọ̀rí àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá (wo ìpín kẹta)

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Ìlànà Ìtúpalẹ̀ Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

### 4.1.1 Kókó Ìtàn

Kókó ìtàn ni a lè pè ní gbòǹgbò ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀, òye ọ̀rọ̀ tí iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan dá lé lórí. A lè pè é ní ẹ̀kọ́ tàbí ọgbọ́n tí wọ́n fẹ́ fi yé wa nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀. Àpapọ̀ kókó ọ̀rọ̀ yìí ni àwọn kan ń pè ní lááríjà ìtàǹ. Nígbà mìíràn kókó ọ̀rọ̀ máa ń ju ẹyọ kan lọ nínú ìtàn, torí náà, a ní láti jẹ́ kí ó yé wa pé kókó ìtàn le è pín sí ọ̀nà méjì:

(i) Olú kókó-ìtàn

(ii) Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó-ìtàn

**(i) Olú kókó-ìtàn**

Èyí ni kókó ọ̀rọ̀ tí ó ṣe pàtàkì jùlọ, ohun ni ó la gbogbo iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kọjá pátápátá, ó ṣe é ṣe kí ènìyàn rí olú kókó ọ̀rọ̀ méjì, tí ọ̀kan kò sì ní ju ìkejì lọ.

**(ii) Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó-ìtàn**

Èyí ni àwọn kókó kékèké tí ó máa ń dúró gẹ̀gẹ̀ bíi ọmọ inú olú kókó, tí à ń bá pàdé nínú iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀, apá kan ni a ti máa ń bá wọn pàdé, àwọn kókó yìí kìí la gbogbo iṣẹ́ ọnà já, ó jẹ́ kókó tí ó máa ń mú kí òye óńkàwé kún dáadáa nípa olú kókó ọ̀rọ̀.

### 4.1.2 Àhunpọ̀-ìtàn

Ètò ìṣẹ̀lẹ̀ inú lítíréṣọ̀ kan ní sísẹ̀-n-tẹ̀lé láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé ìparí gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ṣe tò ó ni à ń pè ní àhunpọ̀-ìtàn. Nínú àlàyé Ògúndèjì (1992: 11) ó di mímọ̀ fún wa pé àhunpọ̀ ìtàn wà lára awọn fọ́nrán tí ó ṣe pàtàkì fún àtúpalẹ̀ eré-oníṣe.

Ìlànà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó wà fún òǹkọ̀wé láti ṣe àgbékalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn rẹ̀:

(i) Ìlànà àrògún ojú ayé

(ii) Ìlànà àrògún ajẹmọ́nà

**(i) Ìlànà àrògún ojú ayé**

Nínú ìlànà yìí òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá gbọ́dọ̀ rí i pé ọ̀nà tí òún gbà hun ìtàn nínú eré tí òun ń kọ kò lọ́jú pọ̀ rárá. Ètò ìṣẹ̀lẹ̀ nínú eré-oníṣe gbọ́dọ̀ bá àrògún ojú ayé mu. Bí àpẹẹrẹ bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìgbé ayé ẹ̀dá-ìtàn kan, a ní láti bẹ̀rẹ̀ nípa ìbí rẹ̀, kí á sọ bí ó ṣe lo ìgbà èwe rẹ̀ títí tí ó fi di àgbàlagbà. Àpẹẹrẹ ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà yìí ni *Afàgò Kẹ́yin Àparò* láti ọwọ́ Àrìnpé Adéjùmọ̀.

Àhunpọ̀ eré-oníṣe máa n pín sí ọ̀nà mẹ́ta. Èyí ni ìbẹ̀rẹ̀, àárín àti òpin àhunpọ̀ ìtàn. Òǹkọ̀wé eré-onítàn máa n fi ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn pàjùbà ni. Nínú ìpàjùbà yìí ni yóó ti máa tá àwọn òǹkàwé lólobó nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí yóò wáyé nínú eré náà. Ní àárín àhunpọ̀-ìtàn ni onírúurú àwọn òṣèré tí máa n wáyé. Ní kété ti eré-oníṣe kan bá ti dé òténté ni ìtàn yóò ti máa sáré lọ sópin. Ní òpin àhunpọ̀-ìtàn ni òǹkàwé eré-onítàn ti máa n yanjú gbogbo ìjà tàbí aawọ̀ tí ó bá wáyé nínú ìtàn náà. Bí àpẹẹrẹ nínú eré-oníṣe *Ayégún* tí Àkàngbé kọ, gbogbo ìkọlura  àti ìkùnsínú tí àwọn ará ìlú *Ayégún* ní sí Gómìnà Kọ̀rọ̀lárí ló wá sópin ni ìgbà tí àwọn ará ìlú bínú pa Gómìnà àti àwọn oníjẹkújẹ olóṣèlú yòókù.

**(ii) Ìlànà àrògún ajẹ́mọ́nà**

Nínú ìlànà yìí, àhunpọ̀-ìtàn eré-oníṣe le má ba àrògún ojú ayé mu. Ọ̀nà àràmọ̀ndà ni àgbékalẹ̀ àhunpọ̀-ìtàn rẹ̀ yóò jẹ́. Bí àpẹẹrẹ nígbà tí òǹkọ̀wé eré-onítàn kan bá sọ̀rọ̀ nípa ikú akíkanjú kan kí ó tó sọ̀rọ̀ nípa ohun tí akíkanjú náà gbé ilé ayé ṣe, èyí kò bá àrògún ojú ayé mu rárá. Àpẹẹrẹ ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ni *Ṣàngó*. Òǹkọ̀wé kò to àhunpọ̀ ìtan rẹ̀ ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé ní ìbámu pẹ̀lú bí ó ṣe máa ń ṣẹlẹ̀ ní ojú ayé. Bí òǹkọ̀wé eré-oníṣe bá ṣe hun ìtàn rẹ̀ pọ̀ nínú eré máa ń sọ ìhà tí irú òǹkọ̀wé bẹ́ẹ̀ kọ sí kókó ọ̀rọ̀ tí eré-oníṣe náà dálé.

Oríṣiríṣi ni fọ́nrán ti àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá máa ń ṣàmúlò nínú àhunpọ̀-ìtàn wọn láti jẹ́ kí ó mú òǹkàwé lọ́kàn, tí yóò sì jẹ́ kí ìfẹ́ láti ka eré-onítàn náà títí dé òpin wà ní ọkan wọn. Àwọn fọ́nrán yìí ni ẹ̀dà-ọ̀rọ̀-ajẹméré-oníṣe, àwàdà, ìjọnilójú, àti ìkóláyàsókè.

**(b) Ẹ̀dà ọ̀rọ̀ ajẹmọ́ eré-oníṣe**

Èyí ni ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé eré-oníṣe máa ń lò láti mú kí ẹ̀dá-ìtàn kan sọ ọ̀rọ̀ kan tàbí kí ó gbé ìgbésẹ̀ kan láìmọ̀ pé yóò wá já sí ibi àti àbámọ̀ ní igbẹ̀yìn. Àpẹẹrẹ irú èyí hànde nínú *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ. Nínú eré yìí, Láwúwo ní ìyàwó kan, orúkọ ìyàwó náà ni Mọrẹ́nikẹ́. Ọwọ́ Morẹ́nikẹ́ ni Láwúwo tọ́jú owó àwọn òsìṣẹ́ sí, ó mú owó yìí ó fi ta tẹ́tẹ́ torí pé ó fẹ́ kí ayé rọrùn fún òun àti ọkọ rẹ̀, ṣùgbọ́n àbámọ̀ ló gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ rẹ̀, wọ́n lù ú ní jìbìtì, ó sì pa ra rẹ̀.

**(d) Àwàdà**

Èyí ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ apanilẹ́rìnín tí òǹkọ̀wé máa ń ṣàmúlò láti la àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ eré oníṣe rẹ̀ kí ó má baà sú òǹkàwé. Onírúurú àwọn àwàdà ni ó wà nínú àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bíi *O Ṣèyí Tán* ti Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé kọ.

**(e) Ìjọnilójú**

Ète yìí ni àwọn òǹkọ̀wé eré oníṣe àpilẹ̀kọ máa ń lò nígbà tí wọ́n bá fẹ́ jẹ́ kí ìrètí àwọn òǹkàwé yọrí sí ibi tí wọn kò fèrò sí. Ìjọnilójú máa ń wáyé nínú àwọn ìwé eré oníṣe àpilẹ̀kọ láti mú ìyàlẹ́nu ńlá bá àwọn òǹkàwé. Nínú eré-oníṣe *Agbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* tí J.F. Ọdúnjọ kọ, Aṣeremásìkà, ọkùnrin akúùṣẹ́ aṣẹ́gità, bí àpẹẹrẹ di Baálẹ̀ ìlú Jòǹtolo.

**(ẹ) Ìkóniláyàsókè**

Òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ máa ń ṣàmúlò ọgbọ́n yìí láti jẹ́ kí òǹkàwé ní ìfẹ́ láti mọ ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀dá ìtàn kan tàbí ohun kan ní ìgbẹ̀yìn. Ọgbọ́n yìí ni Adébáyọ̀ Fálétí ṣàmúlò nínú eré oníṣe *Baṣọ̀run Gáà*. Gbogbo òǹkàwé ni ó ń fẹ́ ka ìwé náà tán kí wọ́n le mọ ohun tí yóò gbẹ̀yìn ẹ̀dá-ìtàn tí a pè ní Baṣọ̀run Gáà nínú ìwé náà. Ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfunṣetán Aníwúrà* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ náà tún ṣàmúlò ète ìkónilàyásókè nínú ìwé náà. Gbogbo òǹkàwé ni ó ń dúró láti rí ìgbẹ̀yìn ẹ̀dá-ìtàn tí à ń pè ní Ẹfúnṣetán Aníwúrà.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Àhunpọ̀ ìtàn jẹ́ ètò ìṣẹ̀lẹ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ. Ẹ̀ka yìí ti fi yé wa pé kò pọn dandan kí ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bá àrògún ojú ayé mu. Nínú ẹ̀kọ́ yìí, náà ni a tún ti fi yé wa pé bí òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bá kùnà láti hun ìtàn rẹ̀ pọ̀ dáradára eré-oníṣe àpilẹ̀kọ bẹ́ẹ̀ yóò sọ ìgbádùn ajẹmẹ́wà rẹ̀ nù. A tún sọ di mímọ̀ pé, àhunpọ̀ ìtàn máa ń ní ìbẹ̀rẹ̀, ààrín àti ìparí. Ní ìparí, a fi yé wa pé, ẹ̀dà-ọ̀rọ̀-ajẹméré-oníṣe, àwàdà, ìjọnilójú, àti ìkóláyàsókè jẹ́ àwọn fọ́ńrán tí òǹkọ̀wé ń lò láti jẹ kí àhunpọ̀ ìtàn lè múná dóko.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kí ni àhunpọ̀ ìtàn?
2. Ipá wo ni àhunpọ̀ ìtàn máa n ní lórí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?
3. Ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé lórí àwọn fọ́ńnrán tí ònkọ̀wé máa n lò láti fi ẹwà kún àhunpọ̀ ìtàn rẹ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adébọ̀wálé, O. (1999) *Ọgbọ́n Òǹkọ̀wé Alátinúdá*. Lagos: The Capstone Publications.

__________ (1995) *O Ṣèyí Tán*. Àkúrẹ́: Montem Paperbacks.

Àkàngbé, A. (2007) *Ayégún*. Ìbàdàn: Straight Gate.

Ògúndèjì, P. A. (1992) *Yorùbá Drama I: Eré-oníṣe*. Ìbàdàn: Department of Adult Education, University of Ibadan.

**Ìpín Karùn-ún: Ẹ̀dá-ìtàn Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**


1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ẹ̀dá-ìtàn Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


**1.0 Ìfáárà**

Ohun tí a fẹ́ ṣe nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ẹ̀dá-ìtan nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. A ó sì tún ṣàlàyé àwọn ẹka méjì tí ẹ̀dá-ìtan pín sí nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- ṣàpèjúwe àwọn ẹ́dá-ìtàn nínú eré-oníṣe Yorùbá.
- ṣàlàyé ẹka méjì tí ẹ̀dá-ìtàn pín sí pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Kí ni àhunpọ̀-ìtàn?
2. Àwọn fọ́nrán wo ni òǹkọ̀wé ń lò láti fi ẹwà kún àhunpọ̀-ìtàn rẹ̀?
3. Dárúkọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn tí o ti bá pàdé nínú ìwé eré-oníṣe kan tí o ti kà rí.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ẹ̀dá-Ìtàn Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ, ẹ̀dá-ìtàn ni àwọn ẹ̀dá inú ìtàn. Ẹni tí nǹkan ṣẹlẹ̀ sí, ẹni tí a ṣe nǹkan sí tàbí tí ó ṣe nǹkan nínú eré. Nínú eré-oníṣe Yorùbá, òǹkọ̀wé ló máa ń ṣàmúlò ọgbọ́n àtinúdá láti dá aṣọ ìwà bọ ẹ̀dá-ìtàn lọ́rùn. Àwọn ẹ̀dá ìtàn tí òǹkọ̀wé sẹ̀dá yìí ni yóó dúró gẹ́gẹ́ bí ohun èlò ìpàrokò iṣẹ́ tí ó fẹ́ rán sí àwùjọ. Òǹkọ̀wé kò le ṣe ohun kan láìsí ẹ̀dá ìtàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ rẹ̀. Gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ni ó máa ń dá lérí àwọn ẹ̀dá-ìtàn. Àrà tí ó wu òǹkọ̀wé ni ó máa ń fi ẹ̀dá ìtàn dá torí pé wọn kò ní agbára tiwọn, àjọṣepọ̀ tí ó sì wà láàárín àwọn ẹ̀dá ìtàn ni ó ń fi ààyè sílẹ̀ fún onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtàn. Ẹnu àwọn ẹdá-ìtàn ni òǹkọ̀wé sì má a ń fi ọ̀rọ̀ sí lẹ́nu. Oríṣìí ẹ̀dá-ìtàn méjì ni ó wà:

(i) Olú ẹ̀dá-ìtàn

(ii) Amúgbalẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí àwọn ẹdá-ìtàn yòókù.

**(i) Olú ẹ̀dá-ìtàn**

Òpómúléró ni olú ẹ̀dá-ìtàn jẹ́. Gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tó bá wáyé nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ni ó máa ń dá lérí olú ẹ̀dá-ìtàn. Ṣùgbọ́n ṣá o, bí olú ẹ̀dá-ìtàn ṣe ṣe pàtàkì tó, igi rẹ̀ kò le dá igbó ṣe, ẹnìkan kìí jẹ́ àwádé, torí náà olú ẹ̀dá-ìtàn nìkan kò le nìkan ṣayé tàbí lògbà nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Nítorí náà, ó pọn dandan fún un láti ní olùrànlọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn.

Bí a ṣe ní olú ẹ̀dá-ìtàn aṣere bẹ́ẹ̀ náà ni a ní olú ẹ̀dá-ìtàn aṣebi. Olú ẹ̀dá-ìtàn aṣere ni àwọn olú ẹ̀dá ìtàn tí iṣẹ́ ọwọ́ wọn dára, tí wọ́n sì ń wá ìlọsíwájú àwùjọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ náà. Bí àpẹẹrẹ bí a bá wo eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Iná Ràn* tí Adéṣọlá Ọlátẹ́jú kọ, òǹkọ̀wé ṣàfihàn Anísẹ́ẹ́rẹ́ gẹ́gẹ́ bí olú ẹ̀dá-ìtàn aṣere, torí pé Anísẹ́ẹ́rẹ́ fẹ́ ìdàgbàsókè àwùjọ àti ìgbáyé-gbádùn mùtúmùwà, ó sì pinnu lọ́kàn rẹ̀ pé afi kí àwọn ja ìjàgbara kúrò lọ́wọ́ àwọn amúnisìn.

Olú ẹ̀dá-ìtàn aṣebi ni àwọn olú ẹ̀dá-ìtàn tó jẹ́ pé ìkà àti ìwà ìbàjẹ́ ni òǹkọ̀wé gbé wọ̀ wọ́n gẹ́gẹ́ bí ìwà. Ìwà ìmọtara-ẹni nìkan tàbí àwọn ìwà búburú mìíràn ni ó jẹ irúfẹ́ àwọn ẹ̀dá-ìtàn bẹ́ẹ̀ lógún. Àpẹẹrẹ èyí wà nínú ìwé *Iná Ràn* tí a ti mẹ́nu ba lẹ́ẹ̀kan. Ìwé eré-oníṣe náà ṣàfihàn Ajẹ́lẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi olú ẹ̀dá-ìtàn aṣebi torí pé ìwà ìgbáyé-gbádùn àwọn ènìyàn

àwùjọ kò jẹ ẹ́ lógún dípò èyí ìyà ni ó fi ń jẹ àwọn ará ìlú. Ó kọ̀ láti ṣe àwọn ohun tí ó tọ́ fún àwọn ará ìlú, ó fi àwọn ará ìlú sí inú ìyà àti ìbànújẹ́ bẹ́ẹ̀ sì ni wọn kò dẹ́kun owó orí ní gbígbà. A rí olú ẹ̀dá-ìtàn yìí gẹ́gẹ́ bíi aṣebi.

### (ii) Àwọn Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Olú Ẹ̀dá-Ìtàn

Àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá-ìtàn ni ó máa ń dúró gẹ́gẹ́ bí olùrànlọ́wọ́ fún olú ẹ̀dá-ìtàn láti mú kí iṣẹ́ rẹ̀ yọrí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò rí amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá-ìtàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá-ìtàn tí ó pọn dandan, ipa tí ó ṣe pàtàkì ni wọ́n ń kó nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Wọ́n le dá wàhálà sílẹ̀ fún olú ẹ̀dá-ìtàn, wàhálà yìí ni yóò mú kí ẹ̀mí eré tàbí àhunpọ̀-ìtàn gùn, wàhálà yìí náà sì ni olú ẹ̀dá-ìtàn yóò máa wá ojútùú sí nínú eré náà. Bí àpẹẹrẹ nínú ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀ko *Rẹ́rẹ́ Rún* láti ọwọ́ Ọládẹ̀jọ Òkédìjí, owó tí àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ fi ṣe ìrànlọ́wọ́ fún Láwúwo tó jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn lórí ẹjọ́ tí ó fẹ́ jẹ́ ni àwọn oníjíbìtì fi ète gba lọ́wọ́ ìyàwó rẹ̀ Mọ̀rẹ́nikẹ́, ní èyí tí ó sì dá wàhálà sílẹ̀. Wàhálà ọ̀hún ni ó mú Mọ̀rẹ́nikẹ́ pa ara rẹ̀ tí Láwúwo náà sì pàdánù iyè rẹ̀. Bí a bá wo eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí dáadáa, a ó rí i pé amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ni àwọn oníjíbìtì ẹ̀dá náà, ṣùgbọ́n wọ́n ṣe ohun tí ó lóòrìn nínú àhunpọ̀-ìtàn náà.

Bí a ṣe ní ẹ̀dá-ìtàn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ aṣere bẹ́ẹ̀ náà ni a ní amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ aṣebi. Àwọn ẹ̀dá-ìtàn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ aṣebi ni àwọn tí ó máa ń wá ìṣubú tàbí àṣìṣe olú ẹ̀dá-ìtàn, gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe rí àpẹẹrẹ rẹ̀ nínú *Rẹ́rẹ́ Rún*. Aṣebi ni àwọn ẹ̀dá-ìtàn oníjíbìtì tí wọ́n wá ìṣubú tàbí ìparun Láwúwo tí ó jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Ohun tí ẹ̀dá-ìtàn jẹ́ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ti hàn kedere sí akẹ́kọ̀ọ́ báyìí, a sì ti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ pé ọ̀nà méjì gbòógì ni ẹ̀dá-ìtàn pín sí, olú ẹ̀dá-ìtàn àti amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá-ìtàn. Ṣíwájú sí i, a tún fi yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pé àwọn ẹka méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí ẹ̀dá ìtàn pín sí yìí ni ó máa ń ní aṣebi àti aṣere, èyí ni pé bí a ṣe ní olú ẹ̀dá-itàn aṣe rere àti aṣebi, bẹ́ẹ̀ náà ni a ní amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá-ìtàn aṣe rere àti aṣe ibi.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

(1) Kí ni ẹ́dá-ìtàn jẹ́ nínú eré-oníṣe Yorùbá?

(2) Ṣàlàyé ẹka méjì tí ẹ̀dá-ìtàn pín sí kí o sì fi apẹẹrẹ láti inú ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ kan gbe àlàyé rẹ lẹ́ṣẹ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Òkédìjí, O. (1973) *Rẹ́rẹ́ Rún*. Ìbàdàn: Onibonje Press & Book Industries (Nig). Ltd.

Ọlátẹ́jú, A. (2009) *Iná Ràn.* Ìbàdàn. DB Martoy Books

**MÓDÙ KEJÌ**

**Ìpín Kìn-ín-ní: Ìfìwàwẹ̀dá Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**


1.0 Ìfààrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìfìwàwẹ̀dá Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


**Ìfáàrà**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kẹrin yìí, ìfìwàwẹ̀dá nínú eré-oníṣe Yorùbá ni a ó ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀. A ó sọ̀rọ̀ lórí ohun tí ìfìwàwèdá jẹ́, a ó sì jíròrò lórí àwọn ọ̀nà tí òǹkọ̀wé máa ń gbà láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Ní òpin ìdánilẹ̀kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le:

- jíròrò lórí ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́ nínú eré-oníṣe Yorùbá.
- dárúkọ irú àwọn ẹ̀dá-ìtàn tó máa n farahàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.
- ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ọ̀nà tí ònkọ̀wé eré-oníṣe lè gbà gbé àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ kalẹ̀.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lóri ìpínsísọ̀rí àwọn ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe Yorùbá.
2. Dárúkọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn tí o mọ̀ nínú eré-oníṣe Yorùbá àti irú ìwà tí wọ́n hù bóyá rere tàbí búburú.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìfìwàwẹ̀dá

Ìfìwàwẹ̀dá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé ń lò láti ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dá-ìtàn inú eré oníṣe àpilẹ̀kọ wọn, kí ó lè wà ní ìbámu pẹ̀lú tí ojú ayé, àti kí àwọn ẹ̀dá-ìtàn yìí le ní àwòmọ́ ẹ̀dá ènìyàn láwùjọ. Ìbáyému tí àwọn ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ máa ń ní ló jẹ́ kí àwọn òǹkàwé ó gbà wọ́n gbọ́.

Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá, àwọn òǹkọ̀wé máa ń lo ọgbọ́n àtinúdá wọn láti gbé ìwà tó wù wọ́n wọ ẹ̀dá-ìtàn, torí náà nígbà tí a bá sọ pé ìfìwàwẹ̀dá, ohun tí ó túmọ̀ sí ni pé “fífí ìwà wọ ẹ̀dá-ìtàn.” Torí pé òǹkọ̀wé ni ó ṣẹ̀dá àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú eré rẹ̀, fún ìdí èyí àrà tí ó wu òǹkọ̀wé ni ó le fi àwọn ẹ̀dá-ìtàn náà dá.

### 4.1.1 Gbígbé ẹ̀dá-ìtàn kalẹ̀

Òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ le lo onírúurú ọ̀nà láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú eré rẹ̀. Ṣíṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dá-ìtàn lè wáyé nípa lílo orúkọ, ìrísí, ìṣesí tàbí ìhùwàsí.

**(a) Orúkọ**

Níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ pé orúkọ ẹni ni ìjánu ẹni Yorùbá ní ìgbàgbọ́ kíkún nínú orúkọ, wọ́n sì gbà pé orúkọ máa ń ro ènìyàn torí náà orúkọ tí òǹkọ̀wé máa ń fún àwọn ẹ̀dá inú ìtàn wọn máa ń yàtọ̀. Orúkọ ẹ̀dá-ìtàn lè jẹ́ àmútọ̀runwá bíi Táyé, Kẹ́hìndé, Ìdòwú, Ìgè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bó bá sì wu òǹkọ̀wé ó le fún àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ ní orúkọ àbísọ bíi Gbémisọ́lá, Fúnmikẹ́, ó sì tún lè fún ẹ̀dá-ìtàn ní orúkọ oyè. Bí àpẹẹrẹ nínú ìwé Ọdúnjọ tí a pè ní *Agbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo*, òǹkọ̀wé sọ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ ní Akọgun tíí ṣe orúkọ oyè.

Síwájú síi, bí ó bá sì wu òǹkọ̀wé, ó le fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ní orúkọ tí ó lágbára tí ó sì ní ìtumọ̀ fún ìfìwàwẹ̀dá wọn. Bí àpẹẹrẹ nínú *Ayégún* tí Àkàngbé kọ, Fọláwẹwọ́ tí ó jẹ́ ìyàwó Gómìnà ìlú Ayégún ni ó fi ọlá wẹ ọwọ́ gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀. Bí ó ṣe wu Fọláwẹwọ́ ni ó ṣe ń ná owó àwọn ará ìlú. Àwọn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn tí orúkọ wọ́n níí ṣe pẹ̀lú ìfìwàwẹ̀dá wọn nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún* ni Àlùfáà Owónikókó, Olóyè Kòrọ́lárí Ọláwuwo àti Ọ̀mọ̀wé Babalajẹ́ Àjojẹ tí ó jẹ́ Máníjà Báǹkì.

Bí a bá tún wo inú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Iná Ràn* tí Adéṣọlá Ọlátẹ́jú kọ, Anísẹ́ẹ̀rẹ́ ni orúkọ ẹ̀dá-ìtàn mìíràn tí ó tún níí ṣe pẹ̀lú ìfìwàwẹ̀dá. Nínú eré-oníṣe yìí, Anísẹ́ẹ̀rẹ́ jẹ́ alágbára ẹ̀dá tí òògùn sì pọ̀ ní ọwọ́ rẹ̀. Ní àwùjọ Yorùbá, inú sẹ́ẹ̀rẹ́ ni àwọn babańlá wa máa ń ṣe òògùn lọ́jọ̀ sí. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé ìwà ẹ̀dá tí ó ní òògùn púpọ̀ lọ́wọ́ ni òǹkọ̀wé gbé wọ ẹ̀dá ìtàn yìí, èyí ló jẹ́ kí ó fún ní orúkọ "Anísẹ́ẹ̀rẹ́."

**(b) Ìrísí**

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ìrínisí ni ìṣenilọ́jọ̀, ìrí tí a rí ọmọ la ó ṣe àna rẹ̀. Òǹkọ̀wé máa ń fi ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ hàn nípa ìrísí nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà òǹkọ̀wé máa ń lo ẹ̀yà ara ẹ̀dá ìtàn láti ṣe àpèjúwe nípasẹ̀ àpèjúwe yìí ni òǹkàwé yóò ti mọ̀ bóyá arẹwà ẹ̀dá ni ẹ̀dá-ìtàn tàbí òbùrẹwà, bóyá ó sanra tàbí ó tínrín, ó kúrú tàbí ó ga.

**(d) Ìṣesí**

Èyí ni ìwà tàbí àṣà tí ó jẹ́ bárakú fún ẹ̀dá-ìtàn kan àmọ́ ṣá o, irú ìrísí yìí kìí sáábà nípa lórí ẹ̀dá-ìtàn. Ẹ̀dá-ìtàn kan lè jẹ́ aláwàdà, tí ó jẹ́ pé gbogbo nǹkan ni ó máa ń fi ṣe àwàdà tàbí yẹ̀yẹ́. Ẹ̀dá-ìtàn mìíràn sì le fẹ́ràn oúnjẹ púpọ̀. Torí náà onírúurú àbùdá ni òǹkọ̀wé lè lò láti ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dá ìtàn rẹ̀.

**(e) Ìhùwàsí**

Èyí náà ni kò yàtọ̀ púpọ̀ sí ìṣesí. Ìhùwàsí ẹ̀dá-ìtàn jẹ́ àwọn ìṣe ẹ̀dá-ìtàn kan tó máa ń nípa lórí àwọn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn. Ipa tí à ń sọ yìí lè jẹ́ èyí tí ó dára tàbí èyí tí kò dára. Àwọn ìhùwàsí náà lè jẹ́ ẹ̀tàn, irọ́, ìkà, ìfẹ́ tàbí oore ṣíṣe.

### 4.1.2 Àwọn ọ̀nà tí à ń gbà mọ orúkọ, ìṣesí àti ìrísí ẹ̀dá-ìtàn

Oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ni òǹkọ̀wé ń lò láti jẹ́ kí òǹkàwé mọ orúkọ, ìṣesí àti ìrísí ẹ̀dá-ìtàn wọn nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ.

**Ọ̀rọ̀ atọ́nisọ́nà**

Ọ̀rọ̀ atọ́nisọ́nà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà tí òǹkọ̀wé ń gbà láti jẹ́ kí òǹkàwé mọ orúkọ, ìṣesí àti ìrísí ẹ̀dá-ìtàn. Òǹkọ̀wé máa ń ṣàmúlò ọ̀rọ̀ atọ́nisọ́nà láti ṣàlàyé nípa àwọn ẹ̀dá-ìtàn àti àwọn ibùdó ìtàn tí ó wà nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ wọn.

Inú àkámọ́ ni òǹkọ̀wé máa ń fi àwọn ọ̀rọ̀ atọ́nisọ́nà wọ̀nyí sí ní gbogbo ibi tí ó bá ti ṣe àmúlò wọn. Fún àpẹẹrẹ, báyìí ni òǹkọ̀wé ṣe ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ ìtọ́nisọ́nà láti ṣe àpèjúwe Igbó Àìro èyí tí ó jẹ́ ọ̀kan lára ibùdó-ìtàn nínú eré onítàn *Agbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* tí Ọdúnjọ kọ.

> (Inú igbo kan tí ó ṣókùnkùn. Àwọn igi wẹ́wẹ́ wà káàkiri, igi nlá kan tí wọ́n fi aṣọ funfun wé sì wà ní ìparí igbó náà ní ọwọ ọ̀tún. Àyè díẹ̀ wà ní ẹ̀gbẹ̀ igi náà láti máa gba ẹ̀hìn rẹ̀ sọ̀ kalẹ̀ sí abẹ́ pẹpẹ kan bí ẹni pé wọ́n n gbá ìdí igi náà wọ inú ihà ilè kan lọ. Ère nlá tí ó dàbí jagunjagun dúró ní ẹ̀gbẹ̀ igi náà bi ẹni pé ó n sọ́ ọ. Aṣeere ni ó kọ́ wọlé, o n rìn kiri)
>
> (*Agbálọ́wọ́mérìí* o. i. 36).

**Ọ̀rọ̀ ẹnu ẹ̀dá-ìtàn**

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó máa ń jẹ́ pé ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé fi sí ẹnu ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ ni yóò jẹ́ kí á mọ orúkọ, ìṣesí àti ìrísí ẹ̀dá-ìtàn tí ó wà nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ rẹ̀. Àpẹẹrẹ èyí ni a lè rí fà jáde nínú ìwé *Iná Ràn*, níbi tí Dàání àti Làmídì ti ń ṣe fàájì lọ́dọ̀ Sìfáwù, ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé fi sí ẹnu ẹ̀dá-ìtàn tí a pè ní Làmídì fi Làmídì hàn gẹ́gẹ́ bí aláwàdà ẹ̀dá, ó jẹ́ kí á mọ orúkọ rẹ̀, àti ìṣesí rẹ̀ nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ náà.

Làmídì: Áà! À fi bẹ́ẹ̀!
Ijó yẹn ṣẹ̀ṣẹ̀ ń tọ̀mí lára ni ó ti ń wọ̀ mi ní akínyẹmí ara.
Èmi Làmídì jóníbi-ó-wù-ú
A-jó-níbi-ó wù ú ọkọ Kúdí
(Ọlátẹ́jú, 2009:18)

Nínú àpẹẹrẹ yìí ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé fi sí ẹnu ẹ̀dá-ìtàn ṣe àfihàn orúkọ ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ pẹ̀lú ìṣesí rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí aláwàdà tí inú rẹ̀ sì ń dùn ní gbogbo ìgbà.

Àpẹẹrẹ kejì tún ni a rí ní ojú ìwé kẹrìndínlógún

Fọ́yánmu: Èèmi! Èmi?
Èmi Fọ́yán-mu-kẹ́rù-ó-bẹ̀kọ

Pàgbín-jẹ-kẹ́rù-ó-bòòṣà
Owó ń bẹ lọ́wọ́ bí ẹdugbẹ
Wo àpò mi bó ti kún fọ́fọ́
(Ọlátẹ́jú, 2009:16)

Ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé fi sí ẹnu ẹ̀dá-ìtàn yìí jẹ́ kí òǹkàwé mọ orúkọ, ìṣesí àti ìrísí ẹ̀dá-ìtàn. Ẹ̀dá-ìtàn sọ orúkọ rẹ̀ fúnra rẹ̀, ó sì ṣe àfihàn ara rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ní àyà, tó sì lówó lọ́wọ́.

**Ọ̀rọ̀ tí ẹ̀dá-ìtàn mìíràn sọ nípa ẹ̀dá-ìtàn kan**

Ní ìgbà mìíràn, ọ̀rọ̀ tí ẹ̀dá-ìtàn kan sọ lè ṣe àfihàn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn tí wọ́n jọ ń takùrọ̀sọ nínú eré-oníṣe. Àpẹẹrẹ ọgbọ́n ìṣàfihàn orúkọ, ìṣesí àti ìrísí ẹ̀dá ìtàn báyìí wọ́pọ̀ nínú *Iná Ràn*.

Ògúndélé: Daani, ó mà tó ọjọ́ mẹ́ta?
Daani: Ó tó bẹ́ẹ̀. Mo ti lọ sí Ìbàdàn láti bí ọjọ́ mẹ́ta
Ògúndélé: Abájọ
Lamidi: Ìwọ ò tilẹ̀ gbé oko mọ́ ń tìrẹ. Máa lọ, máa bọ̀ bí ìlẹ̀kẹ̀ ìdí. Àbí ò ń rí nǹkan pọ́nlá ní Ìbàdàn ni; yáa fọwọ́ ọlá ran àwa náà o.
Fọ́yánmu: Kí lo fẹ́ kí Daani máa ṣe lóko? Èyí oko kò le ro. Ọ̀nà sì rè é, kò le yẹ̀. Èwo làbùrọ̀ jókòó lóko lásán?
Ògúndélé: Oko mélòó tiẹ̀ ni alákọ̀wé lè ro? Ẹ bu ẹmu fún Daani.
(Ọlátẹ́jú, 2009:17)

Bí a bá wo àpẹẹrẹ yìí fínní fínní, a ó rí i pé Ògúndélé tí ó kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ ni ó dárúkọ ẹ̀dá-ìtàn tí à ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ nínú àyọlò yìí. Lẹ́yìn èyí ni ẹ̀dá-ìtàn kejì tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Lamidi ṣe àfihàn ìṣesí rẹ̀ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé fi síi lẹ́nu "ìwọ ò tilẹ̀ gbé oko mọ́ ní tìrẹ. Máa lọ máa bọ̀ bí ìlẹ̀kẹ̀ ìdí." Ọ̀rọ̀ yìí ṣe àfihàn ìṣesí Daani gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ojú rẹ̀ kìí gbé ibìkan. Fọ́yánmu náà tún jẹ́ kí á ríi gẹ́gẹ́ bí ẹni tí kò le ṣe iṣẹ́ oko rárá tàbí ọ̀lẹ ènìyàn.

Gbogbo ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé fi sí ẹnu àwọn ẹ̀dá ìtàn yìí tún jẹ́ kí òǹkàwé ní òye ìrísí Daani gẹ́gẹ́ bíi alákọ̀wé ẹ̀dá nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Iná Ràn*.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ọgbọ́n àti ète tí òǹkọ̀wé eré-oníṣe máa ń lò láti gbé àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ kalẹ̀ ni ìfìwàwẹ̀dá. Oríṣi ẹ̀dá-ìtàn méjì ló wà. Olú ẹ̀dá-ìtàn àti amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá-ìtàn. Orúkọ, ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí ni òǹkọ̀wé eré-oníṣe máa ń lò láti gbé àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ kalẹ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lóri ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́ nínú eré onítàn Yorùbá.
2. Àwọn ẹ̀dá ìtàn wo ló máa ń farahàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?
3. Ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ọ̀nà tí ònkọ̀wé eré onítàn lè gbà gbé àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ kalẹ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Àkàngbé, A. (2007) *Ayégún*. Ìbàdàn: Straight Gate.

Ògúndèjì, P. A. (1992) *Yorùbá Drama I: Eré-oníṣe*. Ìbàdàn: Department of Adult Education, University of Ibadan.

Ọlátẹ́jú, A. (2009) *Iná Ràn.* Ìbàdàn. DB Martoy Books.

**Ìpín Kejì: Ìṣọ̀rọ̀ǹgbèṣì Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**


1.0 Ìfàárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìṣọ̀rọ̀ǹgbèsì Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 Ìfáàrà

Ohun tí a ó gbéyẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. A ó sọ ohun tí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì jẹ́ àti pàtàkì ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

## 2.0 Èròngbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- sọ ohun ti ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì jẹ́.
- ṣe àlàyé pàtàkì ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Àwọn ọ̀nà wo ni òǹkọ̀wé ń gbà ṣe ìfìwàwẹ̀dá àwọn ẹ̀dá-ìtàn wọn?
2. Ki ni ohun tí o mọ̀ nípa ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìṣọ̀rọ̀ǹgbèṣì Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì ni ìlànà tí a máa ń lò láti ṣe àkọsílẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. A ó kọ orúkọ ẹ̀dá-ìtàn tó sọ̀rọ̀, a ó sì tún kọ ọ̀rọ̀ tí ó sọ sí iwájú orúkọ rẹ̀.

Ìsọ̀rọ̀ngbèsì ṣe pàtàkì nínú ìgbékalẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá. Nínú ìsọ̀rọ̀ngbèsì láàárín àwọn ẹ̀dá-ìtàn méjì nínú eré ni a ti máa ń mọ iṣẹ́ ti òǹkọ̀wé fẹ jẹ́ kí ẹ̀dá ìtàn jẹ́, fún àwùjọ. Nígbà tí àwọn ẹ̀dá-ìtàn bá ń bá ara wọn sọ̀rọ̀, àrògún gbọ́dọ̀ wà nínú ìtakùrọ̀sọ wọn. Torí náà, òǹkọ̀wé gbọ́dọ̀ rii dájú pé òun ṣe ètò tó gún láti rii pé ọ̀rọ̀ tí ohun fi sí ẹnu ẹ̀dá-ìtàn kan ni ìtumọ̀, ó sì wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí àwọn ẹ̀dá-ìtàn yòókù ń sọ, kí ó le gbe òye iṣẹ́ tí òǹkọ̀wé fẹ́ jẹ́ fún àwùjọ jáde. Èyí ni wí pé ìṣewẹ́kú gbọ́dọ̀ wà nínú ìtakùrọ̀sọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn.

Nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ, òǹkọ̀wé ní àǹfààní láti ṣe àwílé ìṣẹ̀lẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe wà nínú ìtàn àròsọ ṣùgbọ́n ṣá o, òǹkọ̀wé yóò lo ọgbọ́n àtinúdá rẹ̀ láti fi sí ẹnu àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú eré, àwọn ẹ̀dá-ìtàn náà ni yóò sì gbé e jáde nínú ìsọ̀rọ̀ngbèsí wọn.

Àpẹẹrẹ ìsọ̀rọ̀ngbèsì yìí wá láti inú eré-onítàn *Ayégún* tí Adénìyí Àkàngbé kọ.

Lọlá: Káàsán Ṣọlá

Ṣọlá: Báwo ni Lọlá káàbọ̀. Ṣé dáradára ni gbogbo ilé wà?

Lọlá: A dúpẹ́. Ṣé o kò bínú pé ó pẹ́ mi díẹ̀?

Ṣọlá: N kò bínú púpọ̀ àmọ́ mo ti ń retí rẹ pẹ́ díẹ̀.
Ìgbà tí n kò rí ọ ni mo ní kí ń máa fìwé tí mo ń kà yìí pawọ́dà.

(*Ayégún* o.i. 59)

Bí àpẹẹrẹ ìsọ̀rọ̀ngbèsì tí ó wáyé láàrin Wòlíì Ámọ́sì àti Ìyá Rúùtù nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Afàgò Kẹ́yin Àparò* ní iṣẹ́ tí òǹkọ̀wé fi ń jẹ́ fún àwùjọ:

| | |
|---|---|
| Ìyá Rúùtù: | Ẹ káàárọ̀. |
| Wólíì Ámọ́sì: | Káàárọ̀ o. báwo ni? |
| Ìyá Rúùtù: | Dáadáa ni baba. Bẹ́ ẹ ti wí ló rí. Bí mo ti lo ọṣẹ tẹ́ ẹ fún mi ni ọwọ́ ti tẹ olórí burúkú rẹ̀. Àṣẹ tó wù mí ni mo ń pa fún un báyìí. |
| Wólíì Ámọ́sì: | O ti di ọkọ mọ́ ọn lọ́wọ́ nìyẹn. |
| Ìyá Rúùtù: | Òun nìyàwó báyìí èmi lọkọ. |
| Wólíì Ámọ́sì: | Ó dáa bẹ́ẹ̀ yẹn, àwa ó le ráyè ṣe tiwa. |

## 5.0 Ìsọnișókí

Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì ni ọ̀nà tí òǹkọ̀wé ń lò láti ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ọ̀rọ̀ tí àwọn ẹ̀dá-ìtàn ń sọ. Nínú ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì yìí ni iṣẹ́ tí òǹkọ̀wé fẹ́ jẹ́ fún àwùjọ ti máa ń hàndé. Àrògún gbọ́dọ̀ wà nínú ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì àwọn ẹ̀dá-ìtàn, èyí ni yóò jẹ́ kí o ní ìtumọ̀ sí àwọn òǹkàwé.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ki ni ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?
2. Ṣe àlàyé pàtàkì ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí


Adéjùmọ̀, A. (2010). *Àfàgo Kẹ́yin Àparò*. Ìbàdàn: Evergreen Publishers

Àkàngbé, C. A. (2007) *Ayégún*. Ìbàdàn: Cornerstone Communications.

**Ìpín Kẹta: Ibùdó-Ìtàn Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**

1.0 Ìfàárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ibùdó-Ìtàn Nínú Eré Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

**1.0 Ìfàárà**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ibùdó-ìtàn tí òǹkọ̀wé máa ń lò nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ wọn.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le:

- sọ ohun tí a ń pè ní ibùdó-ìtàn nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.
- ṣàlàyé ọ̀nà méjì tí ibùdó-ìtàn pín sí pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Kí ni o lérò pé ibùdó-ìtàn túmọ̀ sí?

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**


**4.1 Ibùdó-Ìtàn Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

Ibùdó-ìtàn ni ọgangan ibi tí ìṣẹ̀lẹ̀ gbé ṣẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé inú ìwé ni ibùdó eré-oníṣe àpilẹ̀kọ, òǹkọ̀wé a máa ṣàmúlò àwọn ibùdó lóríṣìíríṣi nínú àwọn ìwé wọn. Ọ̀nà méjì pàtó ni ibùdó-ìtàn pín sí. A ní ibùdó-ìtàn ojú ayé, a sì tún rí àwọn ibùdó-ìtàn mériìírí.

**Ibùdó ojú-ayé** – àwọn wọ̀nyí ni ibùdó tí kìí ṣe àjèjì sí ènìyàn, wọ́n jẹ́ ibùdó láàárín àwùjọ, ó lè jẹ́ inú ilé, ààrin ọjà, ilé ọba, inú igbó, ojú pópó, ilé ìgbafẹ́, odò, ìlú kan àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Ibùdó mériìírí** – àwọn ni ibùdó kàyéfì, àwọn ibùdó ayanilẹ́nu bíi, inú omi, ọ̀run, ojú sánmọ̀, inú afẹ́fẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Irú àwọn ibùdó mériìírí yìí ni ó wọ́pọ̀ jù lọ nínú àwọn ìwé ìtàn àrosọ Fágúnwà.

Ògúndèjì (1992) sọ̀rọ̀ nípa ibùdó, nínú ìwòye rẹ̀, òhun náà gbà pé ọ̀nà méjì ni ibùdó ìtàn pín sí. Òun fi yé wa pé, a ní ibùdó-ìtàn pàtó, a sì tún ní ibùdó-ìtàn gbogbogbòò. Nínú àlàyé rẹ̀, ó fi yé wa pé ibùdó ìtàn pàtó ni àwọn ọ̀gangan ibi tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré ti wáyé nínú àwùjọ ńlá-ńlá bí ìlú àti abúléko tí ìṣẹ̀lẹ̀ ìtàn ti ṣẹlẹ̀. Ò sọ pé òǹkọ̀wé kan lè gbé ìtàn rẹ̀ kalẹ̀ nílùú Ìbàdàn, èyí tí ó sì jẹ́ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn náà yóò wà káàkiri láàárín ìlú Ìbàdàn. Èyí túmọ̀ sí pé ibùdó ìtàn gbogbogbòò jẹ́ ìlú Ìbàdàn tí àwọn ibùdó-ìtàn pàtó sì le jẹ́ Fásitì Ìbàdàn, Òkè-Àdó, Kingsway, Àpáta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn wọ̀nyí sì lè wáyé nínú ilé, yàrá, ẹ̀yìnkùlé, ojú títì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ohun tí à ń ṣàlàyé ni pé agbègbè tí ìtàn dálé ni àwọn ibùdó-ìtàn, èyí sì máa ń fi òye yé àwọn òǹkọ̀wé sì ni. Ṣùgbọ́n bí a bá ṣe àkíyèsí ìpínsísọ̀rí Ògúndèjì (1992) yìí dáadáa, a ó rí i pé abẹ́ ìsọ̀rí kan ṣoṣo ni ìpínsísọ̀rí méjèèjì tí ó ṣàlàyé sí òkè yìí wà. Ìpínsísọ̀rí méjèèjì yìí ní a rí ní abẹ́ ìsọ̀ri ibùdó ojú-ayé torí pé ibùdó ojú-ayé ni àwọn méèèjì. Ṣùgbọ́n nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ibùdó mériìírí, àwọn wọ̀nyí kò bá ibùdó ojú-ayé mu rárá, ó máa ń jẹ́ ibùdó ìyanu, ibùdó kàyééfì tí a sọ àwọn àpẹẹrẹ wọn sí òkè. Torí náà, nípaṣẹ̀ àwọn ìṣọ̀ri tí a mẹ́nu bà lókè àti èyí tí Ògúndèjì (1992) sọ, a le ṣe àtúnpín àwọn ìsọ̀rí wọ́nyí nípaṣe ìṣàmúlò àtẹ ìsàlẹ̀ yìí.



## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti kọ́ nípa ohun tí à ń pè ní ibùdó nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ, a fi yé wa pé, ọ̀gangan ibi tí ìṣẹ̀lẹ̀ gbé sẹ̀ ni à ń pè ní ibùdó. A tún jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún wa pé ibùdó pín sí ọ̀nà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ (ibùdó ojú-ayé àti ibùdó mérìírí). Àlàyé tún wáyé lórí ojú tí Ògúndèjì (1992) fi wo ibùdó-ìtàn, ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé ibùdó-ìtàn méjì ni ó wà, ó pe àkọ́kọ́ ni ibùdó-ìtàn pàtó nígbà tí ó pe kejì ní ibùdó-ìtàn gbogbogbòò. Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a lo àwọn ìwòye méjèèjì yìí láti ṣe ìtúnpínsísọ̀rí ibùdó-ìtàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kí ni ibùdó-ìtàn nínú eré oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?
2. Ṣàlàyé ọ̀nà méjì tí ibùdó-ìtàn pín sí pẹ̀lú àpẹẹrẹ.
3. Nípa síṣàmúlò ìlànà Ògúndèjì (1992) ṣàlàyé ìpínsísọ̀rí ibùdó-ìtàn.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Àlàmú, O. O. (2014) Eré-Oníṣe Yorùbá. *Yorùbá Series* Volume III. Book Series for Nigerian Certificate in Education. A Publication of College of Education, Ikere-Ekiti, Ekiti State. (pp. 72 – 103).

Ògúndèjì, P. A. (1992) *Introduction to Yorùbá Written Literature*. External Studies Programme. Ibadan: University of Ibadan.

**Ìpín Kẹrin: Ìlò-Èdè Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**

1.0 Ìfàárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.o Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìlò-Èdè Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Ní abala ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti dánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìlò èdè àti bí òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ṣe ń ṣe àmúlò wọn nínú iṣẹ́ ọnà wọn.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ̀kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le:

- ṣalàyé ohun tí à ń pè ní ìlò-èdè.
- sọ ìyàtọ̀ tó wà láàárin ọnà-èdè àti àwọn èròjà alóhun Yorùbá.
- ṣe àfàyọ àwọn àpẹẹrẹ ọnà-èdè àti èròjà alóhun Yorùbá nínú àṣàyàn ìwé eré-oníṣe àpilẹ́kọ Yorùbá.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú


1. Ṣalàyé ohun tí o mọ̀ nípa ìlò-èdè.
2. Sọ ìyàtọ̀ tó wà láàárin ọnà-èdè àti àwọn èròjà alóhun Yorùbá.
3. Ṣe àfàyọ àwọn àpẹẹrẹ ọnà-èdè àti èròjà alóhun Yorùbá mẹ́wàá láti inú ìwé eré-oníṣe àpilẹ́kọ Yorùbá kan.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Ìlò-Èdè Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

Ìlò-èdè ni ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé ǹ lò láti fi gbé ọ̀rọ̀ kalẹ̀ ní ọ̀nà ìjìnlẹ̀ fún iṣẹ́ lítíréṣọ̀ aláwòmọ́, ní èyí tí yóó jẹ́ kó ní ẹwà bi o ṣe yẹ. Oríṣìíríṣìí ọgbọ́n àtinúdá ni òǹkọ̀wé máa n lo láti gbe ọ̀rọ̀ wọn kalẹ kí ó le lóòrìn ni èyí tí yóò si wuyì láti ka ni ìgbàkúùgbà tí a bá gbée. A tún le sọ pé ìlò-èdè ni ọ̀nà àrà fún iṣẹ́ lítíréṣọ̀ aláwòmọ́ ni ẹwà ti yóò mú ìpèdè dùn, ti yóò si dùn-ún gbọ.

Ọ̀nà méjì ni àwọn onímọ̀ pin ìlo-èdè sí. Wọ́n pe ọ̀kan ni ọnà-èdè nígbà tí ìkejì sì jẹ àwọn èròjà alohùn tàbí ewì àbáláyé gẹ́gẹ́ bi a ti ṣe fi hàn nínú àtẹ ìsàlẹ̀ yìí.




Àwọn àpẹẹrẹ abẹ isọri ọnà èdè ni; afiwe, ìbádọ́gba gbólóhùn, ajumọrin ọ̀rọ̀ àsọdùn/àpọ́npo, awitunwi, ìfohunpènìyàn, àfidípò, ìfìrómọ̀rísí, ìbéèrè pèsìjẹ, ìfọ̀rọ̀yàwòrán àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn àpẹẹrẹ tí ó jẹyọ ni abẹ́ ìsọ̀rí àwọn èròjà alohùn tàbí ewì àbáláyé ni òwe, orin, àkànlò èdè, oríkì, ọfọ, àlọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Àwítúnwí**

Àwítúnwí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọnà èdè nínú lítíréṣọ̀ tí òǹkọ̀wé máa ń lò láti ṣe ìtẹnumọ́ ohun kan. A máa ń lo àwítúnwí nínú lítíréṣọ̀ aláwòmọ́ nígbà tí a bá fẹ́ jẹ́ kí ọ̀rọ̀ yálà ẹyọ ọ̀rọ̀, awẹ́ gbólóhùn tàbí odidi gbólóhùn yé ènìyàn yékéyéké

Èyí lo jẹ́ kí Ọlátúnjí (1984:17) sọ nínú àlàyé rẹ̀ pé “One general feature of Yorùbá oral poetry is repetition. Repetition can be lexico-strucutre, lexical, or sentence. (Àwítúnwí ni èdè pàtàkì kan gbogi tí a fi ń dá ewì àtẹnudẹ́nu Yorúbà mọ̀. Ó le jẹ́ ẹyọ ọ̀rọ̀, ó sì tun le jẹ́ odidi gbólóhùn.

**Àjùmọ̀rìn Ọ̀rọ̀**

Èyí ni àwọn ọ̀rọ̀ ti wọn máa n kọ́wọ̀ọ́rìn papọ̀. Ibikibi tí akéwì ba ti lo ọkan, o di dandan kí o sàmúlò ìkejì rẹ.

**Ìfọ̀rọ̀dárà**

Ìfọ̀rọ̀dárà jẹ ọ̀kan lára àwọn àbùdá tí ń fún iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ Yorùbá ní ẹwà. Wọn a máa lo ìfọ̀rọ̀dárà láti jẹ́ kí iṣẹ́ ọnà ó dùn un kà, kí ó sì dùn ún gbọ́ létí. Olatunji (1984:37) sàlàyé báyìí pé, "Word-play is "the juxtaposition of lexical items which are somehow similar in shape, to produce an effect of verbal dexterity". Èyí túmọ̀ sí pé, (ìfọ̀rọ̀dárà ni kíkó àwọn ọ̀rọ̀ tí kò ní ìtumọ̀ kan náà pọ̀ sùgbọ̀n tí wọ́n fi ìrísí jọra lá fún wa ní òye). Nínú ewì tí a pè ní *Òkè Ìsòro Nàìjíríà,* a ri àwọn ọ̀rọ̀ tií wọ́n fi dárà,

**Ìfohunpènìyàn**

Ìfohunpènìyàn ni bíbá ohun tí kìí ṣe ẹlẹ́mìí sọ̀rọ̀ bí ẹni pé ẹlẹ́mìí ni. Olatunji (1984:49) fi yé wa pé, "it is a device whereby non-human beings are endowed with human feelings and attributes". Èyí ni pé, (ó jẹ́ ohun èlò láti gbé àbùbà ènìyaǹ wọ ohun tí kìí ṣe ènìyàn.)

**Àwọn Èròjà alóhun Tàbí Ewì Àbáláyé**

Àwọn èròjà àbáláyé jẹ́ ọkan lára ohun èlò pàtàkì tí òǹkọ̀wé ń lo láti mú ki àpilẹ̀kọ wọn dun-un ka. Ìwọ̀nyí ni ọ̀kan-ò-jọ̀kan èròjà àbáláyé ti wọ́n máa ń sàmúlò.

**Orin**

Orin ni lílò ìgbóhùn sókè-sódò tàbí ìwọ́hùn àti ìwéhùn láti gbé èrò inú ènìyàn jáde. Kò sí ohun tí ìran Yorùbá kò ní orin fún, èyi ló mú Ọlátúnjí (1984:) sọ pé, "There is no occasion in Yoruba life that is not accompanied with song." Tí ó túmọ̀ sí pé (kó sí ìgbà kan nínú ìgbé ayé Yorubá tí kò sí orin fún). Olúkòjú (1994:1) fi yé wa pé, ọmọ inú músíìkì Yorùbá ni orin jẹ́, a sí ń lò ó láti ṣàfìhàn èrò ọkan wa. Ó sí pín orin sí ìsọ̀rí mẹ́ta; orin àdákọ, orin àjùmọ̀kọ áti orin lílé àti gbígbè. Àwọ̀nyí òǹkọ̀wé erè-oníṣe àpilẹ̀kọ máa ń

lo orin ní ọ̀pọ̀ ìgbà láti ṣe ìtẹnumọ́ ohun kan. Orin jẹyọ nínú ìlò-èdè òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Afàgò Kẹ́yin Àparò*.

Oríṣìí méjì ni àwọn orin tí ó jẹyọ. Bí a ṣe rí orin ẹ̀sìn bẹ́ẹ̀ náà ni orin aláìjẹ́mẹ́sìn. Àpẹẹrẹ

Wòlíì: Máíkẹ́ẹ̀lì oluṣẹ́gun
Yára sọ̀ kalẹ̀ wá
Òní ni ìṣẹ́gun rẹ
Má ẹ dúró pé mọ (o.i. 31)

Wòlíì Ámọ́sì ló n kọrin ẹ̀sìn tí ó wà lókè yìí ní ilé ìjọsìn rẹ̀ kí ó tó bẹ̀rẹ̀ sí ní gbàdúrà. Bákan náà ni a tún rí àpẹẹrẹ orin ayẹyẹ:

Ọmọ ní ó sin ọ́
Bó o ti sin màmá rẹ o
Ọmọ ní ó sin ọ́
Bó o ti sin màmá rẹ̀ o (o.i. 39)

Orin òkè yìí jẹ́ orin àlùjó ti rẹ́kọ́ọ̀dù Ebenezer Obey tí àwọn ènìyàn jó sí ní ibi ayẹyẹ òkú màmá Túndé (ojú ìwé 40 àti 53).

**Òwe**

Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà kan tí kò fi ọ̀rọ̀ òwe ṣeré torí pé, òwe ni ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ ẹnu àwọn àgbà tí wọ́n ń lò láti wá ojútùú sí ọ̀rọ̀. A rí òwe láti inú àkójọpọ̀ òye ẹ̀dá àti ìbásepọ̀ ènìyàn. Níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ pé, nínú ìwòye ẹ̀dá ni òwe ti jáde, òǹkọ̀wé máa ń lo òwe láti fi ìdí ọ̀rọ̀ ọlọgbọ́ múlẹ̀, wọ́n sì tún lò ó láti fi dídángájíá wọn nínú èdè Yorùbá hàn. Àwọn Yorùbá a máa pa òwe pé òwe lẹsin ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ lẹsin òwe bí ọ̀rọ̀ bá sọ nù òwe la fi í wáa. Nínú ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Afàgò kẹ́yin àparò* òǹkọ̀wé ṣàmúlò òwe gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó gbọ́ èdè

Àpẹẹrẹ

(Bísí tó ń dákẹ́ láti àárọ̀ dá sí ọ̀rọ̀)

Bísí: *O rí ẹṣẹ̀ wèrè, o ò bù ú ṣoògùn, ọlọ́gbọ́n wo ni yóò gbé tiẹ̀ kalẹ̀.*
Bí mo jóbìnrin, èmi pàápàá ó sáà tẹ̀lẹ́ olówó lẹ́yìn.
Owó lóbìnrin kúkú mọ̀ (o.i. 2)

Nǹkan tí òwe ti Bísí pa túmọ̀ sí ni pé, owó tí àwọn ọmọbìnrin ń rîì gbà lọ́dọ̀ọ Adéagbo ni wọ́n ṣe ń pààrà ọ̀dọ̀ rẹ̀ torí kì í ṣe gbogbo ọkùnrin ló jẹ́ aláìgbọ̀n tí yóò máa ná ànádànù.

A tún rí àpẹẹrẹ òwe mìíràn nígbà tí Fẹ́mi àti àwọn lọ́gàálọ́gàá ń ṣe ìpàdé.

Fẹ́mi: Èmi ni mo ránsẹ́ pè yín.
*Bí ò bá sì nídìí obìnrin kì í jẹ́ kúmólú.*
Ọ̀rọ̀ ilé iṣẹ́ wa yìí ló ń fẹ́ àpérò. (o.i. 7)

Fẹ́mi tí ó jẹ́ ọ̀gá àgbà pátápátá fún ilé iṣẹ́ Tèmídire ló ránṣẹ́ pe àwọn ọ̀gá ẹkùn kọ̀ọ̀kan. Ìtúmọ̀ òwe tí ó pa ni pé ó ní ìdí pàtàkì tí òun ṣe ránṣẹ́ pè wọ́n.

**Ìsọníṣókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti kọ́ nípa ohun tí à ń pè ní ìlò èdè, a sì tún ti fi ye wa pé ọ̀nà méjì ni ìlò èdè pín sí, ohun náà sì ni ọnà èdè àti èròjà alóhun tàbí ewì àbáláyé. A kò sàì mẹ́nu ba àwọn àpẹẹrẹ lọ́kan-ò-jọ̀kan láti inú àwọn ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá bí i *Afàgò kẹ́yin àparò* àti àwọn mìíràn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé ohun tí o mọ̀ nípa ìlò-èdè.
2. Sọ ìyàtọ̀ tó wà láàárin ọnà-èdè àti àwọn èròjà alóhun Yorùbá.
3. Ṣe àfàyọ àwọn àpẹẹrẹ ọnà-èdè àti èròjà alóhun Yorùbá mẹ́wàá láti inú ìwé erè oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá kan.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adéjùmọ̀, A. (2010). *Àfàgo Kẹ́yin Àparò*. Ìbàdàn: Evergreen Publishers.

**Ìpín Karùn-ún: Ìpàrokò Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

**Àkóónú**


1.0 Ìfàárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìpàrokò Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


**1.0 Ìfàárà**

Òǹkọ̀wé kan ò lè ṣàgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà kan láìní iṣẹ́ tí ó fẹ́ jẹ́ fún àwùjọ. Èyí lè jẹ́ pé ó fẹ́ fi pe àkíyèsí àwọn èniyàn àwùjọ sí ìṣẹ̀lẹ̀ kan, kókó ọ̀rọ̀ kan, ohun tó yẹ láti ṣe, ojúṣe àwọn èniyàn àti gbogbo ohun yòówù tó lè mú àwùjọ tẹ̀síwájú. Nípa báyìí, oníṣẹ́ ọnà yóò fi iṣẹ́ rẹ̀ pàrokò ohun tí ó ní lọ́kàn ni.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò mọ:

- pàtàkì iṣẹ́ ọnà sí àwùjọ pàápàá iṣẹ́ tí òǹkọwé ń fi iṣẹ́ ọnà rẹ̀ jẹ́.

**4.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Kí ni o lérò pé ìpàrokò jẹmọ?

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Ìpàrokò Nínú Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

Òǹkọ̀wé kankan ò lè gbé iṣẹ́ ọnà kan kalẹ̀ kó kọjá àwùjọ. Ohun tó wà ní àwùjọ ni yóò fi pèlò ìtàn jáde láti fi jíṣẹ́ fún aráyé. Níbẹ̀ ni yóò ti rí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kàyééfì tàbí àwọn

ìwà búburú, èyí tí àwọn ènìyàn àwùjọ rẹ̀ ń hù, tí ó sì fẹ́ pàkíyèsí àwọn ènìyàn sí láti mú kí àtúnṣe wà. Irúfẹ́ ìwà yìí lè jẹ́ èyí tí ó lè kóbá ètò ọrọ̀ ajé ìlú, ìdílé, àjọ, iléeṣẹ́, ẹbí àti àwọn ohun yòówù tí ó lè fa ìpalára fún àwùjọ. Nípa báyìí, òǹkọ̀wé yóò wo ṣàkun irúfẹ́ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ yóò sì ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀ lọ́nà tí yóò mú òǹkàwé lọ́kàn gidi, èyí tí oníkálùkù ènìyàn yóò sì máa rí tirẹ̀ ṣà níbẹ̀ láti ṣe àtúnṣe tó tọ́.

Ní irúfẹ́ iṣẹ́ ọnà bẹ́ẹ̀ òǹkọ̀wé yóò ṣàfihàn irúfẹ́ ọṣẹ́ tí ẹni tó ń hu irú ìwà bẹ́ẹ̀ ń ṣe fún àwùjọ àti ní pàápàá ohun tó ṣẹlẹ̀ sí níkẹyìn èyí tó fẹ́ fi kọ́ ènìyàn lọ́gbọ́n. Látàrí èyí, ó ń fi iṣẹ́ rẹ̀ pàrokò fún àwùjọ ni. Bí àpẹẹrẹ, òǹkọ̀wé *Àgbà tí ń yọ́ ilẹ̀ dà* fi ìwé rẹ̀ pàrokò fún àwọn èèyàn tó ń hùwà, pàápàá ní kọ̀rọ̀, pé bó pẹ́ bó yá búburú a máa yọ́ wọn ṣe. Ó kàn le pẹ́ ni, ìkà yóò pa oníkà lọ́jọ́ kan. Òǹkọ̀wé ìwé eré oníṣe *Yéèpà! Ṣólààrín ń bọ̀* ń ṣàfihàn ìwà ìbàjẹ́ láàárín àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba àti irúfẹ́ ọṣẹ́ tí àwọn ìwà láaabi pé kò sí bí wọ́n ti lè gbọ́n tó ọwọ́ pálábá wọn yóò sì pàpà ṣégi lọ́jọ́ kan nítorí ọwọ́ yóò tẹ̀ wọ́n bó ti wù kó pẹ́ tó. Nínú *Àṣàkẹ́ Òréke*, òǹkọ̀wé fi ìwé rẹ̀ pàrokò fún àwọn ènìyàn, pàápàá àwọn obìnrin pé ìgbẹ̀yìn ni í dolókùú àdá àti pé bí ìdí bàjẹ́ tán ti onídìí náà ni yóò dì.

Pẹ̀lú gbogbo àwọn àpẹẹrẹ yìí, ó yé wa pé kò sí ìwé kan tó tayọ àwùjọ tó ti wá, èyí tí ó ń ṣàfihàn bí àwùjọ ti rí gan-an. Ìdí rè é tí wọ́n fi máa ń sọ pé bí ènìyàn bá fẹ́ mọ̀ nípa àwùjọ kan, kí ó ka àwọn lítíréṣọ̀ wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti jíròrò lórí bí iṣẹ́ ọnà kan ò lè ṣe tayọ àwùjọ tí òǹkọ̀wé ti wá. Fún ìdí èyí, ó ń fi iṣẹ́ rẹ̀ pàrokò ni fún àwùjọ rẹ̀ nípa bíbu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà ìbàjẹ́ àti gbígbóríyìn fún àwọn ìwà ọmọlúàbí.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ǹjẹ́ àjọṣepọ̀ kankan wà láàárín òǹkọ̀wé àti àwùjọ?
2. Ṣé lóòótọ́ ni pé bí a bá ti wo iṣẹ́ ọnà àwùjọ kan, a lè rí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ wọn nibẹ̀.
3. Báwo ni oníṣẹ́ ọnà ṣe ń pàrokò?
4. Òǹkọ̀wé kan ò lè kọ nǹkan tó kọjá àwùjọ rẹ̀ ṣé lóòótọ́ ni?

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Awóyẹlé, O. (1983) *Alàgbà Jeremáyà*. Ibadan: Onibọnoje Press & Book Industries (NIg.) Ltd.

Ọ̀ṣọ́fiṣan, F. (2010) *Yéèpà! Ṣólàárín ń bọ̀*. Ibadan: DB Martoy Books.

Owólabí, O. (1985) *Àgbà tí ń yọ ilẹ̀ dà*. Ibadan: Evans Brother Nigeria Publisher Ltd.

## MÓDÙ KẸTA

**Ìpín Kìn-ín-ní:** **Àgbéyẹ̀wò Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ**

**Àkóónú**

1.0 Ìfàárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ Ẹ*fúnṣetán Aníwúrà*
5.0 Ìsọnísókí Eré-Oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*
6.0 Ìsọníṣókí
7.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
8.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwé *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí ó jẹ́ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ni a ó máa ṣe àtúpalẹ̀ rẹ̀. Kókó, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò èdè ni àwọn ìjíròrò wa yóò dálé.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- ṣe ìsọníṣókí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*.
- jíròrò lórí àwọn kókó tí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* dálé.
- ṣàgbéyẹ̀wò ìfìwàwẹ̀dá Ẹfúnṣetán Aníwúrà àti Látòósà, àwọn kókó ẹ̀dá-ìtàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*
- ṣàlàyé àwọn ìlò-èdè inú ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kí ni ìtumọ̀ tí o lè fún kókó ìtàn inú eré-oníṣe Yorùbá?
2. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìfìwàwẹ̀dá àwọn ẹ̀dá-ìtàn méjì nínú eré-oníṣe tí o bá pàdé.
3. Níbo ni o lérò pé ibùdó-ìtàn gbogbogbòò nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* jẹ́?

## 4.1 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.0 Ìsọníṣókí Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*

Ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà jẹ́ eré-oníṣe ajẹmọ́-ìtàn gidi tí ó ṣẹlẹ̀ ní ìlú Ìbàdàn ní ìgbà ayé Ààrẹ Látòósà àti akíkanjú obìnrin Ẹfúnṣetán Aníwúrà tí ó jẹ́ Ìyálóde Ìbàdàn ní àkókò náà. Àfiwé eré-oníṣe yìí àti àkọsílẹ̀ tí a kà nípa ìtàn Ìbàdàn àti ìgbé ayé àwọn àkọ̀ní ẹ̀dá méjèèjì nínú ìwé *The History of the Yorùbá* tí Samuel Johnson kọ àti *Ìwé Ìtàn Ìbàdàn* láti ọwọ́ I. B. Akínyẹlé fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìtàn gidi ni Ìṣọ̀lá mú lò láti kọ eré náà. Ó yẹ kí ó di mímọ̀ fún akẹ́kọ̀ọ́ pé Ìṣọ̀lá ṣe àfikun tirẹ̀ sí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà lọ́nà àti jẹ́ kí ó muni lọkàn gidi. Bí àpẹẹrẹ nínú ìtàn náà tí ó wà nínú ìtàn Ìbàdàn, Ẹfúnṣetán Aníwúrà bímọ ṣùgbọ́n ọmọ náà kú lọ́jọ́ gan-an tí ó wáyé ni.

Nínú eré onítàn tí Akin Ìṣọ̀lá pè ní *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, Ẹfúnṣetán Aníwúrà kò bímọ rárá èyí sì ń ṣàfihàn láríjà ìwà ìkà Ẹfúnṣetán. Bákan náà nínú ìtàn Ẹfúnṣetán nínú ìwé ìtàn Ìbàdàn ọ̀kan nínú àwọn ẹrú rẹ̀ ló ṣekú pa á. Ṣùgbọ́n nínú eré eré-oníṣe tí Ìṣọ̀lá kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà fúnrarẹ̀ ló gbé májèlé jẹ. Gbogbo akitiyan àwọn ẹrú Ìyálóde Ẹfúnṣetán láti pa á pàbó ló já sí. Ó hàn gbangba pé Ìṣọ̀lá lo ọgbọ́n àtinúdá tirẹ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*.

Ẹfúnṣetán Aníwúrà tí ó jẹ́ Ìyálóde Ìbàdàn ní ìgbà kan rí jẹ ìkà àti ọ̀dájú ẹ̀dá nítorí àìbímọ rẹ̀. Onírúurú àrà tó wu ìyálóde ló ń fi àwọn ẹrú rẹ̀ dá láì sí ẹni tí yóò yẹ̀ ẹ́ lọ́wọ́ wò. Lára àwọn ìwà àìbìkítà Ẹfúnṣetán ló jẹ́ kí ó pàsẹ pé ki wọn lu Ògúnjìnmí akọ̀pẹ pa sí inú oko rẹ̀. Àwọn ìjòyè àti ará ìlú kò lè kojú Ìyálóde Ẹfúnṣetán lórí ikú Ògúnjìmí akọ̀pẹ ṣe ni gbogbo wọn n tẹnu bọlẹ̀ kiri lásán.

Ìtáwuyì, ọ̀kan nínú àwọn ẹrú ìyálóde, fún ẹrúbìnrin mìíràn lóyún èyí tí ó jẹ èèwọ̀ nínú ilé ìyálóde. Báyìí ni ẹlẹ́kọ ọ̀run bẹ̀rẹ̀ sí ní polówó. Gbogbo ọgbọ́n àlùmọ̀kọ́rọ́yí tí

àwọn ará ìlú àti ẹ̀gbọ́n ìyálóde lò láti yọ Adétutù nínú ọ̀fin ikú tó kó ara rẹ sì kò so èso rere. Gbogbo ẹ̀bẹ̀ àti ìsìpẹ̀ Akíngbadé kò jámọ́ nǹkan kan lójú ìyálóde Ẹfúnṣetán. Ikú oró ni Adétutù pàpà kú. Ìròyìn ikú Adétutù sì sọ ọjà di pẹ̀ẹ́-ǹ-túká. Ìròyìn ikú Adétutù ló mú Ààrẹ Látòósà àti àwọn ìlú pè fún àjọ tó ní ìrònú. Wọ́n sì fẹnukò pé kí wọ́n ránṣẹ́ si Ẹfúnṣetán pé kò fìlù sílẹ̀. Ìtáwuyi ran Àwẹ̀ró láti gbẹ̀mí Ìyálóde nípa fífi májèlé sínú oúnjẹ rẹ̀, ṣùgbọ́n àjẹ́sára ìyálóde pọ̀. Ìtáwuyi àti Àwẹ̀ró ló padà jẹ oúnjẹ májèlé náà. Lẹ́yìn tí ìyálóde kọ̀ láti fi ìlú sílẹ̀, Ààrẹ Látòósà àti àwọn ará ìlú kógun lọ bá ìyálóde wọ́n sì ségun rẹ̀. Ìyálóde di ẹni tó ń gbálẹ̀ níta Látòósà, ṣùgbọ́n ó ṣe bí akin ó sì gbé májèlé jẹ. Ìyálóde gbàgbọ́ pé ikú yá jẹ̀sín.

**Kókó**

Kókó méjì pàtàkì tí ó súyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà ni ìwà ìkà àti ìfẹ́.

**Ìwà ìkà**

Kári ibi gbogbo nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà ni ìwà ìkà ẹ̀dá-ìtàn tí ó ń jẹ́ Ẹfúnṣetán ti jẹyọ. Lákọ̀ọ́kọ́, ìlòkulò tí ó ń lo àwọn ẹrú rẹ̀ jẹ́ kí ó hàn gbangba pé aláìláàánú ẹ̀dá-ìtàn ni. Nítorí àìrọ́mọbi Ẹfúnṣetán ó sọ ọ́ di èèwọ̀ fún àwọn ẹrúbìnrin rẹ̀ láti lóyún. Ìwà ìkà Ẹfúnṣetán ló mú un rán Adétutù sọ́run àpàpàndodo toyún-toyún. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Akíngbadé àti Akínkúnlé bẹ Ìyálóde Ẹfúnṣetán pé kí ó dáríji Adétutù, inú Ẹfúnṣetán kò jẹ́ kí ó gbọ́ ìpẹ̀ àwọn ọmọ ìyá rẹ̀. Agbára, ọlá, òògùn àti ipò tí ìyálóde Ẹfúnṣetán ní ru bò ó lójú, kò bìkítà fún ẹnikẹ́ni. Bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀mí ènìyàn kò jẹ́ nǹkan kan lójú rẹ̀. Àwọn ẹ̀dá-ìtàn mẹ́rin àti oyún inú ni Ẹfúnṣetán dá ẹ̀mí wọn légbodò nínú eré-onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà.* Èyí sì n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé dájúdájú òṣìkà àti aburú ẹ̀dá-ìtàn ni Ẹfúnṣetán. Bí bàtá bá ti ń ró lárọ̀ọ́jù ó sẹ́tán tó fẹ́ ya ni, Ààrẹ Látòósà àti àwọn ará ìlú ṣígun lọ ilé Ìyálóde. Idà ahun ní í pahun, màjèlé ti ìyálóde Ẹfúnṣetán fi máa ń pa àwọn ẹrú rẹ̀ náà ló fi pa ara rẹ̀. Ó hàn kedere nínú eré-oníṣe náà pé ìwà rere ló dára, ìkà kò lérè

**Ìfẹ́**

Òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* jẹ́ kí òǹkàwé rẹ̀ mọ̀ pe ọ̀rọ̀ ìfẹ́ lágbára, ìfẹ́ ṣe pàtàkì. Ìfẹ́ láàrin olólùfẹ́ méjì kò se é pa mọ́ra. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹrú ni Ìtàwuyì àti Adétutu nínú ilé ìyálóde tí wọn sì n jẹ ìyà àjẹkúdórógbó, síbẹ̀ àwọn méjèèjì fi ìfẹ́ hàn sí ara wọn. Ọfà ìfẹ́ tí ó ti wọlé sára Ìtáwuyì àti Adétutu ni kò jẹ́ kí wọ́n bìkítà nípa èèwọ̀ tí Ìyálóde Ẹfúnṣetán fún àwọn ẹrúbìnrin rẹ̀ pé wọ́n kò gbọdọ̀ lóyún. Adétutù lóyún, ó sì kù. Ìfẹ́ ti Ìtáwuyì ní sí Adétutù ló mú un pinnu láti gbẹ̀san ikú Adétutù lára Ẹfúnṣetán, ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé Ìyálóde ló rẹ́yìn Ìtáwuyì àti ẹni tí ó bẹ̀ nísẹ́, Ìgbéṣẹ̀ Adétutù àti Ìtáwuyì jẹ́ kí ó hàn pé kò sí ohun tí ìfẹ́ kò lè ti ènìyàn ṣe.

**Àhunpọ̀-Ìtàn**

Ewì ni ònkọ̀wé fi pàjùbà tí ó sì tún fi bẹ̀rẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà. Nínú rẹ̀ ló ti jẹ́ kí òǹkàwé mọ ohun tí wọn yóò bá pàdé nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ náà. Inú ìran méjìlá ni Ìṣọ̀lá pín eré onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* sí. Nínú ìran kìnní ni a ti ri àwọn ẹrú Ìyálóde tí wọ́n n ṣe iṣẹ́ àṣekúdórógbó láìní ìsinmi. Àwọn ẹrú Ìyálóde gbàgbọ́ pé ìkà àti ọ̀dájú ènìyàn ni Ìyálóde àti pé ìyà tó fi ń jẹ wọ́n kò ṣẹ́ lẹ̀yìn àìrọ́mọbí rẹ̀. Ṣé ẹni tí kò bí rú ẹni, kò lè fẹ́ràn ẹni.

Ní ìran kejì Akínkúnlé àbúrò Ìyálóde Ẹfúnṣetán wà dágbére fún un wí pé òun ń lọ Òkè-Ẹgàn láti lọ̀ wo Délé ọmọ òun ti ara rẹ̀ kò yá, ṣùgbọ́n Ìyálóde sọ ọ̀rọ̀ kòbákùngbé sí àbúrò rẹ̀. Ìran yìí ni a ti gbọ́ lẹ́nu Ìyálóde pé nì ìgbà tí òun kò bímọ, ẹrú òun kankan tó bá lòyún ọ̀run alákeji ni yóò ti bíì. Àtipé ànàjátí ni òun yóò na ẹrúbìnrin òun tó bá fẹ́ ìyàwó. Àjílé, ọ̀rẹ́ kan ṣoṣo tí ìyálóde ni bẹ̀ ẹ́ wò bákan náà nínú ìran kejì yìí.

Nínú ìran kẹta ni wọ́n ti mú ìròyìn wá bá Ààrẹ Látòósà àti àwọn ìjòyè rẹ̀ láàfin pé àwọn ẹrú Ìyálóde ti pa Ògúnjìmí akọ̀pẹ. Látòósà sì ní kí àwọn wádìí ọ̀rọ̀ náà síwájú síi. Ìran kẹrin ni ó ti hàn gbangba pé ọ̀rọ̀ ìfẹ́ wà láàrin Ìtáwuyì àti Adétutu. Ìtáwuyì sọ àlá tí ó lá fún Adétutù olólùfẹ́ rẹ̀, Adétutù sì jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún Ìtáwuyì pé abàmì ẹyẹ ni Àkàlàmàgbò jẹ́. Àwẹ̀ro ọ̀kan lára àwọn ẹrúbìnrin ṣàkíyèsí pé ó dàbí ẹni pé Adétutù fẹrakù ṣùgbọ́n Adétutù tutọ́ sókè ó sì fojú gbà á. Ìtáwuyì àti Àkànó jà nítorí àwọn ẹrúbìnrin, Ìtáwuyì sì fi ẹ̀yìn Àkànó balẹ̀.

Ní ìran karùn-ún, Àwẹ̀ró fi to Ìtáwuyì létí pé Adétutu ti fẹ́rakù, èyí sì fa ìjayà ńlá fún Ìtáwuyì. Ní ibí yìí ni Akínkúnlé àbúrò Akíngbadé ti bẹ́ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ láti dá sí ọ̀rọ̀ Adétutù ki ọ̀rọ̀ oyún tí ó ní má ba à já sí ikú. Ní ìran keje Ìyálóde Ẹfúnṣetán pe àwọn ẹrú rẹ̀ jọ, ó jẹ́ ki Adétutù mọ̀ pé àṣírí oyún tí ó ní ti tú sí òun lọ́wọ́ àti pé oorun ìkẹyin tí Adétutu yóò sùn ní ilé òun ni ti alẹ́ ọjọ́ náà. Ọ̀súntúndé ni Ìyálóde rán sí abẹ́nilórí. Ìbànújẹ́ dorí gbogbo àwọn ẹrú kodò. Akíngbadé, ẹ̀gbọ́n Ìyálóde àti àwọn àgbàgbà ìlú lọ sí ilé Ìyálóde nínú ìran kẹjọ, láti bẹ̀bẹ̀ pé kí ó foríjin Adétutù torí àbúrò rẹ̀ Akínkúnlé ló fún un lóyún. Ìyálóde fàbùkù kan àwọn àgbàágbà, ó sì fi yé àwọn àgbàágbà náà pé lórí ọ̀rọ̀ Adétutù, aṣọ kò bá ọmọ́yẹ mọ́, ọmọ́yẹ ti rin ìhòhò wọjà.

Nínú ìran kẹsàn-án, obìnrin kan ròyìn ikú Adétutù láàrin ọjà. Ìròyìn yìí sì ba àwọn ènìyàn lọ́kàn jẹ́ débi pé ọjà túká. Ní ìran kẹwàá, àwọn ìlú ṣe ìpàdé lórí ìwà ìkà Ìyálóde tó ń fi ojoojúmọ́ pọ̀ si. Gbogbo ìlú sì panupọ̀ ránṣẹ́ sí Ìyálóde Ẹfúnṣetán pé kí ó fi ìlú sílẹ̀. Ìran kọkànlá ni oníṣẹ́ ti ààrẹ Látòósà rán ti wá jíṣẹ́ fún Ìyálóde pé kí ó fi ìlú sílẹ̀, ṣùgbọ́n oníṣẹ́ náà ni Ìyálóde sọ di ọ̀kan lára àwọn ẹrú rẹ̀. Ìtáwuyì àti Àwẹ̀rò gbìyànjú láti pa Ìyálóde Ẹfúnṣetán nípa fífún un ní májèlé jẹ. Ṣùgbọ́n ẹ̀mí àwọn méjèèjì ló bá ìṣẹ̀lẹ̀ náà rìn. Àjílé, ọ̀rẹ́ ìyálóde ṣòfófó fún un pé àwọn ìlú ń bọ̀ wá jẹ ilé rẹ̀ run, pé kí ó sá kúrò ní ìlú, ṣùgbọ́n Ìyálóde sọ pé òun kò ní ibì kankan sálọ torí Aláńgbá tó bá wọ ihò akan, ẹ̀yìn ni yóò fi rìn padà. Látòósà àti àwọn ìlú kógun wá bá ìyálóde Ẹfúnṣetán wọn sì bori rẹ̀ wọ́n fi okùn dè é lọ́wọ́. Ìran kejìlá ni ó jẹ́ òpin àhunpọ̀ ìtàn eré onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Ẹfúnṣetán di ẹni tó ń gbálẹ̀ ní ìta Látòósà ìbànújẹ́ sì borí ọkàn rẹ̀. Ìyálóde Ẹfúnṣetán ṣe ọkàn akin ó gbé májèlé jẹ, ó sì kú. Bó o láyà o ṣìkà, bó o rántí ikú Ẹfúnṣetán, o ṣe rere.

**Ibùdó-Ìtàn**

Ibùdó ojú ayé ni òǹkọ̀wé ṣàmúlò nínú ìwé eré-oníṣe náà. Ìlú ìbàdàn, ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, ni ibùdó gbogbogbòò. Àwọn àdúgbò bí i Orítamẹ́rin àti Bẹẹrẹ tí wọ́n tún dárúkọ tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ sí i pe ìlú Ìbàdàn ni ìtàn náà ti wáyé. Àwọn ibùdó ìtàn pàtó nínú eré onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* ni Ilé Ìyálóde, Ààfin Látòósà, oko Ìyálóde Ẹfúnṣetán, ilé Akíngbadé àti ojú ọjà.

**Ìfiwàwẹ̀dá**

Ní ìpele yìí, àwọn ẹ̀dá-ìtàn tí a ó máa sọ̀rọ̀ nípa ìfìwàwẹ̀dá wọn ni Ìyálóde Ẹfúnṣetán, Ààrẹ Látòósà, Ìtáwuyì, Adétutù, Àwẹ̀rò àti Akíngbadé.

**Ìyálóde**

Ẹfúnṣetán Aníwúrà ni olú ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Ìyálóde Ìbàdàn tún ni Ẹfúnṣetán jẹ́. Ọlọlá àti alágbára ẹ̀dá-ìtàn ni Ẹfúnṣetán, èyí ló sì máa ń gùn ún ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà. Ìlòkulò ni Ẹfúnṣetán máa ńlo àwọn ẹrú rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni ó sì tún máa ń fi ìyà àjẹkúdórógbó jẹ wọ́n. Bí adìyẹ ni Ẹfúnṣetán ṣe máa ń pa àwọn ẹrúbìnrin rẹ̀ tó bá lóyún èyí sì fi hàn gẹ́gẹ́ bí ìkà àti òdóró ẹ̀dá. Àìbímọ Ẹfúnṣetán tún ṣe okùnfà ìwà ìkà rẹ̀. Gbogbo ẹ̀bẹ̀ Akíngbade àti àwọn àgbà ìlú láti jẹ́ kí ìyálóde Ẹfúnṣetán dárijì Adétutù kò tu irun kankan lára rẹ̀ ó pàpà pa Adétutù toyún-toyún ni. Ìyálóde Ẹfúnṣetán jẹ́ ẹ̀dá-ìtàn tí gbogbo ìlú bẹ̀rù wọn kì í súnmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀. Bí ìyálóde ṣe burú tó yìí, ó ní ọ̀rẹ́ kan tí orúkọ rẹ̀ ńjẹ Àjílé, òun ló sì ta ìyálóde lólobó pé àwọn ìlú ń bọ̀ wá jẹ ilé rẹ run. Àrokò tí òǹkọ̀wé fi èyí pa ni pé kò sí bí ènìyàn ṣe lè burú tó tí kò ní ní ọlọ́rọ̀ tirẹ̀. Ní ìgbà tí òsùnwọ̀n Ẹfúnṣetán kún àkúnwọ́sílẹ̀, Ààrẹ̀ Látòósà àti àwọn ará ìlú kógun wá bá a wọ́n sì borí rẹ̀. Láti lè bo ara rẹ̀ ní àṣírí Ẹfúnṣetán gbé màjèlé jẹ́. Ikú ẹ̀sín ni Ẹfúnṣetán kú.

**Ààrẹ Látòósà**

Látòósà ni ààrẹ àti olórí ní ìlú Ìbàdàn ní àkókò kàn náà ti Ẹfúnṣetán jẹ́ ìyálóde Ìbàdàn. Alágbára àti akíkanju ẹ̀dá-ìtàn ni Látòósà. Látòósà kò kọ́kọ́ fi ọwọ́ tó nípọn mú ọ̀rọ̀ ìyálóde Ẹfúnṣetán ṣùgbọ́n ní ìgbà tí Ẹfúnṣetán sún un kan ògiri ó pajúdà sí Ìyálóde Ẹfúnṣetán. Ó fì ìwà akin àti akíkanju rẹ hàn báyìí ni ó sì borí ìyàlóde Ẹfúnṣetán tí ó si fì ìdándè fún àwọn ẹrú Ẹfúnṣetán. Onígboyà àti akin ẹ̀dá-ìtàn ni ààrẹ Làtòósà.

**Ìtáwuyì**

Ọ̀kan lára àwọn ẹrú Ìyálóde Ẹfúnṣetán ni Ìtáwuyì. Olólùfẹ́ Adétutù ọ̀kan lára àwọn ẹrúbìnrin sì ní Ìtáwuyì pẹ̀lú. Ìfẹ́ àìsẹ̀tàn ni Ìtáwuyì ní sí Adétutù.

Gbogbo ọ̀nà ni Ìtáwuyì wá láti kó Adétutù yọ nínú ọ̀fìn ikú ìyálóde. Lẹ́yìn ikú Adétutu nítorí ìfẹ́ tòótọ́ tí Ìtáwuyì ní sí Adétutù, ó jà kìtìkìtì láti gbẹ̀san lára Ìyálóde Ẹfúnṣetán ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé Ìtáwuyì pàápàá sọ ẹ̀mí rẹ̀ nù.

**Adétutù**

Ẹrúbìnrin ìyálóde Ẹfúnṣetán ni Adétutù. Ó jẹ́ arẹwà obìnrin èyí ló sì sọ ọ́ di àrímáleèlọ fún àwọn ẹrúkùnrin àti àbúrò ìyálóde, Akínkúnlé. Adétutù fẹ́ràn Ìtáwuyì wọ́n sì di olólùfẹ́ ara wọn. Ọfà ìfẹ́ tó wọlé sí ara àwọn olólùfẹ́ méjèèjì yìí ló jẹ́ kí wọ́n rú òfin ìyálóde tí Adétutù sì lóyún. Ìwà tí òǹkọ̀wé gbé wọ àwọn ẹ̀dá yìí ló lò láti fihàn pé kò sí ipò tí ènìyàn le wà tó le tẹ bí Ọlọ́run ṣe da àwa ẹ̀dá ri. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹrú ni wọn, èyí ko di wọn lọ́wọ́ láti fi ìfẹ́ wọn hàn lọ̀nà tí tẹrú tọmọ ń gba ṣe é. Ikú oró ni Adétutù kú torí Ìyálóde pé abẹ́nilórí láti pa á ní ìta gbangba.

**Ìlò-Èdè**

Lára àwọn ìlò-èdè tí ònkọ̀wé ṣàmúlò ni àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àkànlò èdè, òwe, orin, oríkì àti ọfọ̀.

**Àfiwé Tààrà**

A rí àpẹẹrẹ àfiwé tààrà ní ìgbà tí Adétutù n ba Àwẹ̀rò sọ̀rọ̀ lágbàlá ìyálóde.

Adétutù: Dákun bá mi gbómi ọ̀dọ̀ rẹ un.
Ata yìí gbẹ púpọ̀, ó ṣòro ó lọ̀.
Bẹ́ẹ̀ sì ni <u>kò gbọdọ̀ má kúnná bí eti</u>. (o.i.1)

Ata tí Adétutù ń lọ̀ gbọdọ̀ kúnná bí etí. Àfiwé yìí lọ tààrà. Ata náà gbọ́dọ̀ fẹ́lẹ́ bí etí ṣe fẹ́lẹ́.

Ìyálódé: …gbogbo ẹrú tí mo ba fowo mi rà, ó dájú, wọn kò kuku gbọdọ̀ bímọ.
Èyí tí ò bá lóyún nínú àwọn omidan ọ̀run alákeji ni yóò ti bîì.

Ẹrúkùnrin mi tí ò bá sì fẹ́ ìyàwó <u>ànàbẹ́rí ni bí ajá ògun</u>, ṣogún! Bẹ̀ẹ̀ ni (o.i.9)

Òǹkọ̀wé fi orí bíbẹ́ ẹrú wé bí àwọn ọdẹ ṣe ń bẹ́ orí ajá tí wọ́n bá ń bọ Ògún.

**Àfiwé Ẹlélọ̀ọ́**

Òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ náà tún lo àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ láti gbé ẹwà eré onítàn náà jáde. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ kò lọ tààrà bí i ẹlẹ́lọ̀ọ́. Ṣùgbọ́n bákan náà ni à ń fi àwọn ohun tó jọra wé ara wọn.

Ọ̀ṣúntúndé: …ohun tí yóò lé ni nílé ẹni. Èdùmàrè má fi ṣàdánwò ẹni. Ṣé èmi náà ni <u>mo dewúrẹ́ à ń so mọ́lẹ̀ yìí</u>?
Èmi ni <u>mo dàgùntàn olókùn lọ́rùn</u>? (o.i 6)

Ọ̀súntúndé, ọ̀kan lára àwọn ẹrúkùnrin ìyálóde Ẹfúnṣetán ló fi ìyà tí ìyálóde fi ń jẹ ẹ́ we ìyà tí ó ń jẹ ewúrẹ́ àti àgùntàn.

**Òwe**

Ìṣàmúlò òwe pọ̀ nínú eré eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà.

Ìyálóde: Kí ni ẹ fi mí pè? Èmi Ẹfúnṣetán Aníwúrà! Bí irungbọ̀n alágbàṣe gùn tó apá. Ẹni tí ó gbóko fún un lọ̀gá rẹ̀
(o.i. 5)

Ìyálóde Ẹfúnṣetán ló pa òwe òkè yìí láti ṣọ fún àwọn ẹrú rl pé òun lágbára lórí wọn

**Orin**

Oríṣìíríṣìí orin ni wọ́n lò nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà. Bí a ṣe rí orin ìdárayà bẹ́ẹ̀ ni orin òwe kò gbẹ́yìn. Fún àpẹẹrẹ àwọn ọ̀kanòjọ̀kan orin yìí wo ojú ìwé 25, 27, 39, 40, 70, 71, 72, 74.

**Oríkì**

Oríkì bọ̀rọ̀kìnní, oríkì orílẹ̀, oríkì ẹran àti oríkì ìlú ló hànde nínú eré onítàn Ẹfúnṣetán Aníwúrà. Fún àpẹẹrẹ oríkì ìṣàlẹ̀ yìí jẹ́ oríkì ìlú Ìbàdàn.

> Ìbàdàn ọmọ -ajòro-sùn
> Ọmọ a-jẹ-gbín-yó
> Ọmọ a-fi-kárawun-fọ́-ri-mu… (o.i. 13)

wo ojú ìwé 12, 34, 53, 54, 77 fún àwọn oríkì mìíràn.

**Ọfọ̀**

Ọ̀kan lára eròjà alóhun Yorùbá ni ọfọ̀ jẹ́ . Òǹkọ̀wè ṣe àmúlò ọfọ̀ láti ṣe àfihàn olú ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọnibìnrin.

Ìtáwuyì: Ìyá iná mọ́ ọ!
Wòkè kí o wolẹ̀.
O dán an tán lónìí.

Ìyálóde: Dúro níbẹ̀, àgbéró ni ikún gbọ́wọ́.
A-rù-másò ni sigidi ń rú igbá ọṣẹ
A kì í síwọ́ lu imi,
A kì í fèsù jókòó.
A-fọ́po kì í rọ́wọ́ họrí,
A-rí-ta-gìrì ni tejò
Bíná bá romi, a gbàgbé ilé fẹ́ jo
Bẹ́tù bá romi, a gbàgbé ariwo tó fẹ́ pa
Mú àdá ọwọ́ rẹ wa! (Ìtáwuyì fún un ládàá)
Amẹmu kì í bọ́tí rojọ́.

A rí i pè Ìtáwuyì ko ba Ẹfúnṣeta jiyàn. Ohun ti òǹkọ̀wé ń lo ọfọ̀ yìí fún ni ṣíṣe àfihàn agbára tó wà nínú ọfọ̀ láwùjọ Yorùbá.

**5.0 Ìsọníṣókí**

Ìwà ìkà àti ìfẹ́ ni àwọn kókó méjì ti eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* dálé. Ewì ni òǹkọ̀wé fi pàjùbà tí ó sì tún fi kádìí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí. Ìlú Ìbàdàn ni ibùdó ìtàn

gbogbogbòò eré onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Àwọn ìlò èdè tó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* ni àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àkànlò èdè, òwe, orin àti oríkì.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé kíkún lórí àwọn kókó ti eré onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* dálé.
2. Ṣàgbéyẹ̀wò ìfìwàwẹ̀dá Ẹfúnṣetán Aníwúrà àti Látòósà nínú eré-onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*.
3. Ibo ni ibùdó-ìtàn gbogbogbòò eré-onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*?
4. Ọ̀nà wo ni Ìṣọ̀lá gbà lo ọnà èdè nínú eré-onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*?

   Wá àwọn àpẹẹrẹ mìíràn tó jẹ mọ́ àwọn ọnà-èdè tí a mẹ́nu bà nínú ìwé *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ìṣọ̀lá, A. (1979) *Ẹfúnṣetan Aníwúrà*. Ìbàdàn: University Press Plc.

**Ìpín Kejì: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ**

**Àkóónú**

1.0 Ìfàárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*
4.1.1 Ìsọníṣókí Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*
4.1.2 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*
4.1.3 Ìfìwàwẹ̀dá
4.1.4 Ìlò Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ìwé eré-onítàn *Olú Ọmọ* tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ ni a ó máa ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ nínú ìpín kejì yìí. A ó jíròrò lórí kókó ọ̀rọ̀, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò-èdè.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- ṣe ìtúpalẹ̀ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*.
- ṣàlàyé àwọn kókó tó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*.
- ṣàlàyé kíkún nípa àhunpọ̀ ìtàn, ìlò-èdè àti ìfìwàwẹ̀dá eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kí ni kókó-ìtàn?
2. Ọ̀nà wo ni àwọn òǹkọ̀wé eré-oníṣe Yorùbá ń gbà fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn wọn?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*

### 4.1.1 Ìsọníṣókí Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*

Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ jẹ́ ìtàn gidi. Ìlú Ẹ̀gbá àti Èkó ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré-oníṣe náà ti wáyé. Nínú eré-oníṣe *Olú Ọmọ*, Aṣọ̀gbọ́n àti Adéyẹyè wá láti Èkó sí Ìlú Ẹ̀gbá láti dá Tinúubú padà sì Èkó kí ó lè ràn wọ́n lọ́wọ́ láti ja àjàgbara kúrò lọ́wọ́ ìrẹ́jẹ àti àmúsìn àwọn òyìnbó. Tinúubú kọ̀ jálẹ̀, kò fẹ́ padà sí Èkó. Ó ní ibi tí òun bá ti kí wọ́n pé ó dàárọ̀ òun kì í padà kí wọn káalẹ́ níbẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ pé Tinúubú kọ̀ láti padà sí Èkó, síbẹ̀ ó ṣe ìlérí ìrànlọ́wọ́ rẹ fún Aṣọ̀gbọ́n àti Adéyẹyè. Adébógun tí ó jẹ́ olórí ogun Ẹ̀gbá àti Òní wá bẹ Tinúubú pé kí ó darapọ̀ mọ́ àwọn ọlọ̀tẹ̀ yòókù láti ta Ẹ̀gbá fún ogun Ìdọ̀ọ̀mì. Tinúubú lòdì sí èrò Adébogun àti Òní láti ta Ẹ̀gbá fún ìdọ̀ọ̀mì torí owó. Tinúubú jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún Adébógun pé ọmọ àlè Ẹ̀gbá ni, bí bẹ́ẹ̀ kọ́ kò ní torí owó gbé àwọn ènìyàn rẹ̀ tà.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Tinúubú lòdì sí èrò pé kí wọ́n gbé Ẹ̀gbá tà fún Ìdọ̀ọ̀mì nítorí owó, síbẹ̀ Adébógun tẹ̀síwájú nípa ìpinnu rẹ̀ torí owó tí ó ti gbà. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní 'bí ẹnu bá jẹ tí ò yó, ojú ni yóò tì'. Ìgboyà tí Tinúubú ní ló mú kó tú àṣírí Adébógun láti gbé Ẹ̀gbá tà nítorí owó fún àwọn olóyè nínú ìpàdé wọn. Tinúubú ṣe ìlérí ìrànlọ́wọ́ àti àtìlẹ́yìn rẹ̀ fún àwọn Ẹ̀gbà, ó sì tún kì wọ́n láyà pé kí wọ́n máse bẹru ogun Ìdọ̀ọ̀mì tórí àwọn yóò sẹ́gun wọn dandan. Pẹ̀lú àtìlẹyìn Tinúubú àwọn Ẹ̀gbá kojú ogun Ìdọ̀ọ̀mì wọ́n sì ṣẹ́gun wọn. Àṣírí tú sí ọwọ́ àwọn Ẹ̀gbá pé àwọn obìnrin ni Ìdọ̀ọ̀mì dáṣọ ogun fún tí wọ́n sì ń bá Ẹ̀gbá jà. Lẹ́yìn tí Ẹ̀gbá ti sẹ́gun Ìdọ̀ọ̀mì, wọn fàbọ̀ sórí Adébógun àti Òní, wọ́n bẹ́ wọn lórí sídìí ògún ki ọ̀rọ̀ wọn lè jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún àwọn yòókù. Láti fi ìmoore hàn, fún ipa takuntakun tí Tinúubú kó láti ríi pé àwọn Ẹ̀gbá borí ogun Ìdọ̀ọ̀mì, gbogbo ìjòyè Ẹ̀gbá fi ẹnu kò wọ́n sì fi Tinúubú jẹ oyè Ìyálóde Ẹ̀gbá.

### 4.1.2 Kókó-ìtàn

Àwọn kókó inú eré-oníṣe *Olú Ọmọ* ni ìfẹ́ owó, ìfẹ́ ìlú ẹni àti àgbájọ ọwọ́. Nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* Ìṣọ̀lá korò ojú sí èrò àwọn Yorùbá tó ka àwọn obìnrin sí aláìlágbára tí wọn sì ń torí fojú tẹ́ńbẹ́lú obìnrin láwùjọ. Nínú eré-onítàn yìí, èrò àwọn

ènìyàn nípa obìnrin di ìyàtọ̀ ó sì gbé Tinúubú tí í ṣe olú ẹ̀dá-ìtàn náà kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí onígboyà àti alágbára obìnrin. Ó hàn gbangba pé kòṣeémánìí ní obìnrin láwùjọ àti pé agbára abo kò kéré.

**Ìfẹ́ Owó**

Ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn pàápàá àwọn akọ ni wọ́n máa ń fi hàn nínú òwe Yorùbá kan tó sọ pé owó lóbìnrin mọ̀. Òwe yìí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*. Nítorí ìfẹ́ owó, Adébógun gbà láti ta Ẹ̀gbá fún àwọn Ìdọ̀ọ̀mì. Adébógun fi èrò rẹ̀ hàn fún Tinúubú, ó fi owó lọ̀ ọ́, ó sì bèèrè fún àtìlẹ́yìn Tinúubú ṣùgbọ́n Tinúubú kọ̀ jálẹ̀ láti ta ìlú rẹ̀ nítorí owó. Ìṣọ̀lá jẹ́ kí ó hàn gbangba pé nítorí ìfẹ́ owó ni Adébógun ṣe gbà láti sílẹ̀kùn fún àwọn Ìdọ̀ọ̀mì láti kó àwọn ọmọ ìyá rẹ̀ lẹ́rú.

**Ìfẹ́ Ìlú Ẹni**

Tinúubú nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* fi ìfẹ́ ńlá tí ó ní sì ìlú rẹ̀ Abẹ́òkúta hàn nípa kíkọ̀ tí ó kọ̀ láti fi ààyè gba ogun Ìdọ̀ọ̀mì láti kó Ẹ̀gbá lọ. Ìfẹ́ yìí kan náà ni Tinúubú ló fún ìgboyà láti tú àṣírí Adébógun láàrin ìpàdé àwọn ìjòyè. Tinúubú fẹ́ràn ìlú rẹ̀ àti àwọn ènìyàn ibẹ̀. Èyí ló fi rò pé ohunkóhun tó bá ṣẹlẹ̀ sí àwọn ará ìlú ohun kan òun náà pẹ̀lú. Adébógun ní tirẹ̀ kò ní ìfẹ́ ìlú rẹ̀ lọ́kàn bẹ́ẹ̀ ni kò kọ̀ ki ogun Ìdọ̀ọ̀mì kó Ẹ̀gbá. Ìwà ọmọ àlè pọ́ńbélé ni Adébógun hù. Fásànyà pàápàá fi ìfẹ́ ńlá hàn sí ìlú rẹ̀ ni ìgbà tí kò bìkítà fún ọmọ rẹ̀ tí ogun mú sílẹ̀ ní Ìṣàgá. Ó darapọ̀ mọ́ àwọn Ẹ̀gbá láti ja ìjà ìlú. Àpẹẹrẹ rere ni Fásànya fihàn pé àlááfíà ìlú ṣe pàtàkì ju ìṣòro abẹ́ ilé lọ.

**Àgbájọ Ọwọ́**

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹnìkan kì í jẹ́ àwá dé àti pé igi kan kò lè dá igbó ṣe kí ìdàgbàsókè tó lóòrìn tó lè dé bá àwùjọ kan. Irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀ ní láti wà ní ìsọ̀kán torí òṣùṣù ọwọ̀ nìkan ló le gbá ilẹ̀ mọ́ tónítóní. Fún ìjàgbara lọ́wọ́ òyìnbó amúnisìn àti kí ìlú Èkó le tẹ̀síwájú ló mú Asọ̀gbọ́n àti Adéyẹyè bèèrè fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti àtìlẹyìn Tinúubú. Wọ́n mọ̀ pé agbára àwọn níkan kò tó láti kojú àwọn òyìnbó amúnisìn náà. Bákan náà, kí èrò Adébógun àti Òní lè jọ ni wọ́n ṣe bẹ Tinúubú láti darapọ̀ mọ́ wọn. Ṣe Yorùbá bọ̀ wọ́n ní

"ká rìn ká pọ̀, yíyẹ ní yẹni". Lékè gbogbo rẹ̀, ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìṣọ̀kan ti o wà láàrin àwọn obìnrin àti àwọn ológún yòókù ló jẹ́ kí wọ́n borí ogun Ìdọ̀ọ̀mì èyí fihàn pé àgbájọ ọwọ́ lá fií sọ̀yà. Ìṣọ̀lá jẹ kí ó di mímọ̀ fún àwọn òǹkàwé rẹ̀ pé nínú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ni àṣeyọrí wa. Láìsí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìsọ̀kan yóò ṣòro fún orílẹ̀-èdè kan láti tẹ̀síwájú.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Ìran mẹ́fà ni òǹkọ̀wé pín eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* sí. Ìran kìn-ín-ní wáyé nínú ilé Tinúubú. Jẹ́nrọ̀lá ló kọ́kọ́ ǹ kọ orin amúṣẹ́yá, orin yìí ni Jẹ́nrọ̀lá ń kọ lọ́wọ́ ni ìgbà ti Aṣọ̀gbọ́n àti Adéyẹyè wọlé láti ìlú Èkó. Nínú ìtàkùrọ̀sọ tó wáyè láàrin Asògbọ́n, Adéyẹyè àti Tinúubú ni ó ti di mímọ̀ fún àwọn òǹkàwé pe akíkanjú ẹ̀dá àti oníṣòwò pàtàkì ni Tinúubú. Nínú ìran kín-ín-ní yìí kan náà ni Adébógun àti Òní ti bèèrè fún àtìlẹyin Tinúubú pé ki wọn pawọ́pọ̀ ta Ẹ̀gbá fún Ìdọ̀ọ̀mì. Tinúubú fárígá pé òun kò le ta Ẹ̀gbá nítorí owó ṣùgbọ́n Adébógun fi ìwà ọmọ àlè hàn torí ó dúró lórí ìpinnu rẹ̀ láti ta àwọn Ẹ̀gbá fún Ìdọ̀ọ̀mì. Nínú ìran kejì àti ìkẹta ni òǹkọ̀wé ti fi èrò rẹ̀ nípa Adébógun múlẹ̀ síi. Nínú àwọn orí yìí ni Ìṣọ̀lá ti fi àwọn ológun tó nífẹ̀ẹ́ ìlú wọn hàn. Fásànyà sì jẹ́ ọ̀kan lára wọn. Bákan náà òǹkọ̀wé fi Adébógun àti Òní hàn gẹ́gẹ́ bí jẹgúdújẹrá ológun. Òǹkọ̀wé fi Tinúubú hàn gẹ́gẹ́ bí olú ọmọ nínú ìran kẹrin.

Tinúubú fi ara rẹ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí akínkanjú àti onígboyà ẹ̀dá-ìtàn nígbà ti ó tú àṣírí Adébógun láàfin Ṣómóyè. Nínú orí kẹrin yìí gan-an ni ìwà akikanjú tí òǹkọ̀wé gbé wọ obìnrin ti jẹyọ. Ní ìgbà ti Adébógun tí í ṣe olórí àwọn ológun sọ pé agbára àwọn ológun kò le ká ogun, Tinúubú kò bẹ̀rù rárá. Dípò ìbẹ̀rù, ṣe ni Tinúubú ki gbogbo àwọn ọkùnrin tí ó ń bẹ̀rù láyà. Ó sì ṣe ìlérí ìrànwọ́ ìbọn, ọta, ẹ̀tù àti ohun ìtura fún àwọn ológun lójú ogun. Ọ̀rọ̀ Tinúubú yìí ló sì fí ọkan àwọn ológun balẹ̀.

Ìran karùn-ún ni Adébógun àti àwọn ọlọ́tẹ̀ yòókù ti jà raburabu láti dá ìpayà sí ọkàn àwọn ará Ẹ̀gbá nípa gbígba àwọn Ẹ̀gbá níyànjú láti sá àsálà fún ẹ̀mí wọn lọ́nà àti dojú ogun Ẹ̀gbá bolẹ̀, ṣùgbọ́n Tinúubú kò jẹ́ ki èròǹgbà Adébógun àti àwọn ọlọ̀tẹ̀ yìí jọ. Níbi tí àwọn obìnrin ti ń sa ipá wọn láti rí i pé ìlú Ẹ̀gbá kò bàjẹ́ ni àwọn ọkùnrin ti ńlu ìlú tó bá lè túká kò túká. Tí a bá wò ó dáadáa, a ó ri pé èrò yìí ti yàtọ̀ sí ojú tí àwọn Yorùbá fi ń wo ipò obìnrin láwùjọYorùbá.

Ìran kẹ́fà ni ìparí àhunpọ̀ ìtàn *Olú Ọmọ*. Nínú ìran yìí sì ni òǹkọ̀wé ti wa kókó ọ̀rọ̀ rẹ̀ gúnlẹ̀. Ó hàn gbangba pé agbára abo kò ṣe é fojú tẹ́ńbẹ́lú. Àwọn obìnrin Ẹ̀gbá jà fitafita wọ́n sì borí ogun Ìdọ̀ọ̀mì. Ohun ti òǹkọ̀wé fẹ́ fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé àwọn obìnrin ti kúrò ni ẹni tí wọ́n ń fojú yẹpẹrẹ wò. Ní báyìí, kòṣeémánìí ni àwọn obìnrin jẹẹ́ nínú ìdàgbàsókè àwùjọ, akínkanjú sì ni wọ́n pẹ̀lú.

**Ibùdó-Ìtàn**

Ibùdó ìtàn gbogbogbòò fún eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* ni Abẹ́òkúta ni ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn ìlú mìíràn tó tún jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* bí i ibùdó ìtàn ni Èkó, Ẹ̀gbá, Ìṣàgá, Ìdọ̀ọ̀mì àti Agbádárìgì. Àwọn ibùdó-ìtàn pàtó ni ilé Tinúubú, Ilé ọmọ Ológun kan, Ilé Adébógun, Ààfin Ṣómòyè, ààrin ọjà ǹlá kan àti ibùdó ogun.

### 4.1.3 Ìfiwàwẹ̀dá

**Tinúubú**

Olú ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ni Tinúubú jẹ́. Oníṣòwò pàtàkì àti akíkanjú ẹ̀dá-ìtàn ni pẹ̀lú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, Tinúubú kò faramọ́ àjọsepọ̀ ààrin àwọn òyìnbó àti ará Èkó tí ó sì ti kìlọ̀ fún wọn, ṣùgbọ́n tí wọ́n kọ etí ikún sí, ọ̀rọ̀ Tinúubú. Ìgbésẹ̀ Tinúubú ṣe àfihàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí onípinnu ẹ̀dá-ìtàn. Tinúubú tún jẹ́ ẹ̀dá-ìtàn kan tó nífẹ̀ẹ́ ìlú rẹ̀ lọ́kàn èyí ló sì fihàn ní ìgbà tí ó kọ owó ti Adébógun kó wá fún un. Tinúubú ṣe àtìlẹ́yìn ní gbogbo ọ̀nà fún àwọn ológun Ẹ̀gbá títí wọ́n fi ṣẹ́gun Ìdọ̀ọ̀mì. Gbogbo ìwà akin ti Tinúubú hù ló jẹ́ ki àwọn ìjòyè fẹnu kò fi jẹ Ìyálóde Ẹ̀gbá lẹ́yìn tí wọ́n ti rẹ́yìn ọ̀tá wọn tán. Onígboyà, olóòótọ́ àti akíkanjú ẹ̀dá-ìtàn ni Tinúubú.

**Adébógun**

Olórí àwọn ológun Ẹ̀gbá ni Adébógun jẹ́ ṣùgbọ́n nítorí owó Adébógun gbà láti ta àwọn Ẹ̀gbá fún ogun Ìdọ̀ọ̀mì. Gbogbo ìkìlọ̀ àti àrọwà tí Tinúubú ṣe fún Adébógun kò tu irun kan lára rẹ̀. Ọ̀dájú àti ìkà ni Adébógun, ó wà lára àwọn tí wọ́n pa Fáyọmi ẹni tí wọ́n bẹ̀ láti ṣe amí fún Tinúubú. Adébógun kó àwọn ará ìlú Ẹ̀gbá sí ìpaya ó sì sọ fún wọn pé ọwọ́ àwọn ológun kò le ká ogun Ìdọ̀ọ̀mì. Fún ìdí èyí, ó gba àwọn ènìyàn Ẹ̀gbá nímọ̀ràn láti fi

ìlú sílẹ̀. Ọ̀kánjúà, àpà, ọmọ àlè àti arungún ẹ̀dá-ìtàn ni Adébógun. Bíbẹ̀ ni wọ́n bẹ́ orí Adébógun sí ìdí ògún fún ìwà ọ̀dàlẹ̀ tí ó hù sí ìlú rẹ̀.

**Fásànyà**

Ọ̀kan ni Fásànyà jẹ́ nínú àwọn ológun Ẹ̀gbá. Ó dun Fásànyà pé wọn kò pè é sí ètò tí wọ́n ń ṣe fún àwọn ọmọ ogun Ẹ̀gbá. Ogun mú Monílọ̀lá ọmọ Fásànyà sí Ìṣàgá síbẹ̀ ọ̀rọ̀ ìlú rẹ̀ ló jẹ ẹ́ lógún. Òǹkọ̀wé fi Fásànyà hàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá-ìtàn tó fẹ́ràn ìlú rẹ̀ dénúdénú. Bákan náà ni Fásànyà jẹ́ olóòótọ́ ènìyàn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó jẹ́ tálákà àti aláìní kò torí èyí gba owó tí wọ́n fún àwọn ọmọ ológun láti ta Ẹ̀gbá fún àwọn Ìdọ̀ọ̀mì. Nínú ìmọ̀ràn ti Fásànyà fún Adébógun ló ti hàn gbangba pé bi ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ẹ̀dá-ìtàn kan wà tí wọ́n tòṣì, tí wọ́n kò sì rọ́wọ́ họrí tó bẹ́ẹ̀ láwùjọ, síbẹ̀ wọn sì lè jẹ́ olóòótọ́ ènìyàn tí ó nífẹ̀ẹ́ àwùjọ wọn, tí wọ́n sì ń làkàkà fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn náà, láì wò ipò àìní tí wọn wà. Ẹ̀dá-ìtàn tó yẹ fún àwòkọ́ṣe ni Fásànyà jẹ́.

**Ṣómóyè**

Kábìyèsí àti Baṣọ̀run ni Ṣómóyè jẹ́ ní Ẹ̀gbá. Ogun Ìdọ̀ọ̀mì tí Ṣómóyè gbọ pé ó ti dé Ìṣàgá ni ó mú un pé ìpàdé pàjáwìrì sí ààfin rẹ̀. Ní ìgbà tí Ṣómóyè ti rí ọwọ́ ìjà ní ìlasà pé olórí ogun Ẹ̀gbá tí ó ń jẹ́ Adébógun kò ṣetán láti kojú ogun Ìdọ̀ọ̀mì, Ṣómóyè yọ̀ǹda ara rẹ̀ láti ṣíwájú ogun Ẹ̀gbá àti láti ségun Ìdọ̀ọ̀mì. Pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ àti àtìlẹ́yìn akíkanjú obìnrin Tinúubú, Ṣómóyè àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ ségun Ìdọ̀ọ̀mì. Lẹ́yìn ìṣégun Ẹ̀gbá lórí Ìdọ̀ọ̀mì wọ́n bẹ́ orí Adébógun sí ìdí ògún bẹ́ẹ̀ ni Ṣómóyè àti àwọn ìjòyè yòókù fi Tinúubú jẹ Ìyálóde Ẹ̀gbá láti fi ìmọrírì àtìlẹ́yìn tó ṣe fún wọn hàn. Ṣómóyè jẹ́ olórí tí ó fi àpẹẹrẹ rere lélẹ̀, nítorí ẹlẹ́rù ló máa ń gbé e níbi tí ó bá ti wúwo. Yíyọ̀ǹda ti Ṣómóyè yọ̀ǹda láti ṣaájú ogun Ẹ̀gbá ló mú àwọn ọmọ ológun yòókù gbárùkù tì í.

### 4.1.4 Ìlò-Èdè inú Eré-Oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*

Akin Ìṣọ̀lá nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* lo èdè láti mú kókó ọ̀rọ̀ tí ó ń sọ nínú eré-onítàn yìí dùn ni. Àwọn ohun tí a ó máa jíròrò lé labẹ ìlò èdè Ìṣọ̀lá nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* ni: àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, ìfọ̀rọ̀dárà, àwítúnwí, ọfọ̀, òwe àti orin.

**Àfiwé Tààrà**

Nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* àfiwé tààrà jẹyọ ní ìgbà tí Tinúubú àti Adébógun ń ṣe gbólóhùn asọ̀.

Tinúubú: Mo da ọ sí fún ìyà tí ń bọ̀ ni,
bi ikú ti í ṣarúgbó dẹ̀gbẹ dìgbà
ọ̀gìnnìntìn (o.i. 16)

Ìyà tí Tinúubú yóò fi jẹ Adébógun ló fi wé ìyà tí òtútù máa fi ń jẹ arúgbó lásìkò ọyẹ́. Fún àpẹẹrẹ àfiwé tààrà mìíràn wo ojú ìwé 39, 44 àti 47.

**Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́**

Ìṣọ̀lá tún ṣàmúlò àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* nípa ṣíṣe àfidípò ohun méjì tí ó jọra. Lílé tí Adébógun àti àwọn ọlọ̀tẹ̀ yòókù lé àwọn obìnrin tó lọ pọn omi lodò padà ló jẹ́ ki Tinúubú sọ̀rọ̀ báyìí:

Ọkùnrin nìkà
Ọkùnrin lèké (o. i. 74).

Ìwà àti ìṣe Adébógun àti àwọn yòókù rẹ̀ lo jẹ́ ki Tinúubú sọ wọ́n di ìkà àti èké. Tinúubú fi hàn pé ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ọkùnrin ni ìwà ìkà ti wọ̀ lẹ́wù kì í ṣe obìnrin nìkan.

**Ìfọ̀rọ̀dárà**

Ìfọ̀rọ̀dárà jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* lásìkò ti Tinúubú jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún àwọn obìnrin ipa tí wọ́n ni láti kó nínú ogun ti Ẹ̀gbá fẹ́ bá Ìdọ̀ọ̀mì jà. ‘Kú’ àti ‘Kù’ ni òǹkọ̀wé fi dára gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àyọ́lò ìsàlẹ̀ yìí.

Ẹran kú ó fiṣẹ́ sílẹ̀ fáwọ
Ìwọ̀fà kú, ó dá aáwọ̀ sílẹ̀
Ẹni tó kú, ẹ kú ìsinmi,
Ẹni tó kù, ẹ kú u wàhálà

**Àwítúnwí**

Àwítúnwí jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*. Bí àpẹẹrẹ àwọn àwítúnwí yìí, wo ojú ìwé 7, 11 àti 34.

**Ọfọ̀**

Yorùbá gbàgbọ́ nínú agbára ọfọ̀. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn Yorùbá máa ń gbà lo ọfọ̀. Wọ́n lè lò ó fún ìwúré, láti pàṣe tàbí láti yi èrò ọkàn ènìyàn padà. Fún àpẹẹrẹ

… a kì í rídìí okun
A kì í rídìí ọ̀sà
A kì í rídìí ọmọnígèdègédé

Asọ̀gbọ́n ló lo ọfọ̀ òkè yìí láti wúre fún Tinúubú. Wo àpẹẹrẹ síi ni ojú ìwé 74.

**Òwe**

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni òǹkọ̀wé gbà lo òwe nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*. Bí ó ṣe lo òwe kéékèèké náà ló ń ki òwe délẹ̀délè. Bí òǹkọ̀wé ṣe lo òwe láti ṣàlàyé ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ náà ló ṣàmúlò òwe láti ṣe ìbéèrè. Bí àpẹẹrẹ àwọn ọ̀kan-ò-jọ̀kan òwe yìí ki akẹ́kọ̀ọ́ wo ojú ìwé 4, 6, 11, 34, 38, 44, 47, 48, 50.

**Orin**

Èròjà alohùn ti Ìṣọ̀lá ṣàmúlò jùlọ nínú ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* ni orin. Àwọn orin tí ó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* jẹ́ orin amóríyá, orin Ifá àti orin ọ̀tẹ̀ àti ogun. Fún àgbéyẹ̀wò àwọn orin yìí wo ojú ìwé 1, 2, 5, 7, 58, 57, 59, 61, 64, 78, 84, 73, 75 àti 77. Gbogbo àwọn orin ti Ìṣọ̀lá ṣàmúlò yìí ló ṣe wẹ́kú ní ọ̀gangan ibi tí wọ́n ti jẹyọ. Òǹkọ̀wé tí ó mọ èdè tí ó gbọ́ èdè, tí ó sì tún mọ àgbekalẹ̀ èdè ni Ìṣọ̀lá. Ọ̀gá ní Ìṣọ̀lá tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìlò-èdè.

**5.0 Ìsọníṣókí**

Eré eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* jẹ́ ìtàn gidi. Agbára abo, ìfẹ́ owó, ìfẹ́ ìlú ẹni àti àgbájọ ọwọ́ ni àwọn kókó tí ó hànde nínú *Olù Ọmọ*. Ìran mẹ́fà ni òǹkọ̀wé *Olù Ọmo* pín in sí. Ibùdó ìtàn gbogbogbòò fún eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ* ni ìlú Abẹ́òkúta ni ilẹ̀ Yorùbá. Tinúubú ni olú ẹ̀dá-ìtàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí. Àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, ìfọ̀rọ̀dárà, àwítúnwí, ọfọ̀, òwe àti orin ni àwọn ìlò èdè tí ó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣe ìsọníṣókí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*.
2. Jíròrò lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ ti Ìṣọ̀lá fihàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Olú Ọmọ*.
3. Ọ̀nà wo ni Ìṣọ̀lá gbà hun eré-onítàn Olú Ọmọ pọ̀?
4. Ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ọ̀nà tí ònkọ̀wé gbà láti yí ojú tí wọ́n fi ń wo obìnrin láwùjọ Yorùbá padà.
5. Ṣe agbéyẹ̀wò àwọn ọnà-èdè tí a tọ́ka sí nínú eré-oníṣe yìí.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ìṣọ̀lá, A. (1979) *Olú Ọmọ* Ìbàdàn: Oníbọnòje Press & Book Industries (Nig) Ltd.

**Ìpín Kẹta: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ**

**Àkóónú**

1.0 Ìfààrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*: Ọládẹ̀jọ Òkédìjí

4.1.2 Ìsọníṣókí Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*: Ọládẹ̀jọ Òkédìjí

4.1.3 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

4.1.4 Ìfìwàwẹ̀dá inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

4.1.5 Ìlò-Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

*Rẹ́rẹ́ Rún*, eré-oníṣe àpilẹ̀kọ afẹ̀hónú hàn tí Ọládẹjọ Òkèdìjí kọ ni a ó máa túpalẹ̀ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àwọn fọ́nrán tí a ó máa gbéyẹ̀wò ni kókó-ìtàn, àhunpọ̀-ìtàn, ibùdó-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò-èdè.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- jíròrò lórí àwọn fọ́nrán eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*.
- ṣàlàyé kíkún lórí kókó ọ̀rọ̀ tí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún* dálé.
- sọ iṣẹ́ pàtàkì tí eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún* ń jẹ́ fún àwùjọ.
- ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò-èdè nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*
- ṣe àgbéyẹ̀wò Láwúwo gẹ́gẹ́ bí olú ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Àwọn fọnrán wo ni a fi ń ṣe àtúpalẹ̀ àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá?
2. Dárúkọ àwọn ọnà-èdè tí a lè bá pàdé nínú àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

## 5.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ

### 4.1.1 Ìsọnísókí *Rẹ́rẹ́ Rún*

Eré-oníṣe afẹ̀hónúhàn pọ́ńbélé ni *Rẹ́rẹ́ Rún* jẹ. Láwúwo ni ó jẹ́ olórí àwọn òṣìṣẹ́ ni ìlú Mògún tó ń bèèrè ẹ̀kúnwó owó oṣù àti ìtọ́jú lákòkò, àìsàn. Bẹ́ẹ̀ ni àwọn òṣìṣẹ́ tún fẹ́ ní aṣojú nínú ìgbìmọ̀ ìlú. Lẹ́yìn tí àwọn aláṣẹ ìlú Mògún ti ju Láwúwó sí àtìmọ́lé wọ́n pinnu láti fi Ìdòwú ṣe ọ̀gá àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn òṣìṣẹ́ ṣe ìpàdé wọ́n sì kówójọ láti gba lọ́yà fún olórí wọn tí ó wà ní àtìmọ́lé. Lójijì Láwúwó yọ sí àwọn òṣìṣẹ́, ó sì kọ́ owó ti àwọn òṣìṣẹ́ dájọ láti gba lọ́yà fún un. Láwúwo ní òun kò kọ̀ láti padà sí àtìmọ́lé. Kíkọ̀ tí Láwúwo kọ owó tí àwọn òṣìṣẹ́ dájọ fún un, ló mú àwọn òṣìṣẹ́ kó owó náà ránṣẹ́ sí Morẹ́nikẹ́, ìyàwó Láwúwo pé bóyá ó lè bá ọkọ rẹ̀ sọ̀rọ̀ láti gba owó náà. Láwúwo bínú sí ìyàwó rẹ̀ nígbà tí ó gbọ́ pé ó gba owó lọ́wọ́ àwọn òṣìṣẹ́. Láwúwo pàṣẹ fún Morẹ́nikẹ́ ìyàwó rẹ̀ láti dá owó náà padà fún àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn ìjòyè ránṣẹ́ sí Láwúwo, wọ́n sì ṣe ìlérí fún un pé àwọn yóò fún un ní oríṣìíríṣìí nǹkan àti owó tí yóò mu ayé dẹrùn fún un ṣùgbọ́n Láwúwo kọ̀ láti dalẹ̀ àwọn òṣìṣẹ́. Bí àwọn ìjòyè ṣe ń fi àwọn nǹkan amáyédẹrùn tí wọ́n gbèrò láti fún Láwúwo hàn án ni wọ́n ń yà á ni fọ́tò ṣùgbọ́n Láwúwo kò ka èyí sí bàbàrà rárá. Àwọn fọ́tò yìí ni àwọn ìjòyè sì lo láti kọ ẹ̀yìn Láwúwo àti àwọn òṣìṣẹ́ sí ara wọn. Àwọn oníjíbìtì lu Morẹ́nikẹ́, ní jìbìtì wọ́n sì gbà gbogbo owó òṣìṣẹ́ tí ọkọ rẹ̀ ní kí ó dá padà lọ. Fún ìdí èyí, Morẹ́nikẹ́ pa ara rẹ̀. Ní ìgbà tí Láwúwo mọ̀ pé Morẹ́nikẹ́, ìyàwó òun ti kú, tí ó sì tún rántí pé ààrín òun àti àwọn òṣìṣẹ́ kò gún mọ́, ọkàn rẹ̀ dàrù ó sì yí lórí. Báyìí ni àwọn òṣìṣẹ́ padà si ẹsẹ ààrọ̀ ti rẹ́rẹ́ sì rún.

## 4.2 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

Kókó pàtàkì ni ó jẹyọ nínú eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* ni ìmúnisìn àti ìjàgbara lọ́wọ́ amúnìsin. Ní ìgbà tí àyànmọ́ àti ìwà ìkà jẹ́ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó nínú eré onítàn náà.

### Ìmúnisìn àti Ìjàgbara lọ́wọ́ Amúnisìn

Nínú eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* àwọn agbanisíṣẹ́ ni amúnisìn tí wọ́n ń lo àwọn òṣìṣẹ́ bí ẹrú. Nígbà tí àwọn òṣìṣẹ́ kò tîì rí oúnjẹ jẹ, Onímògún ń fi owó tó yẹ kí wọ́n fi ṣanwó oṣù wọn ra aga onígóòlù. Ẹ̀yìn etí Onímògún àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ni gbogbo àlàyé tí Akọ̀wé ń ṣe lórí ìdí ti owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ fi yẹ ní sísan ń bọ́ sí. Èyí farahàn nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Onímògún: Wò mi jàre, àkọwé, ta ló sọ pé àga un ló yẹ mi? àga alága ìgbímọ́ ìlú Mògún. Àga tí a bá rà ní láti fi ipòò mi gẹ́gẹ́ bí ọba hàn, kí ó buyí kún mi.

Akọ̀wé: Àbí kí á sì ra onírin tí wọ́n yọ́ omi góòlù sí lára.

Onímògún: Ẹ̀ẹ̀ẹ̀n! ibo lo ti fi orúkọ sí tí o ń jẹ́ Làǹbòròkí.

Olúgbọ̀n: Ká sì ra tìmùtìmù fùẹ̀fùẹ̀ sí i. Irínisí sáà ni ìsọnilọ́jọ̀

Akọ̀wé àgbà: Ṣùgbọ́n, Kábíyèsí….

Onímògún: Ṣùgbọ́n wo tún ni o, akọ̀wé?

Akọ̀wé àgbà: Mo ní kí n rán yín létí ni… pé a kò tîì sanwó

oṣù

àwọn òṣìṣẹ́… fún oṣù tó kọjá.

[*Onímògún wò ó tíbínú tìbínú]*

Onímògún: Nítorí náà ń kọ́?. Ọjọ́ wo lóṣùú parí ná?

Olúgbọ̀n: Owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ ló ṣe pàtàkì ni, àbí owó ọba ìlúù wa? Bí kò bá sí ọba, bí kò bá sí ìjòyè, ta ni òṣìṣẹ́ yóó gba owó oṣù lọ́wọ́ rẹ̀?

Onímògún: Ṣe bí ẹrú Láwúwo ni gbogbo wọn! O ò jẹ́ kó máa pè wá ní ìkà. Àbí, bí ènìyàn kò bá níí finràn, èló ni owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́, èló si ni owó àga ẹyọkan ṣoṣọ tí a ń sọ. Àwọn òṣìṣẹ́ ìlú Mògún ń ṣiṣẹ́ bí erin ṣùgbọ́n wọ́n ń jẹ ìjẹ èlírí.

> Ọ̀rọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ yìí wa di iṣẹ́ la rí, a kò rówó. Iṣẹ́ èèyàn mẹ́fà tí ẹnìkan ṣoṣo ń ṣe ni àṣelàágùn ló mú àwọn òṣìṣẹ́ ìlú Mògún bèèrè fún ẹ̀kúnwó owó oṣù wọn àti ìtọ́jú lákòkò àìsàn. Àwọn òṣìṣẹ́ tún sọ fún àwọn agbaniṣíṣẹ́ wọn pé àwọn náà fẹ́ ẹ́ ní aṣojú nínú ìgbìmọ̀ ìlú láti lè máa jà fún ẹ̀tọ́ àwọn ṣùgbọ́n àwọn agbaníṣíṣẹ́ ka gbogbo ìbéèrè àwọn òṣìṣẹ́ yìí sí ìkọjá ààyè ẹni bẹ́ẹ̀ ni wọn kò ṣetán láti gba ọ̀rọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ rò.

Gbogbo ipá àti ọgbọ́n arúmọjẹ ni àwọn agbaniṣíṣẹ́ lò láti dá ààrín àwọn òṣìṣẹ́ rú. Kàkà kí ewé àgbọn àwọn òṣìṣẹ́ dẹ̀ koko ni ó tún le sí i. Àjẹkún ìyà ni àwọn òṣìṣẹ́ ìlú Mògún jẹ, wọ́n kùnà láti bọ́ lọ́wọ́ àwọn amúnisìn wọn.

**Àyànmọ́**

Àwọn Yorùbá kò fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ àyànmọ́. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé “Bí a ṣe wáyé wárìí là á rí”. Wọ́n tún máa ń pa á lówe pé “Bí orí bá ń da ọdẹ láàmú, á fi gbogbo ọjọ́ sọdẹ láì mẹ́ran bọ̀ oko, bí orí bá padà lẹ́yìn àgbẹ̀, irú iṣu àgbẹ̀ bẹ́ẹ̀ a máa jọ́bà lébè, àtàrí laláyànmọ́, orì lẹlẹ́jọ́”. Gbogbo ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí Láwúwo nínú eré onítàn *Rẹ́rẹ́ Rún* ni a lè pè ní àyànmọ́, nítorí pé tí a bá wo èsì tí ó fún Morẹ́nikẹ́ nígbà tí ìyẹn ni kó sinmi, a óò ríi dájú pé ìyà jíjẹ jẹ àyanmọ̀ ìràn rẹ̀, ó ní:

| | |
|---|---|
| Morẹ́nikẹ́: | Lónìí yìí náà? Ẹ kò níí simi rárá ni? |
| Láwúwo: | Isinmi! Isinmi! Mo sinmi irúu rẹ̀ rí lójúù rẹ láti ọjọ́ tí o ti mọ̀ mi? Mọlémọlé ni mi, mọlémọlé ni baba tó bí mi. Àjogúnbá ilé wa ni. Nínú ilé tí ọ̀mọ̀lé é mọ, mélòó ni ti òun fúnraa rẹ̀ níbẹ̀? O gbàgbé pé ilé onílè ni bàbáà mi ń mọní òkè ọjà tí ògirí fi wó pa á? Ṣe bí àwa mọ́kànlá ni ọmọ ti babaà mí fi sílẹ̀, tọkùnrin, tóbìnrin. Ìyáà mi àbẹ̀jẹ́ ọ̀kin, ó ṣiṣẹ́, ṣiṣẹ́ bí ẹni máa kú, kí a le máa róúnjẹ jẹ! Ṣe bí èyí ló dà á lórí rú, tí ó fi bẹ̀rẹ̀ sí sìnwìn. Nígbà tí omi pọ̀ ju èlùbọ́ lọ, ni mo fi kọ́ṣẹ́ẹ̀ bíríkìlà, tí mo tún kọ́ káfìnńtà, tí mo kọ́ ilé kíkùn lọ́dà, kí ń tó wáá lọ sí lẹ́sìnnì tí mo fi mọ táátàátá tí mo fi ń ṣamọ̀nà àwọn òṣìṣẹ́ lónìí. Ìwọ wo orógùn tí ń rokà. Ọkà mélòó ni orógún ń jẹ? Ṣíbí tó ń torí bọ ọbẹ̀ gbígbóná, bí |

> ọbẹ̀ díẹ̀ bá ṣẹ́kù sára ṣíbí, ṣe bí fífá ni wọ́n ọ́n fá a, tí wọ́n ọ́n fi ọṣẹ ẹ́ fọ ìyóókù kúrò. Ẹ̀ṣẹ̀dálẹ̀ ilée wa ni, ká máa ṣiṣẹ́ oníṣẹ́ láìro wàhálà tó wà níbẹ̀, láìrò nípa èrè gúnmọ́ kan fún araa wa. Iṣẹ́ tí èmí bá ṣe sílẹ̀, bí ń kò tilẹ̀ dúró jẹ nínú rẹ̀, bó báá yá, ẹni ti mo ṣe é fún le ṣe ọmọ tèmi náà lóore, ọmọ tí Ọlọ́run bá fún wa. Jẹ́ kí n tètè máa lọ, Morẹ̀nikẹ́. Bí mo bá dé, màá pa ààrẹ pọ̀. Wọ́n ni àwọn ń fẹ́ẹ́ bá mi sọ̀rọ̀ ni, a kò sì mọ ohun tí wọ́n ń fẹ́ẹ́ sọ. (o.i. 41-42)

**Ìwà Ìkà**

Ìdòwú tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òṣìṣẹ́ jẹ́ ìkà ènìyàn àti agbẹ̀yìnbẹbọjẹ́. Gbogbo àṣírí àwọn òṣìṣẹ́ ni Ìdòwú máa ń tú fún àwọn agbaniṣíṣẹ́ nítorí ohun tí àwọn agbaniṣíṣẹ́ máa ń fún un. Ìdòwú yìí kan náà ni àwọn agbaniṣíṣẹ́ fẹ́ fi ṣe olórí àwọn òṣìṣẹ́ ní ìgbà tí wọ́n ti Láwúwo mọ́ ilé ṣùgbọ́n àwọn òṣìṣẹ́ lòdì sí èyí. Lọ́nà àti di ọ̀gá àwọn òṣìṣẹ́, Ìdòwú rán àwọn oníjìbìtì láti gba owó tí àwọn òṣìṣẹ́ kó fún Morẹ́nikẹ́ ìyàwó Láwúwo. Àbájáde jìbìtì yìí ikú Morẹ́nikẹ́ ni ó jásí èyí tí ó sì fa dídàrú tí orí Láwúwo dàrú. Ìkà, ọ̀dájú àti ọ̀dàlẹ̀ ẹ̀dá ni Ìdòwú jẹ́ láàrin àwọn òṣìṣẹ́ ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Ìpín mẹ́wàá ni òǹkọ̀wé eré eré-oníṣe *Rẹ́rẹ̀ Rún* pín in sí. Orin tí àwọn òṣìṣẹ́ ń kọ ni Òkédìjí fi bẹ̀rẹ̀ ìpín kìnín-ní. Ọ̀nà tí àwọn òṣìṣẹ́ ń gbà kọ orin yìí mú ìkáànú lọ́wọ́ èyí sì ń ṣe àfihàn pé inú àwọn òṣìṣẹ́ kò dùn rárá. Nínú ìtàkùrọ̀sọ àwọn òṣìṣẹ́ ni ó ti di mímọ̀ pé olórí wọn Láwúwo wà ní àtìmọ́lé, àwọn òṣìṣẹ́ sì ń gbèrò àti gba lọ́yà tí yóò ṣe ìdúró fún ọ̀gá wọn tó wà látìmọ́lé, tí yóò sì tún ṣẹnu fún àwọn òṣìṣẹ́ bí ọ̀rọ̀ bá di ti kóòtù. Ní ìpin kejì ni Onímògún àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ti sàyẹ̀wò àwọn ohun èlò tí àwọn òṣìṣẹ́ bàjẹ́. Ó hàn gbangba pé lórí ẹ̀tọ́ àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n bèèrè fún ni àwọn agbanisíṣẹ́ ṣe ti Láwúwo mọ́lé. Àwọn agbanisíṣẹ́ pẹ̀lú tún ti ń gbèrò ohun mìíràn tí wọ́n lè ṣe láti wagbò dẹ́kun fún àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn òṣìṣẹ́ kówójọ nínú ìran kẹta láti gba lọ́yà fún Láwúwo ṣùgbọ́n sí ìyàlẹ̀nu wọn Láwúwo yọ sí wọn kúlẹ̀.

Láwúwo lòdì si owó tí àwọn òṣìṣẹ́ dá láti gba lọ́yà fún un. Ìgbàgbọ́ Láwúwo ni pé àwọn òṣìṣẹ́ kò tíì jẹun yó débi pé wọn yóò máa gba lọ́yà fún òun. Owó tí àwọn òṣìṣẹ́ dá láti gba lọ́yà fún Láwúwo ṣùgbọ́n tí ó kọ̀ jálẹ̀ láti gba ni àwọn òṣìṣẹ́ kó lọ fún Morẹ́nikẹ́ ìyàwó Láwúwo ni ìpín kẹrin. Láwúwo bínú sí ìyàwó rẹ̀, ó sì pàṣẹ fún un láti dá owó náà padà. Nínú ìpín yìí kan náà, òwú àti abẹ́rẹ́ ni Morẹ́nikẹ́ fi ń rán aṣọ Láwúwo tí ó fàya, èyí si ń fi Láwúwo àti ìyàwó rẹ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí akúṣẹ̀ẹ́. Láwúwo fúnrarẹ̀ tún fi ẹnu ara rẹ̀ sọ ní ìpín kẹrin yìí bí bàbá rẹ̀ ṣe kú níbi tí ó ti ń mọ ilé onílé tí àtijẹ àtimu sì sọ ìyá rẹ̀ di asínwín. Àwọn ìjòyè ránṣẹ́ pe Láwúwo nínú ìpín karùn-ún wọ́n sì fi ilé, owó àti àwọn oríṣìíríṣìí nǹkan tí wọn yóò fi dáa lọ́lá hàn án. Bí wọ́n ṣe ń fi gbogbo nǹkan wọ̀nyìí hàn Láwúwo ni wọ́n ń ya fọ́tò rẹ̀, ṣùgbọ́n Láwúwo kò ka fọ́tò tí wọ́n ń yà si nǹkankan. Báyìí ni Láwúwo kó sínú pańpẹ́ tí àwọn ìjòyè dẹ sílẹ̀ fún. Fọ́tò tí àwọn olóyè yà yìí ni wọ́n mú tọ àwọn òṣìṣẹ́ lọ èyí tí ó bu omi tútù sọ́kàn àwọn òṣìṣẹ́, tí wọn kò sì ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Láwúwo mọ́ gẹ́gẹ́ bí olórí wọn. Àwọn ìjòyè dunnú pé àwọn ṣàṣeyọrí nípa dídá wàhálà sílẹ̀ láàrin àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn ìjòyè tún bẹ́ Ìdòwú lọ́wẹ̀ láti ríi pé àlàáfíà kò jọba láàrin àwọn òṣìṣẹ́. Nínú ìpín kẹfà àtì keje, Ìdòwú rán àwọn oníjìbìtì sí Morẹ́nikẹ́, ìyàwó Láwúwo láti gba owó tí ọkọ rẹ̀ ní kí ó dá padà fún àwọn òṣìṣẹ́. Èyí ló sì mú kí Morẹ́nikẹ́ gbé òògùn jẹ tí ó sì dágbére fáyé. Ìpín kẹjọ ni àwọn òṣìṣẹ́ ti fi ẹ̀sùn kan Láwúwo pé ó ti gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ìjòyè, ó ti fi ọ̀bẹ ẹ̀yìn jẹ àwọn ní iṣu. Wúràọla àti Sàríyù bẹ́ Láwúwo láti foríjin Morẹ́nikẹ́ fún owó ti àwọn oníjìbìtì gbà lọ́wọ́ rẹ̀. Agolo owó àti ìgò oògùn tí Láwúwo rí ló jẹ́ kí ó mọ̀ pé Morẹ́nikẹ́ ti kú èyí ló sì dà á lórí rú.

Ní ìpín kẹsàn-án àwọn òṣìṣẹ́ wá bá Láwúwo kẹ́dùn lórí ikú ìyàwó rẹ̀, Morẹ́nikẹ́, ṣùgbọ́n ó hàn gbangba pé ọkàn Láwúwo ti dàrú. Ìpín kẹwàá ni àwọn òṣìṣẹ́ ti padà sí ẹnu iṣẹ́ wọn. Onímògún ránṣẹ́ ìbánikẹ́dùn sí àwọn òṣìṣẹ́ lórí ikú Morẹ́nikẹ́, ó sì jẹ́ ki wọ́n mọ̀ pé Ìdòwú ni àwọn yàn báyìí láti jẹ́ olórí àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn òṣìṣẹ́ tún padà si ẹsẹ àárọ̀.

**Ibùdó-Ìtàn**

Ibi tí a lè pè ni ibùdó ìtàn gbogbogbòò fún eré-oníṣe Rẹ́rẹ́ Rún ni ìlú Ìmògún àti gbogbo ilé iṣẹ́ ìjọba jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá àti orílẹ̀ èdè Nàìjíríà lápapọ̀. Ní ìgbà ti àwọn ibùdó ìtàn pàtó jẹ́ ibi iṣẹ́ àwọn òṣìṣẹ́, ààfin Onímògún àti ẹ̀bá ojú ọ̀nà.

### 4.1.3 Ìfìwàwẹ̀dá inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

Ní ìsọ̀rí yìí àwọn ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* ni a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò wọn. Bí ó ti jẹ́ pé a kò lè se àgbéyẹ̀wò gbogbo àwọn ẹ̀dá-ìtàn náà tán, àwọn mẹ́fà péré ni a ó máa sọ̀rọ̀ nípa wọn, kí akẹ́kọ̀ọ́ gbìyànjú láti ṣàgbéyẹ̀wò ìfìwàwẹ̀dá àwọn ẹ̀dá-ìtàn yòókù tí a kò mẹ́nu bà.

**Láwúwo**

Láwúwo ni olú ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún*. Láwúwo ni olórí àwọn òṣìṣẹ́ ni ìlú Mògún. Akọni ẹ̀dá-ìtàn ládojúdé ni Láwúwo jẹ. Gbogbo ipá, agbára, ọgbọ́n, ìmọ̀ àti oye tí Láwúwo ní ló ṣàmúlò láti rí i pé àwọn òṣìṣẹ́ ẹgbẹ́ rẹ̀ tí ó jẹ́ olórí fún ja àjàbọ́ lábẹ́ àwọn amúnisìn tí í ṣe àwọn agbaniṣíṣẹ́ wọn, ṣùgbọ́n gbogbo akitiyan àti ìlàkàkà Láwúwo pàbó ló jásí. Gbogbo akitiyan Láwúwo láti mú ayé dẹrùn fún àwọn òṣìṣẹ́ èyí tí ó jásí pàbó ni a rí bí àyànmọ́ rẹ̀ nítorí pé kí a máa ṣe akitiyan tàbí wàhálà láì yọrí sí rere jẹ́ ohun tí Láwúwo jogún nínú ìṣẹ̀dálẹ̀ ilé wọn. Láwúwo jẹ́ ẹ̀dá-ìtàn tí ó ní ìpinnu bẹ́ẹ̀ ni ò sì jẹ́ alágídí ọkàn èyí sì jẹ́ ọ̀kan lára ohun tí ó ṣe àkóbá fún un. Agídí ọkàn àti ipinnu Láwúwo ni ó jẹ́ kí ó kọ̀ jálẹ̀ láti gba owó lọ́yà tí àwọn òṣìṣẹ́ dájọ fún un. Àìgba owó lọ́wọ́ àwọn òṣìṣẹ́ ló jẹ́ kí wọ́n kó owó náà lọ fún Morẹ́nikẹ́ ìyàwó Láwúwo. Bí Láwúwo bá gba owó náà ni, owó náà kì bá tí dé ọdo. Ìyàwó rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn oníjìbìtì kò bá má rí àyè láti ṣe iṣẹ́ ọwọ́ wọn. Agídi ọkàn Láwúwo ló ṣekú pa ìyàwó rẹ́ tí ó sì sọ òun gan di asínwín.

Bákan náà, Láwúwo jẹ́ ẹ̀dá-ìtàn tí kò ní àkàsì bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Láwúwo mọ̀ pé agbẹ̀yìnbẹbọjẹ́ ni Ìdòwú, kò ṣe ohunkóhun nípa rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni nígbà tí àwọn ìjòyè ń ya fọ́tò rẹ nígbà tí wọ́n pè é sí ìpàdé, kò ka èyí náà si rárá. Fọ́tò yìí ni àwọn olóyè sí lò láti da àárín Láwúwo àti àwọn òṣìṣẹ́ rú. Ó hàn gbangba pé alágbára máa mèrò ẹ̀dá-ìtàn ni Láwúwo, ó lágbára nítòòótọ́ ṣùgbọ́n kò fi ọgbọ́n kún un. Alágbára má mérò sì ni bàbá ọ̀lẹ. Àbùdá méjì yìí, agídí àti àìlákàsí ni kò jẹ́ kí Láwúwo ṣe àṣeyọrí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Láwúwo jẹ́ alágídí ọkàn àti aláìlákàsí ẹ̀dá-ìtàn, olóòótọ́ ènìyàn ni. Ó kọ̀ láti gba gbogbo ohun amáyédẹrùn tí àwọn olóyè fún un. Láwúwo kọ̀ láti dalẹ̀ àwọn òṣìṣẹ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn olóyè parọ́ mọ́

ọn pé ó gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ síbẹ̀ àṣírí padà tú si ọwọ́ àwọn òṣìṣẹ́ pé irọ́ ni àwọn ìjòyè ń pa ṣùgbọ́n aṣọ kò bá ọmọ́yẹ mọ́, ọmọ́yẹ ti rin ìhòhò wọ ọjà, bẹ́ẹ̀ ni rẹ́rẹ́ ti rún.

**Morẹ́nikẹ́**

Morẹ́nikẹ́ ni ìyàwó Láwúwo tí í ṣe olú ẹ̀dá-ìtàn *Rẹ́rẹ́ Rún*. Morẹ́nikẹ́ jẹ obìnrin rere ni ọ̀ọ̀dẹ̀ ọkọ rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Láwúwo ko lówó lọ́wọ́, tí ó sì ń fa wàhálà lórí ọ̀rọ̀ ìdẹ̀rùn àwọn òṣìṣẹ́ síbẹ̀ Morẹ́nikẹ́ nífẹ̀ẹ́ Láwúwo ọkọ rẹ̀. Morẹ́nikẹ́ kò lóyún àárọ̀ dalẹ́ rí fún Láwúwo, ṣùgbọ́n ó gbàgbọ́ pé dídùn lọsàn yóò so. Tí a bá wo gbogbo ohun ti Morẹ́nikẹ́ là kọjá yìí, a ó rí i pé onísùúrù àti aláforítì ẹ̀dá-ìtàn ni Morẹ́nikẹ́. Morẹ́nikẹ́ gba owó tí àwọn òṣìṣẹ́ kó wá, ó lérò pé bi òun bá bá ọkọ òun sọ̀rọ̀ yóò gba owó náà ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kò rí bí ó ṣe rò ó. Lọ́nà àtimú ayé dẹrùn fún Morẹ́nikẹ́ àti ọkọ rẹ̀. Láwúwo ni ó ṣe kó owó àwọn òṣìṣẹ́ fún àwọn oníjìbìtì, èyí tí ó sì mú gbóògùn jẹ́ ni ìgbà tí ó mọ̀ pé jìbìtì ti lu òun. Morẹ́nikẹ́ kú lẹ́yìn tí ó ti gbóògùn jẹ, ó hàn gbangba pé òjìyà ẹ̀dá ládọjúdé ni Morẹ́nikẹ́.

**Onímògún**

Ọba ìlú Ìmògún àti olórí àwọn agbaniṣíṣẹ́ ni Onímògún jẹ́. Ìkà àti ọ̀dájú ènìyàn ni Onímògún jẹ́. Ìgbáyé gbádùn àwọn òṣìṣẹ́ kò jámọ́ nǹkànkan lójú Onímògún. Ó lòdí si ẹ̀tọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n bèèrè fún, gbogbo ọ̀nà sì ni Onímògún gbà láti rí i pé gbogbo àlá tí àwọn òṣìṣẹ́ lá parẹ́ mọ́ wọn nínú ni. Amúnisìn àti arẹ́nijẹ ẹ̀dá-ìtàn ni Onímògún jẹ́.

**Ìdòwú**

Ọ̀kan lára àwọn òṣìṣẹ́ ìlú Ìmògún ni Ìdòwú jẹ́. Agbẹ̀yìnbẹbọjẹ́ àti onímọ́dàrú ènìyàn ni. Nítorí àbẹ̀tẹ́lẹ̀ ti Ìdòwú ń rí gbà lọ́wọ́ àwọn ìjòyè ṣe ni ó gbé àwọn òṣìṣẹ́ ẹgbẹ́ rẹ̀ tà. Gbogbo ètò tàbí ìgbésẹ̀ tí àwọn òṣìṣẹ́ bá fẹ́ gbé ni Ìdòwú máa ń tú àṣírí rẹ̀ fún àwọn agbaniṣíṣẹ́. Ìdòwú yìí kan náà ni àwọn ìjòyè bẹ̀ lọ́wẹ̀ láti máà dá wàhálà sílẹ̀ láàrin àwọn òṣìṣẹ́. Ìkà àti ọ̀dájú ẹ̀dá-ìtàn ni Ìdòwú. Nítorí ki ìlépa àti àfojúsùn rẹ̀ láti di olórí àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ ní ìlú Ìmògún lè wá sí ìmúṣẹ ló ṣe dẹ àwọn oníjìbìtì sí Morẹ́nikẹ́ ìyàwó Láwúwo, èyí ló sì sọ Láwúwo di asínwín. Orúkọ ti òǹkọ̀wé fún Ìdòwú ni ipa lórí ìhùwàsí rẹ torí bí

Ìdòwú ṣe jẹ́ Èṣù lẹ́yin ìbejì bẹ́ẹ̀ ni Ìdòwú gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá-ìtàn nínú eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* jẹ́ Èṣù lẹ́yìn àwọn òṣìṣẹ́ àti Láwúwo.

### 4.1.4 Ìlò-Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*

Ọ̀nà tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí gbà lo èdè nínú eré-oníṣe yìí ni a máa jíròrò lé lórí ni abala tí a wà yìí. Àwọn ìlò èdè tí a ó sì máa sọ̀rọ̀ nípa wọn ni àfiwé tààrà, àkànlò èdè, ọ̀rọ̀ àyálò, èdè àdúgbò, ọ̀rọ̀ àtijọ́, orin àti òwe.

**Àfiwé Tààrà**

Òkédìjí ṣe àmúlò àfiwé tààrà nínú eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún*. Fún àpẹẹrẹ ní ìgbà tí àwọn òṣìṣẹ́ síwọ́ iṣẹ́ ti wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí palẹ̀mọ́, Ìdòwú wọlé bá wọn ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní bú àwọn òṣìṣẹ́, ó ń fi kùmọ̀ lè wọn kiri. Èyí ló mú Bọ́dúndé sọ pé:

> Bọ́dúndé: O ò fi i sílẹ̀! Yóò si máa ṣe kúbẹ̀kúbẹ̀ kiri ilé àwọn ìjòyè!
> Yóò máa fàyàpọ́nlẹ̀ bí aláàmù kiri! (o.i. 12)

Ìdòwú ni Bọ́dúndé fi wé aláàmù nítorí bí ó ṣe ń ṣe kúbẹ̀kúbẹ̀ lọ́dọ̀ àwọn ìjòyè. Bákan náà Akọ̀wé àgbà fi pákó tí àwọn òṣìṣẹ́ gé kalẹ̀ púúpùùpú wé àgédànù etí igi.

> Akọ̀wé àgbà: Iṣẹ́ wo ni wọ́n ṣe kalẹ̀ rẹpẹtẹ! Pákó tí a ní a ó fi ṣe ọ̀pá àjà, òun kọ́ ni àwọn ọ̀tá ajé gé kalẹ̀ púúpùùpú bí àgédànù etí igi wọ̀nyí! Kí la rí èyí fi ṣe mọ́?

**Àkànlò Èdè**

Àkànlò èdè náà kò gbẹ̀yìn lára àwọn ọnà èdè ti Òkédìjí lò láti ṣe àgbékalẹ̀ eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún*. Ní báyìí a ó wo àwọn àpẹẹrẹ àkànlò èdè náà. Nígbà tí Láwúwo ń bá àwọn òṣìṣẹ́ wí sí owó lọ́yà tí wọ́n dá jọ, ó ni:

> Láwúwo: À ń gé e yín lọ́wọ́, ẹ tún ń bọ òrùka! Bí mo ti ké tó, bí mo ti ń pàrọwà, ẹ tún fẹ́ máa ré èèsun dà sínú ibú! (o.i.28-29)

Láwùwo ni ó sọ gbólóhùn òkè yìí. Àwọn òṣìṣẹ́ ni Láwúwo ń bá sọ̀rọ̀. O ní kí wọ́n máṣe rẹ èèsún dà sínú ibú èyí túmọ̀ sí pé kí wọ́n máṣe kó owó wọn tí wọ́n jìyà láti rí fún àwọn tí wọ́n ti jẹ àjẹyọ́ àti àjẹṣẹ́kù. Àpẹẹrẹ àkànló èdè mìíràn tún jẹyọ nínú àrọwà tí Wúrọ̀ọ̀lá ń pa fún Láwùwo. Ó ni:

Wúràọlá: Dẹjú o rímú, Láwúwo. Dẹjú o rímú ọmọ aráyé ò féni fọ́rọ̀, àforí ẹni pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ dọwọ́ọ̀ rẹ̀. Àti pé kí o din fitafitaà rẹ kù nínú ọ̀rọ̀ ẹgbẹ́ títí tí ìjọ̀ngbọ̀n ilẹ̀ yìí yóò fi <u>kásẹ̀ nílẹ̀</u>. Fùlenge fùlenge rẹ yóò kàn máa bí àwọn ìjòyè nínú síi ni. <u>Fi ẹ̀jẹ̀ sínú kí ó máa tutọ́ funfun jáde</u>. Ṣebí Yorùbá ni ọ́! <u>Yorùbá dọ̀bálẹ̀, inú rẹ̀ lọ́ṣọ̀ọ́</u>! (o.i. 33)

Wúràọlá, ẹ̀gbọ́n Láwúwo ni ó gbà á níyànjú pé kí ó fi gbígbọ́ ṣaláìgbọ́ lórí ọ̀rọ̀ àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ torí inú àwọn ìjòyè kò dùn sí ipa tí ó ń kó lórí ọ̀rọ̀ àwọn òṣìṣẹ́, ṣùgbọ́n Láwúwo ké ọ̀rọ̀ Wúràọla dànù ni.

**Ọ̀rọ̀ Àyálò**

Ọ̀rọ̀ àyálò ni àwọn ọ̀rọ̀ tí a yá láti inú èdè kan sí òmíràn. A lè ya ọ̀rọ̀ láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì, Haúsá tàbí Lárúbáwá wọ inú èdè Yorùbá. Nínú eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* oríṣìíríṣìí èdè ni òǹkọ̀wé ti yá ọ̀rọ̀ wọ inú èdè Yorùbá tí ó fi ṣe àgbékalẹ̀ eré oníṣe náà. Bí àpẹrẹ:

<u>Yu sii</u>! Àwa náà sì ti múra dè wọ́n.

A ti dáwọ́o <u>lọ́yà</u>, a fọ̀rọ̀ lọ adáhunṣe,

a sì tún ṣètò bí a ó ti ṣe kóbì fún adájọ́ <u>kóòtù</u> (o.i. 28)

Adéníyì ni ó sọ gbólóhùn òkè yìí ní ìgbà tí ó ń jábọ̀ àwọn ìgbésẹ̀ tí àwọn òṣìṣẹ́ ti gbé ní ìgbà tí Láwúwo wà ní àtìmọ́lé. Àwọn ọ̀rọ̀ àyálò nínú gbólóhùn náà ni Yù síí, ti o túmọ̀ sí “Wò ó” nínú èdè Yorùbá. Lọ́yà tí ó túmọ̀ sí “agbejọ́rọ̀” àti kóòtù tí ó túmọ̀ sí “Ilé ẹjọ́! Yù síí, lọ́yà àti kóòtù jẹ́ ọ̀rọ̀ àyálò láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì. Fún àwọn àpẹẹrẹ mìíràn lórí ọ̀rọ̀ àyálò wo ojú ìwé, 6, 8 àti 35. Ẹnú Aláwodé tí ì ṣe ọ̀kan lára àwọn oníjìbìtì tó lu Morẹ́nikẹ́ ní èdè Háúsà ti jẹyọ. Ó ní:

Aláwodé: <u>Yáù waa</u>. <u>Síkèèná.</u> <u>Àíkí yákáárè.</u> <u>Màtá, kúdí</u> èyí, tirẹ̀ rẹ̀ <u>kwátákwátá</u> ó wà nínú èyí. <u>Dúkà</u> né tìrẹ, <u>Múwá tóbìlà dáyá, bíú ùkù, udu</u> (o.i. 79)

**Orin**

Orin àlọ́ ni Òkédìjí fi ṣíde tí ó sì tún fi parí eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún*. Ọ̀nà tí àwọn òṣìṣẹ́ ń gbà kọ orin àlọ́ yìí mú ìkáàánú àti ìmí ẹ̀dùn dání. Èyí fihàn pé orin arò ni orin náà jẹ́. Tí a bá wo orin tí àwọn òṣìṣẹ́ ń kọ yìí, ó ní ìtumọ̀ ń lá, ó sì ṣe wẹ́kú pẹ̀lú àhunpọ̀ ìtàn eré-oníṣe yìí.

> Èrò tí ń ròjééjé, òjééje
> Ẹ wí fún ìyáà mi, òjééje
> Ẹyin tó fi sílẹ̀, òjééje
> Lorogún sè fọ́mọ rẹ̀, òjééje
> Ewùrà tó kan bóbó, òjééje
> Èrò tí ń ròjééje, òjééje (o.i. 1)

Ìpàròko ni àwọn òṣìṣẹ́ ìlú Ìmògún fí orin tí wọ́n ń kọ yìí ṣe. Àwọn òṣìṣẹ́ ń kọ orin yìí láti jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún àwọn agbanisíṣẹ́ wọn pé ipò tí àwọn wà kò tẹ́ àwọn lọ́rùn àti pé àwọn agbanṣíṣẹ́ tí wọ́n fi wé orogún nínú orin àlọ́ tí wọ́n ń kọ yìí ń fí ẹ̀tọ̀ àwọn dun àwọn. Ibi pẹlẹbẹ náà ni ọ̀bẹ àwọn òṣìṣẹ́, padà fi lélẹ̀ lópin eré-oníṣe àpilẹ̀kọ afẹ̀hónú hàn *Rẹ́rẹ́ Rún* èyí ló sì jẹ́ kí àwọn òṣìṣẹ́ tún fi orin yìí kan náà parí èyí tí ó túmọ̀ sì pé wọn kò jàjàbọ́ lọ́wọ́ àwọn amúnisin wọn. Fún àpẹẹrẹ àwọn orin mìíràn, wo ojú ìwé 21, 81, 98, àti 110.

**Òwe**

Bí a bá wo *Rẹ́rẹ́ Run* fínnífínní, a óò rí i pé òwe ni Òkédìjí n ń fi eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* náà pa láti ìbẹ̀rẹ̀ dópin. A rí i pé oríṣìíríṣìí àrà ni Òkédìjí máa ń dá sí àmúlò òwe nínú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ rẹ̀. Àpẹẹrẹ:

| | |
|---|---|
| Onímògún: | <u>Ilá a máa ga ju olóko lọ</u>? |
| Arẹ̀sà: | Ó tì o, Kábíyèsí |
| Onímògún: | <u>Obìnrin tó bá gbọ́n bí ọkọ a máa rí èrè ọkọ jẹ</u>? |

Ọ̀nà ṣíṣe ìbéèrè ni Òkédìjí fi gbé àwọn òwe yìí kalẹ̀.

**5.0 Ìsọníṣókí**

Ìjàgbara lọ́wọ́ amúnisìn, àìkàsí, àyànmọ́ àti ìwà ìkà ni kókó mẹ́rin tí ó jẹyọ nínú eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún*. Ìpín mẹ́wàá ni Òkédìjí pín eré-oníṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* sí. Ìmògún àti ilé isẹ́ ìjọba ni ilẹ̀ Yorùbá àti jákèjádò Náíjíríà ni wọ́n sì ló gẹ́gk bí i ibùdó ìtàn gbogbogbòò.

Láwúwo ni olú ẹ̀dá-ìtàn bẹ́ẹ̀ ni ó sì tún jẹ́ akọni ẹ̀dá-ìtàn ládojúdé. Àfiwé tààrà, àkànlò èdè, ọ̀rọ̀ àyálò, èdè àdúgbò, ọ̀rọ̀ àtijọ́ orin àti òwe ni àwọn ọnà èdè ti Òkédìjí fi ṣàgbékalẹ̀ *Rẹ́rẹ́ Rún.*

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Jíròrò lórí àwọn fọ́nrán eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*
2. Ṣàlàyé kíkún lórí kókó ọ̀rọ̀ tí ó wà nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*.
3. Iṣẹ́ pàtàkì wo ni eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún* jẹ́ fún àwùjọ?

**Ìwé Ìtọ́kasí**

Òkédìjí, O. (1973) *Rẹ́rẹ́ Rún*. Ìbàdàn: Onibọnoje Press & Book Industries (Nig). Ltd.

**Ìpín Kẹrin: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayégún* tí Adéníyì Àkàngbé kọ**

**Àkóónú**

1.0 Ìfàárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayégún*: Adéníyì Àkàngbé
4.1.1 Ìsọníṣókí Eré-Onítàn *Ayégún*
4.1.2 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayégún*
4.1.3 Ìfìwàwẹ̀dá inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayégún*
4.1.4 Ìlò-Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayégún*
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfàárà

Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún* ti Adéníyì Àkàngbé kọ ni a ó gbéyẹ̀wò nínú ìpele ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àwọn fọ́nrán tí a ó sì máa jíròrò lé ni kókó ọ̀rọ̀, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò èdè.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- sọ kókó ọ̀rọ̀ tó jẹyọ nínú eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayégún*.
- jíròrò lórí ọ̀nà tí Àkàngbé gbà fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ nínú *Ayégún*.
- ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò èdè nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún*.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kókó pàtàkì wo ni ó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*?
2. Àwọn ọnà-èdè wo ni o rí fàyọ nínú *Rẹ́rẹ́ Rún*?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-Onìṣe *Ayégún* tí Adéníyì Àkàngbé kọ

### 4.1.1 Ìsọníṣókí Eré-Onítàn *Ayégún*

Olóyè Kòrọ̀lárí Ọláwúwo ló wọlé ìdìbò láti inú ẹgbẹ́ onírú pẹ̀lú àtìlẹ́yìn ọba Ayégún. Lẹ́yìn tí wọ́n ti kéde èsì ìdìbò gómìnà àti àwọn alaṣẹ rẹ dáwọ̀ọ́ ìdùnnú. Gómìnà ṣe ètò fún àwọn alátìlẹ́yìn rẹ, kò fẹ́ jẹ́ abaramóore jẹ. Kábìyésí ló fọwọ́ mú gbogbo iṣẹ́ kọngílá tó fi mọ́ fásitì méjì tí wọ́n fẹ́ kọ́. Jẹ́nẹ́rà ló gba kọngílá iṣẹ́ ojú ọ̀nà àti iṣẹ́ omi ẹrọ tí ó fi mọ́ pápá ìṣeré ń lá tí wọ́n ń gbèrò láti kọ́. Ọ̀gá ọlọ́pàá, Abárọ́tan Kòsọ̀fẹ́ ni ó wà nídìí àmójútó pápá ọkọ̀ òfurufú. Amòfin Aríjẹ Alápapín ni wọ́n sì fi ṣe asojú ilẹ̀ òkèèrè. Wọ́n dá fásitì sílẹ̀ sí ìlú gómìnà ní Ayélu àti ìlú Kọmísọ́nà Ọláníyọnú ní Ayékàn.

Gómìnà gba bílíọ̀nù méjì náírà owó ìdàgbásókè àwọn àgbẹ̀ tí wọ́n yá láti òkè òkun láti fi ṣe òkú bàbá bàbá rẹ̀ tó ti kú lọ́dún méjìlélọ́gbọ̀n sẹ́yìn. Ní ìgbà tí àwọn àgbẹ̀ gbọ́ pé owó ìrànwọ́ àwọn ti dé, wọ́n lọ béèrè lọ́wọ́ gómìnà ìdí tí àwọn kò fi tí ì rí owó náà gbà ṣùgbọ́n àbùkù àti ẹ̀tẹ́ ni wọ́n bá bọ̀. Ṣọlá àti Lọlá tí wọ́n jẹ́ olólùfẹ́ sọ̀rọ̀ nípa ìwà ọ̀jẹ̀lú tí àwọn olóṣèlú ń hù wọ́n jẹ́ kí ó di mímọ̀ pe nnkan kò dẹrùn fún àwọn mẹ̀kúnnù rara ṣùgbọ́n ní ti àwọn olóṣèlú Ayégún bámúbámú ni wọ́n yó, wọn kò mọ̀ pé ebí n pa ẹnìkankan. Lára ìmúrasílẹ̀ fún ìnáwó òkú bàbá bàbá gómìnà, gómìnà fún Ṣadé ọ̀rẹ́bìnrin rẹ ni ọ̀kẹ́ mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n náírà (N500,000.00). Níbi ìnáwó òkú bàbá bàbá gómìnà tó ti kú lọ́dún méjìlélọ́gbọ̀n sẹ́yìn ni wàhálà ti sẹ́yọ àwọn ará ìlú lòdì sí ìwà ìmọtaraẹni-nìkan tí àwọn olóṣẹ̀lú ń hù, wọ́n fi ẹ̀hónú wọn hàn nípa pípa àwọn ọ̀jẹ̀lú tí wọn n pe ara wọn ní òṣèlú yìí.

### 4.1.2 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayégún*

Olúborí kókó kan pàtàkì tí eré-oníṣe *Ayégún* dálé ni àṣìlò ipò, ìmọ̀taraẹni-nìkan àti ìrẹ́nijẹ. Ní kété tí gómìnà Kòrọ̀larí wọlé gẹ́gẹ́ bí gómìnà Ayégún ni òun àti àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ rẹ ti dáwọ̀ọ́ ìdùnnú tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣe ètò bí ayé yóò ṣe rọrùn síi fún ara wọn, tí wọn kò sì rántí àwọn ará ìlú tí wọ́n dìbò fún wọn mọ́. Lákọ̀ọ́kọ́ gómìnà ṣètò fún agbaṣẹ́ṣe láti yára kọ́ ilé ìgbàlódé tí àwọn aláṣẹ yóò máa lò kíákíá torí wọn kò le gbé ilé tí àwọn aláṣẹ àná gbé. Gbogbo ilé iṣẹ́ tí wọ́n pinnu láti dásílẹ̀ ni ó jẹ́ pe ìlú àwọn aláṣẹ wọ̀nyí ni

wọ́n dá wọn sí. Ilé iṣẹ́ epo pupa ni wọ́n gbé lọ sí Ayékan nitorí ìmọtaraẹni-nìkan wọn. Bẹ́ẹ̀ ni wọn tún da fásitì méjì sílẹ̀, ìkan ni ìlú Ayékan tí í ṣe ìlú Kọmísọ́nà Ọláníyọnu àti ìkejì sí ìlú gómìnà ni Ayélu.

Èyí nìkan kọ́, Kọmísọ́nà Ẹ̀dẹlọlá náà jà raburabu láti rí i pé wọ́n gbé ilé iṣẹ́ irin ríro lọ sí ìlú òun ní Ayéró. Bákan náà ni wọ́n sọ pé kí kábíyèsí Amáyégún fọwọ́ mú gbogbo Kọngílá tó jẹmọ́ ilé kíkọ́ pátá jákèjádò ilẹ̀ náà, tí ó fi mọ́ ilé ìwé Yunifásitì méjì tí wọ́n fẹ́ kọ́. Gbogbo iṣẹ́ ojú ọ̀nà àti iṣẹ́ omi ẹ̀rọ tí wọ́n fẹ́ fà sí tabúlé-tìletò pẹ̀lú pápá ìṣeré nlá tí wọ́n fẹ́ kọ́ ni wọn fà lé Jẹ́nẹ́rà lọ́wọ́. Ọ̀gbẹ́ni Abárọ́tan Kòsọ̀fẹ́ tí í ṣe ọ̀gá ọlọ́pàá ni wọ́n fa àmójútó pápá ọkọ̀ òfurufú tí wọ́n fẹ́ kọ́ lé lọ́wọ́. Amòfin Aríjẹ Alápapin tí í ṣe ọ̀gá àgbà ìgbìmọ̀ olùṣètò ìdìbò ni wọ́n sọ di aṣojú ilẹ̀ òkèèrè. Ẹ̀mí ìrẹ́nijẹ tí ó wà nínú àwọn olórí àti olóṣèlú ni orílẹ̀ èdè wa tún fẹsè múlẹ̀ ní ìgbà tí gómìnà Kọ̀rọ́lárí gba bílíọ̀nù méjì àbọ̀ owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ ní bánkì láti fi sin òkú bàbá bàbá gómìnà tí ó ti kú ní ọdún méjìlélọ́gbọ̀n sẹ́yìn.

Gómìnà Kọ̀rọ́lárí kò tílẹ̀ dàá rò lẹ́ẹ̀mejì tí ó tún fi bèèrè fún owó oṣù kan àwọn tíṣà ki owó lè tó, kí ó tún sẹ́kù níbi òkú bàbá bàbá rẹ̀ tó fẹ́ ṣe. Torí òkú tí gómìnà fẹ́ ṣe yìí gan-an ni Fọláwẹwọ́ aya gómìnà náà ṣe bèèrè fún mílíọ̀nù mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n láti ra àwọn ohun ọ̀ṣọ́ tí yóò lò lọ́jọ́ ayẹyẹ òkú náà. Ṣadé, ọ̀rẹ́bìnrin gómìnà pàápàá gbọ ọ̀kẹ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ́n náírà fún ìmúrasílẹ̀ tirẹ̀ pẹ̀lú. Bí gómìnà Kọ̀rọ́lárí ṣe ń bù jẹ bù dànù yìí fi hàn gẹ́gẹ́ bí olórí tí kò ní àáánú àwọn ará ìlú tí ó gbé e dé ipò lọ́kàn. Òǹkọ̀wé fi gómìnà Kọ̀rọ́lárí pàrokò irúfẹ́ àwọn olórí tí a ní láwùjọ wa ni. Gbogbo ìlàkàkà àwọn ẹgbẹ́ àgbẹ̀ láti jẹ́ kí gómìnà sọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí owó ìránlọ́wọ́ àwọn àgbẹ̀ ti wọ́n gbọ́ pé ó ti dé láti òkè-òkun pàbó ló jásí, àbùkù àti ẹ̀tẹ́ ni àwọn àgbẹ̀ bá kúrò lọ́dọ̀ gómìnà.

**Ìfẹ̀dásẹ̀fẹ̀**

Ìfẹ̀dásẹ̀fẹ̀ náà tún jẹ Àkàngbé lógún nínú eré yìí. Bí a ṣe rí ìfìṣèlúṣẹ̀fẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni ìfẹ̀sìnsẹ̀fẹ̀ jẹ jáde. Bí àpẹẹrẹ, ìwà ìbàjẹ́ tí ó kún ọwọ́ àwọn ọ̀jẹ̀lú àwùjọ tó ń pé ara wọn ní òṣèlú ní àpẹẹrẹ, tí a mẹ́nu bà ṣaájú tọ́ka sí. Nínú *Ayégún* a rí àrídájú pé kì í ṣe àwọn òṣèlú ìwòyí nìkan ló ń hu ìwà ìbàjẹ́, àwọn òṣèlú ìbílẹ̀ náà kò gbẹ́yìn. Ìdí nìyí tí a fi ri orí adé, ìyẹn Kábíyèsí Ọba Adékúnlé tí òun náà darapọ̀ láti rẹ́ mẹ̀kúnnù jẹ. Àlùfáà, ọ̀mọ̀wé

Ọbadájà ni òǹkọ̀wé sì lò láti bu ẹnu àtẹ lu àwọn olórí ẹ̀sìn tó ń pẹ̀lú ọ̀bọ jẹko nípa dídarapọ̀ mọ àwọn olóṣèlú, tí wọ́n sì ń fi àjọsepọ̀ wọn pagi dínà ìtẹ̀síwájú lórílẹ̀-èdè wọn. Gbogbo ìwà ìrẹ́nijẹ àti bámúbámú la yó tí gómìnà àti àwọn aláṣẹ rẹ̀ ń hù ló bí àwọn ará ìlú nínú tí wọ́n sì dá sẹ̀ríà ikú fún àwọn olórí ní ìlú *Ayégún*, lọ́nà àti jẹ́ kí ayé gún régé fún àwọn mẹ̀kúnnù.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún* bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìpàjùbà, àgbàlagbà akéwì kan ni ó fi aṣọ pakájà, ó mú ọ̀pá ìtìlẹ̀ lọ́wọ́ ó sì dé fìlà abetí ajá. Nínú ewì tí ònkọ̀wé fi pàjùbà ni kókó tí ìwé eré oníṣe *Ayégún* dá lé ti jẹyọ. Nínú ewì yìí ni òǹkọ̀wé ti gún àwọn òńkàwé ni kẹ́ṣẹ́ nípa àfojúsùn ìwé oníṣe àpilẹ̀ko *Ayégún*. Òǹkọ̀wé jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé àkùkọ gàgàrà àwọn aṣíwájú kò fẹ́ kí tàwọn ọmọlẹ́yìn kọ, àtipé bámúbámú làwọn olórí yó, wọn kò mọ̀ pébi ń pọmọ ẹnìkọ̀ọ̀kan. Ewì yìí sàfihàn àwọn olórí bí onímọ̀taraẹni-nìkan. Lẹ́yìn ewì àgbàlagbà akéwì tí òǹkọ̀wé fi pàjùbà, orin lóríṣìíríṣìí ló tún jẹyọ. Bí àwọn olórí àti àwọn olówó láàrin ìlú *Ayégún* ṣe ń kọrin ìdùnnú fún yíyege gómìnà Kòrọ́lárí tí ó sì di gómìnà *Ayégún* bẹ́ẹ̀ ni àwọn mẹ̀kúnnù pẹ̀lú ń kọ orin tiwọn pẹ̀lú ìmí ẹ̀dùn pé ki Èdùmarè ko fi iṣẹ́ yín àwọn náà káyé lè rọrùn fún wọn.

Ìran mẹ́sàn-án ni òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀ko *Ayégún* pín in sí. Ìran kìn-ín-ní wáyé ní ilé ìgbìmọ̀ aláṣẹ ní ìlú Ayégún. Ní ìgbà tí ìran kejì àti ìkẹta wáyé ní ilé gómìnà Kòrọ́lárí. Ilé Adéoyè ni ìran kẹrin ti ṣẹlẹ̀. Ìran karùn ún wáyé ní ilé Ṣọlá. Ilé gómìnà Kòrọ́lárí ni ìran kẹfà àti ìkeje tún ti wáyé. Ìran kẹjọ wáyé ní ilé Ṣọlá. Ìran kẹsàn-án tí ṣe òpin eré-onítàn náà wáyé ní ibi ìnáwó òkú bàbá bàbá gómìnà.

Ní ìran kìn-ín-ní gómìnà Kòrọ́lárí àti àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ rẹ̀ nínú ilé ìgbìmọ̀ aláṣẹ Ayégún fi ìdùnnú wọn hàn fún àṣeyọrí tí wọ́n ṣe nínú ìdìbò tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ parí ní Ayégún. Pẹ̀lú ijó àti orin ni àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ fi ń kí ara wọn kú oríire.

Lẹ́yìn tí wọ́n ki ara wọn kú oríire tán, gómìnà pinnu láti mú ìgbésí ayé dẹrùn fún àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ rẹ, gẹ́gẹ́ bí gómìnà ti sọ "kúuṣẹ́ ní mórí iṣẹ́ ya". Gómìnà Kòrọ́lárí ṣètò owó oṣù tí wọn yóò máa gbà lóṣooṣù. Ọ̀kẹ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n ni owó oṣù gómìnà jẹ́, àwọn kọmíṣọ́nnà yóò sì máa gba ogún ọ̀kẹ́ náírà lóṣù, nígbà tí àwọn akọ̀wé yóò máa gba ọ̀kẹ́

mẹ́ẹ̀ẹ́dógún náírà gẹ́gẹ́ bí owó oṣù tiwọn náà. Síwájú síi, gbogbo ọmọ aláṣẹ kọ̀ọ̀kan ni gómìnà pèsè ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ titun tí a mọ̀ sí fólífò fún. Gbogbo àwọn iṣẹ́ àgbàṣe pátá àti àwọn ilé-iṣẹ́ tí wọ́n pinnu láti dá sílẹ̀ ni àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ tún pín mọ ara wọn lọ́wọ́ ní ìran kìnínní.

Nínú ìran kejì ni Kábíyèsí àti Jẹ́nẹ́rà ti wá kí gómìnà Kòrọ́lárí kú oríire. Ọtí olówó iyebíye tí ó wá láti ilẹ̀ òkèère ni gómìnà fi ṣe àlejò wọn. Kábíyèsí jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún gómìnà pé ènìyàn kì í ni irú àǹfààní tí ó ní lẹ́ẹ̀mejì fún ìdí èyí ó gbọdọ̀ pín in dáadáa ti ibi tó lọ́ràá yóò ṣe kan gbogbo àwọn tó ṣe wàhálà ọ̀rọ̀ ìbò rẹ̀ tí kò bá fẹ́ di aláìmoore. Gómìnà fi yé kábíyèsí pé ò ń kì í ṣe òpè ènìyàn tí kò mẹ̀tọ́, ó ni kí kábíyèsí Amáyégún fọwọ́ mú gbogbo kọngilá to jẹmọ́ ilé kíkọ́ pátá jákèjádò ilẹ̀ wọn, bẹ̀ẹ́ ni ó gbé gbogbo iṣẹ́ ojú ọ̀nà àti iṣẹ́ omi ẹ̀rọ tí ó fi mọ́ pápá ìṣeré nlá tí wọn fẹ́ kọ́ lé Jẹ́nẹ́rà lọ́wọ́. Inú Kábíyèsí àti Jẹ́nẹ́rà sì dùn sí ètò yìí. Orin ìkìlọ̀ fáwọn aláṣẹ ni ònkọ̀wé fi kádìí ìran kejì. Gómìnà Kọ̀rọ́lárí bá Máníjà Bánkì sọ̀rọ̀ pé kí ó fi bílíọ̀nù méjì owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ ránṣẹ́ sí òun láti lò ó fún ìnáwó òkú tó fẹ́ ṣe

Nínú ìran kẹta ni Fọláwẹwọ́, ìyàwó gómìnà ti bèèrè fún mìlìọ̀nù mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n fún ìpèsè àwọn ọ̀ṣọ́ tí ó fẹ́ lò lọ́jọ òkú tí wọ́n fẹ́ ṣe. Gómìnà korò ojú si iye tí ìyàwó rẹ̀ bèèrè fún ṣùgbọ́n níkẹyìn ó gbà láti fún un lówó náà. Fọláwẹwọ́ tún ran ọkọ rẹ̀ létí láti tètè parí ilé ìtaja tí ó fẹ́ kọ fún un, ó mú mọ̀ràn wá pé àwọn lè gba owó oṣù kan àwọn Tíṣà láti yanjú gbogbo ohun tí wọ́n fẹ́ ṣe. Ní ìgbà tí Fọláwẹwọ́ rí ipò ọlá ti òun àti gómìnà ọkọ rẹ̀ wà àti bí ìfà rẹpẹtẹ ṣe sàba sí sàkání wọn, orin ayọ̀ fún ipò ọlá ló gbẹnu rẹ̀ kan òun àti ọkọ rẹ̀ sì mújó jó. Orin ìkìlọ̀ ni òǹkọ̀wé fi parí ìran kẹta.

Ní ìran kẹrin Adéoyè ń kọ orin ìwérénde níwájú ìta rẹ̀ àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ méjì Ifátádé àti Ọpẹ́àgbè wá bẹ̀ ẹ́ wo. Nínú ìran yìí kan náà ni a ti gbọ́ ìròyìn ẹyìn ìtàgé pé Àjíún, ìyàwó Adéoyè ti kó kúrò nílé nítorí aṣọ ẹbí. Àwọn ọ̀rẹ́ Adéoyè fẹnu kò láti lọ bẹ ìyàwó Adéoyè pé kí ó padà wálé ni ọjọ́ ọjà jàkúta. Wọ́n tún sọ̀rọ̀ nipa owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ tí ìwé ìròyìn gbé pé ó ti dé ṣùgbọ́n tí kò tẹ àwọn àgbẹ̀ lọ́wọ́. Àwọn aṣójú àgbẹ̀ pinnu láti bèèrè lọ́wọ́ gómìnà ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí owó náà. Adébóyè ọmọ Adéoyè náà ní wọ́n lé wálé láti ilé ìwé fún owó ilè ìwé rẹ̀ tí kò rí san. Ṣọlá àti ọ̀rẹ́bìnrin rẹ̀, Lọlá sọ̀rọ̀ lórí ọ̀wọ́ngógó ọjà tí ó gbòdekan nílùú àti bí àwọn ará ìlú ṣe ń kérora.

Ní ìran karùn-ún. Ṣọlá àti Lọlá fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ ní orí karùn-ún pe àìlè tọ́jú àwọn erè oko lásìkò ọ̀pọ̀ wọn, ọ̀nà bíbàjẹ́, ọ̀wọ́ngógó àwọn ẹ̀yà ará ọkọ̀ àti owó gọbọi tí ìjọba ń gbà lórí àwọn ọjà òkè òkun ní bodè ló ń fa ọ̀wọ́ngógó ọjà. Òǹkọ̀wé jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé àìnífẹ̀ẹ́ ìlú àti ìmọtara-ẹni-nìkan tí ó ǹ bá àwọn olórí tàbí adarí wa jà ló ń mú kí àwọn ènìyàn máa mòòkùn nínú ìṣòro. Ṣadé, ọ̀rẹ́bìnrin gómìnà, nínú ìran kẹfà wá rí i. Ṣadé àti gómìnà sì fi ìfẹ́ hàn sí ara wọn. orin ìfẹ́ tún gbòdekan nínú ìran kẹfà. Bákan náà ni gómìnà fún Ṣadé ní ọ̀kẹ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n náírà fún ìmúrasílẹ̀ òkú tí wọ́n fẹ́ ṣe. Àwọn aṣojú ẹgbẹ́ àgbẹ̀ bèèrè lọ́wọ́ gómìnà nípa owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ èyí tí ìwé ìròyìn gbé pé ó ti dé. Àbùkù àti ẹ̀tẹ́ ni àwọn aṣojú àgbẹ̀ bá kúrò lọ́dọ̀ gómìnà.

Ìran keje ni gómìnà Kòrọ̀lárí ti bèèrè fún owó oṣù kan àwọn tíṣà láti fi kún owó tó fẹ́ fi ṣe òkú bàbá bàbá rẹ̀. Mánîjà kò sì kọ̀rọ̀ sí gómìnà lẹ́nu. Orin ìfẹ́ ni òǹkọ̀wé fi bẹ̀rẹ̀ ìran kẹjọ. Ṣọlá àti Lọlá ọ̀rẹ́bìnrin rẹ̀ tàkùrọ̀sọ̀ nípa ìrọ́kẹ̀kẹ̀ òkú bàbá bàbá gómìnà tí ó ti kú lọ́dún méjìlélógún sẹ́yìn. Lójú Ṣọlá àti Lọlá ọ̀rẹ́bìnrin rẹ̀ gbogbo ìpálẹ̀mọ́ ti gómìnà àti ìyàwó rẹ̀, Fọláwẹwọ̀ ńṣe jẹ́ ìfowóṣòfò. Àwọn olólùfẹ́ méjéèjì yìí gbàgbọ́ pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pàápàá máa ń dàrapọ̀ mọ àwọn wọ̀bìà ti wọ́n jẹ́ olórí yìí ní kété tí wọ́n bá ti jáde ilé ìwé. Èyí túmọ̀ sí pé a kò lè ṣe bẹ́ẹ̀ fi ìgbẹ́kẹ̀lé wa sínú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí mèsáyà ọjọ́ ọ̀la. Ibi ìnáwó òkú bàbá bàbá gómìnà ni ìran kẹsàn-án ti wáyé. Oríṣìíríṣìí orin ìyìn àti àyọ ni ó gba afẹ́fẹ́ kan nínú ìran kẹsàn-án. Kábíyèsí ló kí àwọn ènìyàn káàbọ̀ sí ibi ayẹyẹ òkú náà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ oúnjẹ àti ohun mímu ni àwọn ènìyàn fi ń gbádùn ara wọn. Ìgbésẹ̀ gómìnà Kòrọ̀lárí láti ṣe ayẹyẹ òkú bàbá bàbá rẹ̀ kó dùn mọ́ àwọn ara Ayégún nínú, èyí ló sì mú àwọn mẹ̀kúnnù parapọ̀ tí wọ́n sì gba ẹ̀mi àwọn òjẹ̀lú wọ̀nyí kí ara lè tu tilé toko. Orin ìkìlọ̀ ni ònkọ̀wé fi parí ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún*.

**Ibùdó-Ìtàn**

Ibùdó-ìtàn gbogbogbòò fún eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún* ni ìlú Ayégún. Pẹ̀lú gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tó wáyé nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún*, ó hàn gbangba pé òǹkọ̀wé fi ìwé eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí pàrokò ayé ìjẹkújẹ àti ìwà ìmọtara-ẹni-nìkan tí àwọn olórí wa ń hù ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ni. Àwọn ibùdó-ìtàn pàtó nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún* ni Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣòfin, Ilé gómìnà, ilé Adéoyè, ilé Ṣọlá àti ibi ìnáwó òkú.

### 4.1.3 Ẹ̀dá-ìtàn àti Ìfìwàwẹ̀dá inú Eré-Onítàn Àpilẹ̀kọ *Ayégún*

**Gómìnà Kòrọ̀lárí**

Òun ni olú ẹ̀dá-ìtàn *Ayégún*. O tún jẹ́ gómìnà tuntun tí ó wọlé nínú ẹgbẹ́ onírú nínú ètò ìdìbò tí ó sẹ̀sẹ̀ kásẹ̀ nílẹ̀ ní ìlú Ayégún. Oníjẹkújẹ àti aláìláàánú ènìyàn ni Kòrọ̀lárí jẹ́. Ní kété tí ó gorí àléfà gẹ́gẹ́ bí gómìnà Ayégún ni ó bẹ̀rẹ̀ sí pínpín gbogbo ọrọ̀ ìlú fún àwọn tí ó bá á ṣe màgòmágó ìbò tí ó fi di gómìnà. Èyí nìkan kọ́, gómìnà Kòlọ̀lárí tún ṣe òkú bàbá bàbá rẹ̀ tí ó ti kú ní ọdún méjìlélọ́gbọ̀n ṣẹ́yìn, ayé gbọ́ ọ̀run sì mọ̀, gbogbo ohun èlò ti gómìnà Kòrọ̀lárí lò fún ayẹyẹ òkú yìí àti òkè òkun lo ti kó wọn wá. Pabanbarì rẹ̀ ni pé owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ tí wọ́n yá láti òkè òkun àti owó oṣù kan àwọn tíṣà ni gómìnà Kòrọ̀lárí ń lò fún gbogbo ìmúrasílẹ̀ tí ó ṣe fún ti òkú náà. Ìkà àti ọ̀dájú ẹ̀dá-ìtàn ni gómìnà Kòrọ̀lárí jẹ́, bámúbámú ló yó kò sì rántí pé ebi ń pa àwọn ara ìlú rárá. Àbùjẹ-bùdànù gómìnà Kòrọ̀lárí pọ̀ to bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ tí ó fi fún ọ̀rẹ́bìnrin rẹ̀, Ṣadé ni ọ̀kẹ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n náírà láti ṣe ìmúràsílẹ̀ òkú ti wọ́n fẹ́ ṣe. Orúkọ alárokò tí ònǹkọ̀wé fún gómìnà Kòrọ̀lárí nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún* ní ipa lórí ìṣẹṣí àti ìhùwàsí rẹ̀. Nítòóótọ́, ọmọ ojú Kòrọ̀lárí tí ń sọ ọmọ rẹ̀ ní Ọláníyọnu ni gómìnà Kòlọ̀lárí jẹ́. Gbogbo ìwà tí gómìnà hù nínú eré-oníṣe àpilẹ̀ko *Ayégún* ló fi hàn gẹ́gẹ́ bí àpà àti ọ̀dájú ẹ̀dá-ìtàn.

**Fọláwẹwọ̀**

Ìyàwó gómìnà Kòrọ̀lárí ni Fọláwẹwọ̀ jẹ́. Ìyàwó burúkú tí ọ̀ṣọ́ àti afẹ́ ayé tí gba ọkàn rẹ̀ ni Fọláwẹwọ̀. Ìmọ̀ràn burúkú ni Fọláwẹwọ̀ máa ń gbà gómìnà Kòrọ̀lárí tí ó jẹ́ ọkọ rẹ̀. Fọláwẹwọ̀ ni ó ki gómìnà láyà láti fi owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ ṣe òkú bẹ́ẹ̀ ni ó tún gbà ọkọ rẹ̀ nímọ̀ràn láti gba owó oṣù kan àwọn tíṣà fún òkú tí wọ́n fẹ́ ṣe. Gbogbo ìgbéṣẹ̀ Fọláwẹwọ̀ yìí fi hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀dájú àti ìkà ẹ̀dá-ìtàn tí ó máa n ro ti ara rẹ̀ nìkan. Mílíọ̀nù mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n ni Fọláwẹwọ̀ bèèrè fún lọ́wọ́ gómìnà ọkọ rẹ̀ láti fi ra àwọn ohun ọ̀ṣọ́ ti yóò ló fún òkú bàbá bàbá gómìnà tí wọ́n fẹ́ ṣe.

Àrokò ni òǹkọ̀wé fí orúkọ aya gómìnà pa. Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, ṣe ni Fọláwẹwọ̀ ń fi ọlá jẹyọ. Gbogbo ìrònú Fọláwẹwọ̀ kò ju bí yóò ṣe ná owó ìlú èyí ti gómìnà ọkọ rẹ̀ ń ṣe

ìjọba lé lórí. Ìwà àti ìṣe Fọláwẹwọ̀ ní ṣe pẹ̀lú orúkọ ti òǹkọ̀wé fún un nínú eré-oníṣe *Ayégún*.

**Kábíyèsí**

Ọba Adékúnlé Báyéwùmí Afowoṣefújà ni ọba ìlú Ayégún. Gẹ́gẹ́ bí àṣà Yorùbá ti là á kalẹ̀ Kábíyèsí yẹ kó jẹ́ ẹni àyẹ́sí àti ẹni ọ̀wọ̀. Bẹ́ẹ̀ ni ó tún yẹ kò jẹ́ bàbá fún gbogbo ìlú ṣùgbọ́n nítorí àti rówó ṣe fújà kábíyèsí tọwọ́ bọ ọ̀rọ̀ òṣèlú, òun ló sì ṣe ọ̀nà bí ẹgbẹ onírú ṣe borí nínú ìbò tí wọ́n dì tán tí gómìnà Kòrọ̀lárí sì di aláṣẹ.

Lẹ́yìn ti gómìnà ti wọlé tán, Kábíyèsí Amáyégún rán gómìnà létí pé ó gbọdọ̀ dúpẹ́ oore tí àwọn ṣe fún un. Torí ẹni tí a ṣe lóore tí kò dúpẹ́ bí ọlọ́sà kó ni lẹ́rù lọ ni. Kábíyèsí Amáyégún ni wọ́n ní kó fọwọ́ mú gbogbo kọngilá tó jẹmọ́ ilé kíkọ́ jákèjádò Ayégún, tí ó fi mọ́ ilé ìwé Yunifásitì méjì tí wọ́n fẹ́ kọ́, ilé ìwé lóríṣìíríṣìí, ilé ìtura àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Inú Kábíyèsí sì dùn gan-an sí ètò tí gómìnà ṣe fún un yìí. Kábíyèsí Amáyégún wà lára àwọn ọ̀jẹ̀lú tí àwọn ará ìlú pa ní ibi ìnáwó òkú bàbá bàbá gómìnà.

**Jẹ́nẹ́rà**

Ọ̀gágun Àlàbí Alápamọ́pamọ̀ tí ó jẹ́ ọ̀gá ológun náà wà lára àwọn tí wọ́n ṣe àtìlẹyìn fún gómìnà Kòrọ̀lárí láti dé orí àléèfà. Lọ́nà àti fi ìmoore hàn sí Jẹ́nẹ́rà, gómìnà Kòrọ̀lárí gbé gbogbo iṣẹ́ ojú ọ̀nà àti iṣẹ́ omi ẹrọ tí wọ́n fẹ́ fà sí tabúlé-tìletò lé e lọ́wọ́ bẹ́ẹ̀ ni gómìnà tún ní kó fọwọ́ mú pápá ìṣeré ńlá tí wọ́n fẹ́ kọ́. Jẹ́nẹ́rà náà wà lára àwọn ọ̀bàyéjẹ́ tí àwọn ará ìlú dẹ́mìí wọ́n légbodò nítorí ìjẹkújẹ wọn.

**Mánίjà Báńkì**

Ọ̀mọ̀wé Babalejẹ́ Àjọjẹ ni mánίjà Bánkì Ayégún. Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, àjọjẹ ni Mánίjà ń ṣe pẹ̀lú gómìnà Kòrọ̀lárí. Mánίjà ni ó kó bílíọ̀nù méjì abọ owó ìdàgbàsókè àwọn àgbẹ̀ tí wọ́n yá lókè òkun fún gómìnà bẹ́ẹ̀ ni ó tún yọ̀ǹda owó oṣù kan àwọn tíṣà fún gómìnà láti fi kún owó òkú tí ó fẹ́ ṣe. Owó tí gómìnà ń fún mánίjà ni ó ṣe ń ṣe gbogbo ohun tí ó ń ṣe. Nítòóótọ́, àjọjẹ àti àpapín ni gómìnà àti mánίjà báńkì ń ṣe.

**Àlùfáà**

Ọbadáyà Mobọ́lọ́rundúró Owónikókó tí ó jẹ́ òjíṣẹ́ Ọlọ́run, tí ó sì ní ojúṣe láti ṣe fún àwọn àgùntàn tí ó ń darí ni ó tojúbọ ọ̀rọ̀ òṣèlú nítorí owó tí ó ń rígbà níbẹ̀. Ní ti àlùfáà, owó ni o ṣe kókó, iṣẹ́ Ọlọ́run kò jẹ ẹ́ lógún bẹ́ẹ̀ ni ó ń ṣe àsìlò ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ti o sì ń ti ipasẹ̀ èyí ṣi ọ̀pọ̀lọpọ̀ lọ́nà. Ayédèrú àlùfáà ni Owónikókó, dípò agbo àgùntàn tí ó yẹ kí ó bójútó, ikùn rẹ̀ àti owó ni ó ṣe kókó tí ó sì jẹ ẹ́ lógún.

**Ṣadé Ọlọ́runṣògo**

Ọ̀rẹ́bìnrin gómìnà Kòrọ́lárí ni Ṣadé jẹ́. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà sì ni gómìnà Kòrọ́lárí máa n fún Ṣadé lówó láti gbádùn ara rẹ̀ àti láti ra àwọn ohun ọ̀sọ́. Inú Ṣadé sì máa ń dùn pé òun rí owó gbà lọ́wọ́ gómìnà. Ọ̀kẹ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n náírà ni gómìnà Kòrọ́lárí fún Ṣadé láti fi ṣe ìmúrasílẹ̀ fún òkú tí gómìnà fẹ́ ṣe. Ṣadé yìí kan náà ni gómìnà fi sí ìdí ètò gbogbo tó jẹ mọ́ ti àwọn omidan tí yóò wá síbi ayẹyẹ òkú ti gómìnà fẹ́ ṣe. Olè àti olójúkòkòrò obìnrin ni Ṣadé. Kò dúró sí sùúrùlérè Ọlọ́runsógo ló wà. Àwọn ọlọ́lá ló ń ta sí. Ojúkòkòrò Ṣadé ló mú un fi ikú ṣe ìfà jẹ ni ibi ìnáwó òkú bàbá bàbá Gómìnà Kòrọ́lárí.

### 4.1.4 Ìlò-Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayégún*

**Ewì**

Ewì ni òǹkọ̀wé lò láti ṣíde àti láti pàjùbà eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún*. Nínú ewì ti òǹkọ̀wé fi ṣíde eré-onítàn ni ó ti pàsamọ̀ ohun tí àwọn òǹkàwé yóò bá pàdé nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún*. Ewì náà lọ báyìí:

> Ayé dojúrú poo, ayé polúkúmuṣu
> Ayé ò gún gẹ́gẹ́ mọ́, ayé dayé wàhálà
> Mo wolé ayé suu, ilé ayé súmi
> Mo ròrò ayé sàà, ọ̀rọ̀ ayé sòmí ní rírò
> Àkùkọ gàgàrà ò fẹ́ kí kékeré kọ
> Àwọn tó ti mókè ò fẹ́tẹ̀síwájú àwọn ọmọlẹ́yìn
> Bámúbámú làwá yó
> Àwa ò mọ̀ pébi n pọmọ ẹnìkọ́ọ̀kan
> Àwa ti gòkè odò káfárá ó tó já
> Ẹ̀yin tokú ẹ múra
> Lorin tó gbẹnu gbogbo olórí wa (*Ayégún* o.i. 1)

Ò hàn gbangba pé ìwà ìmọtara-ẹni-nìkan àti ayé ìjẹkújẹ tí àwọn olórí ń jẹ láì rántí àwọn mẹ̀kúnnù àti ará ìlú tí ó gbé wọn dé ipò ni akéwì ń kọminú lé lórí. Ewì yìí mú òǹkàwé lọ́kàn gidi, ó sì ṣe iṣẹ́ ti òǹkọ̀wé fẹ́ kí ó ṣe ni ọ̀gangan ipò tí ó ti jẹyọ.

**Orin**

Òǹkọ̀wé eré-oníṣe àpilẹ̀ko *Ayégún* ṣe àmúlò orin lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú eré-oníṣe náà. Orin ni òǹkọ̀wé ṣe àmúlò nínú *Ayégún* gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti fi èrò ẹni hàn fún aráyé tàbí láti fi ẹ̀hónú hàn lórí ìwà tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ kan tó ṣẹ̀ láwùjọ ṣùgbọ́n tí kò mú inú ẹni dùn. Àpẹẹrẹ orin;

> Gómìnà Kòrọ́lárí wa o láti rẹ sílẹ̀ ko gbọ́ o gómìnà oníjẹkújẹ o tẹ́tí rẹ̀ sílẹ̀ ko gbọ́rọ̀ ìwà ìparun kò dára, àpamọ́pamọ̀ kò dára. Ìwà ìkà ni ká kówó mì ká máa febi pàlú o Èèbù ìkà tíwọ bá gbìn gbọdọ̀ hu fún ọ lọ́la (*Ayégún* o.i. 27)

Orin òkè yìí jẹ́ orin ìkìlọ̀ fún gómìnà Kọ̀rọ̀lárí pé ki o ṣíwọ́ owó ìlú níná lọ́nà tí kò tọ̀nà èyì tí ó ń mú kí ebi pa àwọn ará ìlú. Wọ́n fẹ́ ki gómìnà rántí wí pé àṣegbé kò sí àti pé àṣepamọ́ ló wà.

**Òwe**

Òwe náà tún jẹyọ lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀ko *Ayégún*. Fún àpẹẹrẹ lẹ́yìn tí àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ ilẹ̀ Ayégún ti dáwọ̀ọ́ ìdùnnú tán. Kọmísánà Ọláníyọnu pòwe pé “àárọ̀ lọjọ́ iṣẹ́ là á fi í ṣe” (*Ayégún* o.i.10) èyí túmọ̀ sí pé lẹ́yìn tí wọ́n ti yayọ̀ ìdùnnú tán, ohun tí ó kan ni bí wọn yóò ṣe pín àwọn iṣẹ́ àgbàṣe tó wà nílẹ̀. Fún àpẹẹrẹ àwọn òwe mìíràn, wo ojú ìwé 12, 14, 18, 19, 21.

**Ọfọ̀**

Òǹkọ̀wé tún ṣàmúlò ọfọ̀ láti fi ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nínú agbára tí ọfọ̀ ní. Bí àpẹẹrẹ lẹ́yìn tí àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ Ayégún yayọ̀ ìdùnnú pẹ̀lú orin àti ijó tán gómìnà pé ọfọ̀ báyìí:

> Àṣetì kì í bọ́jọ́
> Áṣetì kì í bóòrùn
> Àṣeyè lalákan í ṣepo (o.i. 9)

Ọfọ̀ òkè yìí jẹ ọfọ̀ ìwúre fún àwọn ìgbìmọ̀ aláṣẹ Ayégún pé àṣeyè àti àṣeyege ni wọn yóò ṣe iṣẹ́ ìlú tó wà níwájú wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Ìjàgbara lọ́wọ́ amúnisìn ni ìwé *Ayégún* dá lérí, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn kókó inú rẹ̀. A sí tún sọ nípa àwọn ọ̀nà tí ìjọba ń gbà rẹ́ àwọn ará ìlú jẹ. A kò gbágbé láti wo àwọn ìlò èdè bíi: àfiwé tààrà, àkànlò èdè, orin àti òwe ti Àkàngbé lò láti ṣàgbékalẹ̀ ìwé *Ayégún*.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Sọ kókó ọ̀rọ̀ tó jẹyọ nínú eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayégún*.
2. Jíròrò lórí ọ̀nà tí Àkàngbé gbà fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ nínú *Ayégún*.
3. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò èdè nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayégún*.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adéjùmọ̀ A. (2006) Yorùbá Drama II. Ìbàdàn: Ibadan Distance Learning Centre, University of Ibadan

Àkàngbé, C. A. (2007) *Ayégún*. Ìbàdàn: Cornerstone Communications.

**Ìpín Karùn-ún: Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ Àkóónú**

1.0 Ìfàárà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

4.1.1 Ìsọníṣókí Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

4.1.2 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

4.1.3 Ìfìwàwẹ̀dá inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

4.1.4 Ìlò-Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

**Ìfáàrà**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ ni a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀. Àwọn ohun tí a ó sì máa jíròrò nípa wọn ni kókó ọ̀rọ̀, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò-èdè.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- ṣe ìsọníṣókí eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*.
- ṣàlàyé àwọn kókó tó súyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ yìí.
- jíròrò lórí ìlò-èdè Ìṣọ̀lá nínú *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Àwọn kókó ọ̀rọ̀ wo ló súyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*?

2. Ọ̀nà wo ni Ìṣọ̀lá gbà fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ?

3. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò èdè Ìṣọ̀lá nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán.*

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Àgbéyẹ̀wò Eré-oníṣe Apilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

#### 4.1.1 Ìsọníṣókí *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

Simisọ́lá ọ̀kan lára àwọn ọmọ oyè ní ìlú Ìpo ni àwọn afọbajẹ panupọ̀ láti fi jẹ́ Ọba. Bí ó tilẹ̀ ẹ́ pé ifá kò fọre nípa Simisọ́lá síbẹ̀ àwọn afọbajẹ rii dájú pé Ṣiyanbọ́lá di ọba, nítorí àwọn ìlérí ọlọ́kanòjọ̀kan àti àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí àwọn afọbajẹ ti gbà ni ọwọ́ rẹ̀. Ní kété tí Simisọ́lá gorí itẹ, ó gbàgbé gbogbo ìlérí tí ó ṣe fún àwọn ará ìlú. Ó kọ láti mú ìlérì rẹ̀ ṣẹ lórí ilẹ̀ tó ní òun yóò fún àwọn ẹgbẹ́ Alájùmọ̀ṣe láti fi dá oko. Dípò ìdẹ̀rùn, ìnira àti wàhálà ni Simisọ̀lá kó bá àwọn ará ìlú. Gbogbo àwọn tí Adédùn, Olorì Sìyanbọ́lá lérò pe ó lè jẹ́ ìdíwọ́ fún ọkọ òun láti jẹun sínú ni ó dá ẹ̀mí wọn légbodò. Èyí tí ó ṣeni láàánú jùlọ ni Ọláwépọ̀ ọmọ ọba tí àwọn asekúpani tí Adédùn rán níṣẹ́ pa nínú gbọ̀ngàn ìpàdé ti ilé-ìwé gíga Ìpo.

Bákan náà ni Adédùn gbèrò láti pa Fáṣakin, ọ̀kan pàtàkì lára ọmọ ẹgbẹ́ Alájùmọ̀ṣe ṣùgbọ́n orí kó o yọ. Adédùn ṣi ipò rẹ lò gẹ́gẹ́ bí olorì Ọbà, bẹ́ẹ̀ ni kò gbá Simisọlá láàyè láti ṣe ojúṣe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe tọ, àti bó ṣe yẹ. Ní ìgbà ti ọ̀rọ̀ dójú ẹ̀ tán àwọn ìjòyè ìlú tí wọn kò faramọ onírúurú ìwà ìbàjẹ́ ti Simisọlá àti Ayédùn ìyàwó rẹ̀ ń hù dá a lábàá pé kí ọba àti àwọn ìjòyè lọ búra níwájú irúnmọlẹ̀ kí òpin lè dé ba gbogbo rògbòdìyàn tó ń lọ láàrin ìlú Ìpo. Gbogbo akitiyan Simisọ́lá láti dabarú ìbúra pàbó ló já sí torí àwọn ara ìlú gbe ìjà ara wọn báyìí ni òpin dé bá ìjọba aninilára ní ìlú Ìpo.

### 4.1.2 Kókó inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

Kókó méjì pàtàkì tí ó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ni ìfẹ́ owó àfẹ́jù àti àṣìlò ipò.

**Ìfẹ́ Owó Àfẹ́jù**

Ìfẹ́ owó àfẹ́jù ni kókó pàtàkì tó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ. Ìfẹ́ owó àfẹ́jù ló mú bàbá arúgbó ti ọfọ̀ bọnu ni gbọ̀ngàn ti àwọn afọbajẹ ti fẹ́ ṣé ìpàdé, kódà ó da oògùn sílẹ̀ nínú gbọ̀ngàn náà kí Simisọ̀lá ba à lè wọlé. Ọ̀rọ̀ owó tí bàbá arúgbó yóò gbà lọ́wọ́ Simisọ̀lá tí ó bá di ọba tán ló mú un gba ọmọ rẹ̀ níkòó lórí lẹ́ẹ̀mejì ní ìgbà tí ó rí i pé àwọn afọbajẹ kan fẹ́ ká a mọ inú gbọ̀ngàn ìpàdé. Bàbá arúgbó gbàgbọ́ pe òun yóò di ọlọ́rọ̀ rẹpẹtẹ tí Simisọ̀lá bá di ọba ìlú Ìpo ṣùgbọ́n asán ni ìgbẹ́kẹ̀lé bàbá arúgbó yìí jásí. Bákan náà, Àyànlọlá gbékẹ̀lé ìlérí tí Similọ̀lá ṣe fún un, ó sì gbàgbọ́ pé ni kété tí ọba Simisọ̀lá bá ti gorí àléfà ni ìrọ̀rùn yóò dé bá òun. Ìrètí ọjọ́ iwájú tí Àyànlọlá gbàgbọ́ pé yóò dára fún òun nípasẹ̀ Simisọ̀lá ló ṣe ń kìlọ̀ fún ìyàwó rẹ̀ Sẹ̀gí pé kí ó tọ́jú òun dáradára bí bẹ́ẹ̀ kọ́ nígbà tí òun bá bọ́ sínú ọla àti ọrọ̀ lẹ́yìn ìwúyè ọba Simisọ̀lá pípààrọ̀ ni òun yóò pàrọ̀ Ṣẹgi pẹ̀lú òló ẹlẹ́jẹ̀ tútù. Gbogbo ìgbẹ́kẹ̀lé Àyànlọlá àti àlá rẹ̀ láti di ọlọ́rọ̀ nípasẹ̀ Simisọ̀lá parẹ́ mọ́ ọn nínú bí isó ni torí Simisọlá kàn fi èrú gba ìfẹ́ Àyànlọlá lásán ni. Ìfẹ́ owó àfẹ́jù yìí kan náà ló mú àwọn afọbajẹ́ kọ̀ jálè pé Simisọlá ní àwọn fẹ́ gẹ́gẹ́ bí Ọba bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ifá kò fọre nípa rẹ̀. Yorùbá bọ̀ wọ́n ni "bí ẹnu bá jẹ, ojú á tì". Owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí àwọn afọbajẹ́ ti gbà ni ó jẹ́ ki wọ́n takú pé Simisọlá làwọn fẹ́ bí wọn tilẹ̀ ti mọ̀ pé Simisọ́lá kò lè ṣe ìlú Ìpo ni àǹfààní. Borí gbogbo rẹ̀, Simisọlá tí àwọn afọbajẹ àti mẹ̀kúnnù jà raburabu pé dandan ni kó de ipò ọba nítorí àwọn ìlérí tí ó ṣe fún wọn gbàgbé gbogbo ìlérí rẹ̀ ni kété tí ó gorí àléfà. Nítorí ìfẹ́ owó àfẹ́jù, Simisọ̀lá fi ilẹ̀ tó ṣe ìlérí láti fún àwọn mẹ̀kúnnù láti dákó kọ́ ilé ìtura. Ìdámẹ́wàá tí àwọn agbáṣése yóò fún Simisọ̀lá ká a lára ju ìgbáyégbádùn àwọn ara ìlú lọ. Ayé ti yẹ Simisọ̀lá báyìí oríṣìíríṣìí ìwà ìbàjẹ́ ló sì ń hù.

**Àṣìlò Ipò**

Adédùn gẹ́gẹ́ bí olorì Ọba ṣi ipò rẹ̀ lò nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Gẹ́gẹ́ bí ìyàwó ọba, ohun tí ó to ni kí Adédùn máa gba ọkọ rẹ̀ nìmọ̀ràn lórí bí ìlú yóò ṣe tẹ̀síwájú ṣùgbọ́n nínú eré onítàn yìí Adédùn ṣi ipò rẹ̀ lò. Adédùn fẹ́ máa gba owó oṣù láìṣe iṣẹ́

kankan, ṣùgbọ́n Símisọ̀lá lòdì sí èyí. Bákan náà, gbogbo ìgbà tí Similọ̀lá bá ti ń ronú àti ṣe ìfẹ́ àwọn tó ń jọba lé lórí ni Adédùn máa ń takò ó. Adédùn kó ipa pàtàkì nínú ìkùnà Simisọ̀lá gẹ́gẹ́ bí Ọba. Olùdámọ̀ràn burúkú ni Adédùn jẹ́ fún ọkọ rẹ̀. Ọba Simisọ̀lá náà ṣi ipò rẹ lò torí ó pa ọwọ́ pọ̀ pẹ̀lú Adédùn láti máa dún koókó mọ́ àwọn mẹ̀kúnnù. Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n yan àwọn ọlọ́pàá níṣẹ́ láti máa dojú ìjà kọ́ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ àlájùmọ̀ṣe. Simisọ̀lá tí ó jẹ ọba ìlú, ti ó yẹ́ kí ó máa jà fún àlàáfíà àti ìfọ̀kànbalẹ̀ àwọn ará ìlú rẹ̀ ló wá ń fi ẹ̀tọ̀ wọn dùn wọ́n, tó sì tún ń pa wọn, àṣìlò ipò lèyí. Baṣọ̀run àti àwọn afọbajẹ yòókù náà ṣi ipò wọn lò. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n mọ̀ pé Simisọ̀lá kò le ṣèlú lọ́nà tó tọ́, ohun tí wọn yóò jẹ àti èyí tí wọ́n ti gbà kò jẹ́ kí wọ́n le ṣe ìdájọ́ òdodo. Èyí si fa wàhálà àti ìdàámú bá gbogbo àwọn ará ìlú Ìpo.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Ìwà ẹ̀tàn àti àrékérekè gbogbo tí àwọn olóṣèlú àti àwọn olórí ìjọba máa ń hù, èyí tí ó máa ń jẹ́ kí àwọn olùdìbò yan ẹni tí kò tọ́ sórí àléfà ni Ìṣọ̀lá pàṣamọ̀ rẹ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* Ìran mẹ́wàá ni Ìṣọ̀lá pín eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* sí. Ìran kìn-ín-ní ni bàbá arúgbó kan ti wa sa òògùn sí gbọ̀ngàn ìpàdé tí àwọn afọbajẹ fẹ́ lò. Ó si pe ọfọ̀ pé Simisọ̀lá ni kí àwọn afọbajẹ yàn gẹ́gẹ́ bí ọba ìlú Ìpo. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ifá kò-fọre nípa Simiṣọ̀lá síbẹ̀ àwọn afọbajẹ fẹnukò pé kí wọ́n fi Simiṣọ̀lá jẹ Ọba Ìpo. Ìran kejì ni òǹkọ̀wé ti fi Àyànlọlá àti ìdílé rẹ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí òtòṣì. Àyànlọ̀lá tòṣì debi pé kì í rowó fún ìyàwó rẹ̀ láti fi se ọbẹ̀. Àyànlọlá ní ìgbẹ̀kẹ̀lé nínú Simisọ̀lá tí ó ti lerí fún un pé yóò jẹ olórí onílù láàfin òun ní kété tí òun bá gori ìtẹ́, èyí ló sì mú ki Àyànlọ̀lá máa kọrin ire ki Simisọ̀lá. Nínú ìran kejì yìí náà ni Oyinadé ti ka Simiṣọ̀lá mọ́ ọkàn nínú àwọn onífàyàwọ́.

Nínú ìran kẹta ni Ọba Simisọ̀lá àti Adédùn ti jíròrò lórí ọ̀nà ti wọn lè gbà kowó jọ torí ọjọ́ ọ̀la. Àwọn ìyálọ́jà pàrọwà sí kábíyèsí pe kí Káńsùrù gba gbogbo ìsọ̀ padà lọ́wọ́ alágbàtà. Kábíyèsí Ọba Simisọ̀lá ṣe ìlérí fún àwọn ìyálọ́jà láti pa àṣà aláìnàrun lórí ìsọ̀ ọjà. Baṣọ̀run Oyinadé àti Òní mú agbaṣẹ́ṣẹ wá sì ọ̀dọ̀ Simisọ̀lá wọ́n sì gbà á nímọ̀ràn láti fi ilè to ṣe ìlérí fún àwọn mẹ̀kúnnù kọ ilé ìtura. Nítorí ìdámẹ́wàá àti lọ́nà àti jẹun sínú, Simisọ̀lá da àwọn mẹ́kúnnù o sì gba láti fi ilẹ̀ tó ṣèlérí fún àwọn mẹ̀kúnnù kọ́ ilé ìtura. Ayé ti yẹ Simisọ̀lá tan, ìwà ìbàjẹ́ sì ti di bárakú fún un báyìí, ọ̀rọ̀ ifá ti ṣẹ. Ìran kẹrin ni àwọn ẹgbẹ́

Alájùmọ̀se ti pàdé ni gbọ̀ngàn ilé ìwé gíga Ìpo fún àpérò. Torí wọ́n gbàgbọ́ pé “àìláṣọ lọ́rùn pàká, ó tó àpérò ọmọ eríwo”. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe fẹnukò pé àwọn gbọdọ̀ já ara wọ́n gbà lọ́wọ́ àwọn ọ̀jẹ̀lú ti wọn ń pe ara wọn lòṣèlú. Àwọn adárí ẹgbẹ́ fi ye àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yòókù pé láti ja àjàbọ́ àwọn kò gbọdọ̀ gbà láti fi ẹran ikún gbọ́n ti àgbọ̀nrín dànù. Lójijì àwọn ọlọ́pàá da ìpàdé àwọn ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe rú bẹ́ẹ̀ ni àwọn jàǹdùkú náà tún pa ọmọ Ọba Ọláwépọ̀. Èyí fi Simisọ́lá àti Adédùn hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀dájú àti ìkà. Ajé pé Ọba Simisọ́lá àti àwọn ìsọmọgbé rẹ̀ sí àsè láti fi ìmoore ilé-iṣẹ́ rẹ̀ hàn fún iṣẹ́ tí wọ́n gbé fún wọn. Àwọn jàǹdùkú jabọ iṣẹ́ wọn fún olorì Adédùn inú rẹ̀ sì dún pé Ọláwépò ti kú. Ìbẹ̀rù gba ọkan Adédùn ní ìgbà tí ìròyìn kàn án lára pé ọwọ́ tẹ ọ̀kan lára àwọn jàǹdùkú tó rán níṣẹ́, ṣùgbọ́n Simisọ́lá fi í lọ́kàn balẹ̀. Ní ìran karùn-ún àwọn ẹgbẹ́ Àjùmọ̀ṣe ṣe ìpàdé bòǹkẹ́lẹ̀ wọ́n sì pinnu láti da àpèjẹ tí àwọn olórí fẹ ṣe ni Sátidé rú. Basọ̀run àti Ọ̀ní ta Ọba lólobó pé àwọn kan fẹ́ da àsè ru. Fún ìdí èyí ki gbogbo wọn múra gírí. Ọ̀bí fi àbùkù kan Ọ̀ní fún ọmọ rẹ̀ Jọláadé tí ó ń gbé kiri. Ìjà ń lá bẹ sílẹ̀ láàrin àwọn ọmọ ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe àti àwọn jàǹdùkú, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló sì farapa. Ìran kẹfà ni Ọ̀ní ti pé Sọ̀fíọ̀ láti pín ilẹ̀ ìjọba tó sẹ́kù fún Kábìyèsí àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ṣùgbọ́n Sàmù kọ̀ jálẹ̀ pé òun kò fẹ́ ilẹ̀ ìjọba. Sàmú fi ẹjọ́ sun Ọ̀bí àti àwọn yòókù rẹ̀. Àyànwálé àti Ọ̀bí sì di aṣọ mọ́jú lọ bá àwọn ìjòyè, wọ́n lu Ọ̀ní ní àlùbàjẹ́.

Ìran keje ni àwọn ìjòyè Ọba Simisọ́lá ti ránṣẹ́ sí i pé wọn fẹ bá a ṣe ìpàdé pọ̀. Àwọn olóyè pinnu láti fi àìdùnnú wọn hàn sí gbogbo ìwà ipá àti ìpànìyàn ti Simisọ́lá gùnlé. Básọ̀run àti Aṣípa lo oògùn bẹ́ẹ̀ni wọ́n sín gbẹ́rẹ́ tórí ìpàdé tí wọ́n fẹ́ lọ. Ọba rọ Ọ̀ní láti tẹ̀lé e lọ sí ìpàdé àwọn olóyè ó sì gbà, ṣùgbọ́n àwọn olóyè kò gba Ọ̀ní láàyè láti dúró sí ibi ìpàdé wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Simisọ́lá fẹ́ lo agídí, ṣùgbọ́n àwọn olóyè fi yé e pe igi kan kò lè dá igbó ṣe. Ìpàdé àárín Kábíyèsí àti àwọn ìjòyè rẹ̀ gbóná yanyan àwọn olóyè sì pè fún ìbúra ọba àti gbogbo ìjòyè. Èyí sì mu ìbẹ̀rù bójò ba Ọba Simisọ́lá àti àwọn alátilẹ̀yìn rẹ̀. Ní ìran kẹjọ, olorì Adédùn tẹ̀síwájú lórí ìmúrasílẹ̀ fún ayẹyẹ ọjọ́ ibi rẹ̀ bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ìlú kò fararọ́ èyí kò kan olorì Adédùn. Àwọn ìyálọ́jà kọ̀ láti ra aṣọ ọjọ́ ibi olorì bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọ ilé-ìwé kò ṣetán láti wá kọrin ìbílẹ̀ fún olorì. Pabanbarì rẹ̀ ni pe Àyànlọ́lá náà kọ̀ láti wa lu ìlù níbi ayẹyẹ ọjọ́ ìbí olorì èyí lo mú olorì Adédùn pàsẹ pé kí wọn ti Ayan mọ́lé. Simisọ́lá jábọ̀ ìpàdé ti wọn lọ fún Adédùn, o sì bú sẹ́kún gbaragadá ṣùgbọ́n kábíyèsí fi í

lọ́kàn balẹ̀. Simisọ́lá àti àwọn alátìlẹ́yìn rẹ̀ ṣètò àwọn jàǹdùkú láti da ìbúra níwájú irúnmọlẹ̀ rú. Ìran kẹsàn-án ni àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Àjùmọ̀se ti gbéra láti lọ sí oko láti béèrè fún ìrànwọ́, ṣùgbọ́n sí ìyálẹ́nu wọn, wọn pàdé Fáṣakin ti wọ́n lérò pé ó ti kú. Fáṣakin mú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yòókù padà sí abúlé lẹ́yin àlàyé wọn, àwọn ara abúlé pinnu láti ràn wọ́n lọ́wọ́. Àrọ̀nì sì bá wọn padà sí ìlú Ìpo. Fásakin, Àrọ̀nì, àti àwọn yòókù rẹ̀ ló gba Àyànlọ́lá sílẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ọlọ́pàá.

Ìran kẹwàá wáyé ni ojúbọ Irúnmọlẹ̀ nínú igbó ńlá kan. Gbogbo ètò ti ọba Similọ́lá ṣe láti da ètò ìbúra ni ojúbọ Irúnmọlẹ̀ rú ló padà forí ṣánpọ́n. Àwọn ìjòyè yòókù tí kò gbàbọ̀dè àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Àjùmọ̀se parapọ̀ gba ara wọn sílẹ̀ lọ́wọ́ ìjọba amúnisìn àti apàniyàn. Ó hàn gbangba nínú àhunpọ̀ ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* pé ìpinnu àwọn ara ìlú Ìpo láti gba ara wọn sílẹ̀ lò mu wọn ja àjàbọ́ bí bẹ́ẹ̀ kọ wọ̀n kò bá jìyà pẹ́ lọ́wọ́ àwọn alágbára tó ń fọwọ́ ọlá gbá wọn lójú.

**Ibùdó-Ìtàn**

Ibùdó-ìtàn gbogbogbòò ni ó wà nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ni ìlú Ìpó. Bákan náà a lè fi ìlú Ìpó wé orílẹ̀ èdè Nàìjíríà nítorí gbogbo ìwà ìbàjẹ́ oríṣìíríṣìí tó farahàn nínú ìlú Ìpó ló kún orílẹ̀ èdè Nàìjíríà dẹ́nu. Ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ìfẹ́ owó àfẹ́jù ló ń mú ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn yan ẹni tí kò tọ́ tàbí kojú òsùwọ̀n sí ipò àṣẹ. Tí a ba sọ pe orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ni Ìṣọ̀lá ń pàsamọ ìlànà ìṣèlú rẹ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*, a kò jayò pa. Àwọn ibùdó ìtàn pàtó nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ni gbọ̀ngàn ìlú Ipo, Ilé Àyànlọ́lá, Ààfin Ọba Ìpo, Ilé Ajé, Ibi àpejẹ, Ilẹ̀ Ìjọba, búkà ẹlẹ́mu, Ilé Baṣọ̀run, ọ̀nà oko àti ojúbọ Irunmọlẹ̀.

### 4.1.3 Ìfiwàwẹ̀dá inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

Ọna tí Ìṣọ̀lá gbà fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ni a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ ní abala yìí. Àwọn ẹ̀dá-ìtàn tí a ó sì máa sọ̀rọ̀ nípa ìfiwàwẹ̀dá wọn ni Simisọ́lá, Adédùn, Bàbá Arúgbó, Àyànlọ́lá, Baṣọ̀run, Òní àti Òbìadé.

**Simisọ̀lá**

Olú ẹ̀dá-ìtàn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ni Simisọ̀lá jẹ́. Nípa ìwà ẹ̀tàn àti àrekèrekè àwọn ìjòyè àti ará ìlú Ìpo fi Simisọ̀lá ṣe Ọba wọn pẹ̀lú ìrètí pé ni kété tí o di ọba Ìpo ni ìlú yóò dẹrùn fún tẹrú tọmọ. Ní kété ti Simisọ̀lá di ọba ìlú Ìpo, ó gbàgbé àwọn mẹ̀kúnnù bẹ́ẹ̀ ni kò náání àwọn ìjòyè rẹ̀. Simisọ̀lá ni ọba ti ayé yẹ tán, tí ó sì bẹ̀rẹ̀ ìwà ìbàjẹ́ ọlọ́kanòjọ̀kan. Ẹṣin obìnrin ni Ọba Simisọ̀lá ń gùn. Gbogbo ìmọ̀ràn burúkú ti Ayédùn ìyàwó rẹ̀ àti ale rẹ̀, Oyinadé ń gbà á ló múlò. Èyí ni ko si jẹ́ kí o lè mú ìlérí tí ó ti ṣe kí ó tó gun orí àléfà ṣẹ. Ọ̀dájú àti ìkà ẹ̀dá-ìtàn ni Ọba Simisọ̀lá. Dípò, kí ó máa wá ìdẹ̀rùn àti ìfọ̀kànbalẹ̀ fún àwọn ará ìlú rẹ̀, ìdààmú àti wàhálà ni ó kò àwọn ará ìlú sí. Ọ̀jẹ̀lú àti onífàyàwọ́ Ọba ni Simisọ̀lá. Ní ìgbà tí ago ìwà ìkà Simisọ̀lá kún àkúnwọ̣sílẹ̀, àwọn ìjòyè pàṣẹ pe ki wọ́n búra ni ìdí Irunmọ̀lẹ̀. Gbogbo ipá àti agbára ni Ọba Simiṣọ̀lá sà kí ìbúra níwájú Irunmọ̀lẹ̀ lè forí ṣánpọ́n, ṣùgbọ́n àwọn ará ìlú kò gbà fún un. Ìkà yóò ka oníkà, rere á bẹ́ni rere.

**Adédùn**

Olorì Ọba Siyanbọ̀lá ni Adédùn. Ìkà, ọ̀dàjú àti apànìyàn ẹ̀dá ni Adédùn. Ẹ̀mí ènìyàn kò jọ Adédùn lójú rárá. Adédùn tún ni ìfẹ́ owó láfẹ̀jù èyí ló jẹ ki o pe àwọn jàǹdùkú láti pa. Ọláwépọ̀, ọ̀kan pàtàkì nínú ẹgbẹ́ Àjùmọ̀se. Bákan náà, Adédùn gbìyànjú láti pa Fáṣakin pẹ̀lú ṣùgbọ́n orí kó o yọ. Gbogbo ìmọ̀ràn burúkú tí Adédùn fún ọba Simisọ̀lá láti lọ́wọ́ ni kò jẹ kí o lè ṣe ohun kan tó ní láárí fún àwọn ara ìlú Ìpo. Bí gbogbo ìlú ṣe ń dàrú kò tu irun kankan lára Adédùn, ṣe ni ó múra sí ìmúrasílẹ̀ ayẹyẹ ọjọ́ ìbí rẹ̀. Adédùn tilẹ̀ tún gba igba isọ lọ́jà tí ó sì wá gbé e kalẹ̀ lọ́wọ́ gegere fún àwọn ará ìlú, èyí sì fi hàn gẹ́gẹ́ bí ìyàwó burúkú àti onímọ̀ràn burúkú fún ọkọ rẹ̀. Àìláṣeyọrí Ọba Simisọ̀lá gẹ́gẹ́ bí
Ọba ìlú Ìpo kò sẹ̀yìn olorì rẹ̀, Adédùn.

**Àyànlọ̀lá**

Onílù ni Àyànlọ̀lá, ó sì tún jẹ́ ọkọ Ṣẹ̀gilọlá àti bàbá Àyánníyì. Kí Simisọ̀lá tó di Ọba Ìpo ló ti ṣèlérí fún Àyànlọ̀lá pé òun yóò ràn-án lọ́wọ́ lórí ilẹ̀ ọnà odò tí àwọn ọ̀gá ìgbìmọ̀ ìjọba ìbílẹ̀ fẹ́ ẹ́ dàrú. Bákan náà ni ó tún ṣèlérí láti sọ Àyànlọ̀lá di ọ̀gá onílù láàfin tí yóò máa

gba owó oṣù. Gbogbo ìlérí tí Simisọ́lá ṣe fún Àyànlọ́lá ló jẹ́ kí Àyànlọ́lá máa kọrin ire ki Similọ́lá ni gbogbo ìgbà. Simisọ́lá kan fi èrú gba ìfẹ́ Àyànlọ́lá lásán ni torí Ọba Simisọ́lá kò mu gbogbo ìlérí tí ó ṣe fún Àyànlọ́lá ṣẹ. Inú Àyànlọ́lá bàjẹ́ ni ìgbà ti gbogbo àgbọ́kànlẹ́ rẹ̀ jásí asan èyí ló mú wọn kọ jalẹ̀ láti lọ kọrin ni ibi ayẹyẹ ọjọ́ ìbí olorì Adédùn. Orí ló kó Àyànlọ́lá yọ, bí bẹ́ẹ̀ kọ́ àwọn ọlọ́pàá kò bá fi ojú rẹ̀ rí màbo. Akúṣẹ̀ẹ́ àti aláìlágbára ẹ̀dá-ìtàn ni Àyànlọ́lá jẹ́.

**Bàbá Arúgbó**

Àrokò àwọn ẹ̀dá-ìtàn tó fẹ roko sí ọdọ ara wọn ni bàbá arúgbó ń pa. Àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí àwọn olólùfẹ́ Simisọ́lá fún bàbá arúgbó ló jẹ́ kí ó kọ da oògùn sílẹ̀ si inú gbọ̀ngàn tí àwọn afọbajẹ ti fẹ ṣe ìpàdé tí ó sì pọ́fọ̀ pé dandan ni kí Simisọ́lá di Ọba ìlú Ìpo. Ìhùwàsí bàbá arúgbó yìí sí ọmọ rẹ̀ nínú gbọ̀ngàn ìlú Ìpo fi hàn gbangba pé bàbá arúgbó yìí kò fẹ ki ohunkòhun dènà àti gorí ìtẹ́ Simisọ́lá, èyí ló sì jẹ́ kí ó kan ọmọ rẹ̀ níkòó lórí láìbìkítà. Ó ṣeni láàánú pé gbogbo wàhálà bàbá arúgbó yìí kò so èso kankan fún ún nítorí Simisọ́lá kò rántí bàbá arúgbó mọ́ ní ìgbà tí ó gorí oyè. Àtẹ̀gùn lásán ni Simisọ́lá fi bàbá arúgbó ṣe láti de orí ìtẹ́.

**Òbílàdé**

Ọlọ́pàá ni Òbílàdé, ó sì tún jẹ́ bàbá Jọláadé. Akúsẹ̀ẹ́ ni Òbílàdé, èyí ló sì jẹ́ kí ó máa halẹ̀ mọ́ àwọn ènìyàn ní ìgboro láti gbà owó lọ́wọ́ wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Òbílàdé mọ̀ pé àbẹ̀tẹ́lẹ̀ gbígbà kò dára síbẹ̀ ó gbà á lọ́wọ́ Oyinadé kí ó lè fi san owó aṣọ ọmọ rẹ̀ Jọláadé. Òbílàdé gbà pe ìṣe tí ó ń bá òun fínra ló jẹ́ ki òun máa jẹ oúnjẹ ọ̀tá òun. Òbílàdé pinnu láti síwọ nínú ríbà gbígba nítorí kò fẹ́ fi ẹran ikún gbẹran àgbọ̀nrin dànù. Ìṣẹ́ tí ó ń bá Òbílàdé fínra tì kò jẹ́ kí o rí owó gidi fún ọmọ rẹ̀ Jọláadé tó wà ní ilé ẹ̀kọ́, èyí sì sọ Jọláadé di aṣẹ́wó fún àwọn olówó. Òbílàdé kùnà gẹ́gẹ́ bí òbí nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Òbílàdé faraya ni ìgbà tí ó mọ̀ pé Jọláadé ń tẹ̀lé àwọn olówó kiri bẹ́ẹ̀ ni ó gbẹ̀san ìyà tí Òní fi jẹ ẹ́. Àpẹẹrẹ àwọn ọlọ́pàá tí ó máa ń gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ ni Òbílàdé jẹ́.

**Baṣọ̀run**

Ọ̀kan pàtàkì lára àwọn afọbajẹ ìlú Ìpo ni Baṣọ̀run. Owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí Baṣọ̀run ti gbà lọ́wọ́ Simiṣọ́lá lo jẹ́ kí ó takú pé Simiṣọ́lá ni o gbọdọ̀ di Ọba Ìpó. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ifá kò fọ rere nípa Simisọ́lá, síbẹ̀ Baṣọ̀run fi ọgbọ́n àyínìke mú àwọn afọ́bajẹ yòókù láti fọwọ́ sí Simisọ́lá gẹ́gẹ́ bí Ọba tuntun. Ìfẹ́ owó àti àìnífẹ̀ẹ́ ará ìlú lọ́kàn ni Baṣọ̀run fi takú pe Simisọ́lá ni kí ó jọba. Baṣọ̀run wà lára àwọn tí ó ń fún Ọba Simisọ́lá ni ìmọ̀ràn búburú, èyí tí kò jẹ kí ó se ìfẹ́ àwọn ara ìlú Ìpo. Baṣọ̀run jẹ ẹ̀dá-ìtàn oníṣẹ ibi, o fi oògùn ṣe ìgbékẹ̀lé rẹ, kódà o mu lára oògùn yìí wá fún Ọba Simisọ́lá. Ìmọtara-ẹni-nìkan ló mú Baṣọ̀run hu gbogbo ìwà ibi tó hù.

### 4.1.4 Ìlò-Èdè inú Eré-oníṣe Àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*

Ọ̀nà tí Ìṣọ̀lá gbà lo èdè nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ni a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ ni abala tí a wà yìí. Ògúnná gbòǹgbò tíí dátọ́ lẹ́nu ìgbín ni Ìṣọ̀lá jẹ́ tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìlò-èdè. Èròjà alohùn ni ó sì jẹ́ bárakú fún Ìṣọ̀lá nínú àwọn iṣẹ́-ọnà rẹ̀. Bákan náà nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán,* Ìṣọ̀lá ṣàmúlò àwọn èròjà alohùn lọ́pọ̀lọpọ̀. Àwọn èròjà alohùn tí a ó sì máa jíròrò nípa wọn ni ọfọ̀, orin, ìwúre, òwe àti ẹsẹ ifá.

**Ọfọ̀**

Ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tó lágbára, tó sì ní ètò ní ọfọ̀ jẹ́. Ọfọ̀ ṣe pàtàkì nínú àṣà Yorùbá, oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni a sì máa ń gbà lò ó. A le lo ọfọ̀ fún ìtọ́jú tàbí ìdáàbòbò ara. Bẹ́ẹ̀ ni a máa ń lo ọfọ̀ fún arọ́bi èyí ni láti gba ara wa sílẹ̀ lọ́wọ́ ọ̀tẹ́. Ọfọ̀ tún jẹ́ ohùn tí a ń fọ̀ jáde lẹ́nu láti mú ki ohun tí a fẹ́ ṣẹ. Nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán,* bàbá arúgbó pe ọfọ̀ sí òògùn tó dà sórí aṣọ pé Simisọ́lá ni àwọn afọbajẹ gbọdọ̀ yàn.

> Àjẹ gbémì ni ti kàlòkàlò
> Tiletọ̀nà la fi í jin ológìnní
> Ekukéku kìí rìn kó borí asín
> Èèrà kéèrà kì í rùn kó borí ìkamọ̀dù
> Ọ̀tún làá tàkòtó.
> Òsì labiyamọ ń damọ rẹ̀ sí (o.i. 21)

**Orin**

Ìṣọ̀lá ṣàmúlò orin lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Oríṣìíríṣìí sì ni àwọn orin tí Ìṣọ̀lá lò. Bí a ṣe ri orin ìkìlọ̀ àti orin amóríyá, bẹ́ẹ̀ ni orin ìgbàgbọ́ àti orò súyọ. Orin ìṣẹ́gun àti èhónú náà kò gbẹ́yìn. Bí àpẹẹrẹ àwọn ìyálọ́jà kọ orin ẹ̀hónú lọ sí ilé ọba pé àwọn kò lè faramọ́ ìwà búburú rẹ̀ mọ́. Wọ́n kọrin báyìí pé;

**Orin:** Àwa ò gbà mọ o
Óníye, e ò gbóhùn mi
Àwa ò gbá mọ́ o
Ká ṣanwó èlé o
Ká tó le rí búkà
Àwa ò gbà mọ́ o (o.i 43)

Àwọn àpẹẹrẹ orin tún wà ní ojú ìwé 4, 14, 17, 18, 19, 20, 21, 26, 38, 151.

**Òwe**

Ìṣọ̀lá lo òwe lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* èyí sí tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ síi pé òǹkọ̀wé tí ó gbọ́ èdè, tí ó sì mọ̀ àgbékalẹ̀ èdè ni Ìṣọ̀lá jẹ́. Bí àpẹẹrẹ wó ọ̀rọ̀ tí Ayanlọ̀lá sọ ni ìsàlẹ̀ yìí

Erèé tó rún náà ló mú gbẹ̀gìrì ṣàn.
Àrífín wọ̀nyí yóò dópin láìpẹ́.
Ó ń wa owó nínú àpò agbádá rẹ̀,

Àyànlọlá ló pa òwe òkè yìí ní ìgbà ti Sẹ̀gilọlá gba kọ̀ǹgọ́ tí ó fi ń lu ìlù lọ́wọ́ rẹ̀. Àyàn pa òwe yìí láti fi ye Ṣẹ̀gilọlá pe àìlówó lọ́wọ́ òun ni Ṣègi ṣe ń rí òhun fín. Fún àpẹẹrẹ òwe síi wo ojú ìwé 23, 24, 30, 31, 32, 36, 41, 45.

**5.0 Ìsọníṣókí**

Ìmọtara-ẹni-nìkan àti àṣìlò ipò láti ọ̀dọ̀ àwọn olórí olóṣèlú ni kókó tó farahàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Ìran mẹ́wàá ni àhunpọ̀ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* pín sí. Àwòta

ìṣèlú àti àwọn òṣelú orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ni *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* jẹ. Ònkọ̀wé eré onítàn *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ṣàmúlò ewì alohùn láti fi wa kókó ọ̀rọ̀ àti àhunpọ̀ eré náà gúnlẹ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kókó pàtàkì wo ni ó jẹyọ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*.
2. Ṣàlàyé kíkún lórí ìlò ewì alohùn fún ìgbékalẹ̀ kókó ọ̀rọ̀ àti àhupọ̀ ìtàn *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéjùmọ̀ A. (2006) Yorùbá Drama II. Ìbàdàn: Distance Learning Centre, University of Ibadan.

Ìṣọ̀lá, Akínwùmí. (2009) *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Ìbàdàn: DB Martoy Books.